IITA
Transforming African Agriculture

AMBASSADE DE FRANCE AU NIGÉRIA
Liberté
Égalité
Fraternité

www.iita.org

# ÌLÀNÀ ÌKỌNI LÁTI GBÁRÙKÙ TI ÀWỌN OBÌNRIN ONÍṢÒWÒ AJẸMỌ ẸKA ÀGBẸ-OLÓUNJẸ NÍ NÀÌJÍRÍÀ



Small & Medium Enterprises Development Agency Of Nigeria

FIIRO

NEPC
NIGERIAN EXPORT PROMOTION COUNCIL

# ÀKÓÓNÚ


Ẹ̀kọ́ kìíní....................03

Ẹ̀kọ́ Kejì....................30

Ẹ̀kọ́ Kẹta....................36

Ẹ̀kọ́Kẹrin....................47

Ẹ̀kọ́ Karùn-ún....................53

Ẹ̀kọ́ Kẹfà....................59

Ẹ̀kọ́ Keje....................70

Ẹ̀kọ́ Kejọ....................77

Ẹ̀kọ́ Kẹsàn-án....................84

Ẹ̀kọ́Kẹwàá....................97

Fọ́ọ̀mù ìgbéléwọ̀n fún Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ SWEAN....................102

# ỌRỌ̀ ÀKỌ́SỌ

Ìyípadà ìgbà láti ìdásí ajẹmọ́-ìpesè sí ìdásí ajẹmọ́-ìbèèrè tó dára jùlọ ni ó jẹ́ kí ìfojú-àwùjọ-wò ṣe é ṣe. Ìfojú-àwùjọ-wò yìí ń bẹ̀bẹ̀ pé wọ́n gbọ́dọ̀ mọ àwọn àìní akópa kí wọ́n tó ṣe ètò ìdásí kanakn. Nítorí náà, a ṣe ìdámọ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí àwọn obìnrin oníṣòwò ajẹmọ́-ọ̀gbìn nílò ní Ìbàdàn àti Zaria ti ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ àti Kaduna, níbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ Iṣẹ́-Àkànṣe ajẹmọ́ Ìlànà Ìkọ́ni Láti Gbárùkù ti Àwọn Obìnrin Oníṣòwò ajẹmọ́ Ẹ̀ka Àgbẹ̀-Olóunjẹ ní  Nàìjíríà (SWEAN). Láti kọ́ àwọn Obìnrin Oníṣòwò ajẹmágbẹ̀ látàrí àfo tí a tọ́ka sí, a ṣe àgbékalẹ̀  Ìlànà Ìkọ́ni Láti Gbárùkù ti Àwọn Obìnrin Oníṣòwò ajẹmọ́ Ẹ̀ka Àgbẹ̀-Olóunjẹ ní  Nàìjíríà (SWEAN).

Ìwé ìtọ́ni náà jẹ́ àbájáde àwọn ìṣe ìròrí pẹ̀lú àwọn èèkàn bíi Federal Institute of Industrial Research (FIIRO), Nigerian Stored Product Research Institute (NSPRI), Small and Medium Enterprise Development Agency of Nigeria (SMEDAN), Standard Organisation of Nigeria (SON), Nigerian Export Promotion Council (NEPC), National Agency for Food and Drug Administration and Control (NAFDAC), Oyo State Agribusiness Development Agency (OYSADA) àti Agricultural Development Programmes (ADP) in ìpínlẹ̀ Kaduna. Ìwé ìtọ́ni náà kún fún módù mẹ́jọ ni àwọn agbọn pípèsè àti ríró oúnjẹ lágbára; ìfúnlórúkọ tuntun àti ìṣelọ́jọ̀ọjà; àwọn àlàkalẹ̀ìlànà ìforúkọ ọjà oúnjẹ sílẹ̀ tí àjọ NAFDAC; ìpele ìdára oúnjẹ; títa ẹ̀gẹ́ àti ẹjà; àkọsílẹ̀ àti ìkówèépamọ́; ètò ìṣúná àti ìlànà ìṣirò nínú oko-òwò àti ìdarí àti ìṣàkóso oko-òwò tó láṣeyọrí. A ṣe ìwé ìtọ́ni náà fún ìlò ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí ẹgbẹ́ tí ó gbájúmọ́ ṣíṣe ìgbéláruge fún àwọn obìnrin olókoòwò ajẹmọ́-ìpèsè oúnjẹ ní ojú òpó ìníyelórí tí àwọn obìnrin olókoòwò náà ti mú ní ọ̀kúnkúndùn. Ní àfikún, ìwé ìtọ́ni náà pèsè àwọn ìgbésẹ̀ àti ìtàkún tó rọrùn nínú èyí tí àwọn ọjà lè gbà ní ìwé ẹ̀rí fún lílò lábẹ́lé, títà àti kíkó lọ sókè òkun.

A ṣètò ìwé ìtọ́ni náà lọ́nà tó rọrùn láti bá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ iṣe àwọn obìnrin olókoòwò mu àti àwọn iṣẹ́ tí ó lè mú ìmọ̀ọ̀nṣe wọn gbèrú sí i fún àǹfààní ìfigagbága ní àwọn ọjà abẹ́lé àti ti àgbáyé. Ní àfikún, ìwé ìtọ́ni náà jẹ́ ìtọ́ni tí ó rọrùn láti lò èyí tí a ti túmọ̀ sí èdè Yorùbá àti Hausa láti bá èdè tí àwọn obìnrin náà fẹ́ mu. Fún àwọn obìnrin olókoòwò tí yóò lo àǹfààni yìí láti kópa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ohun-èlò yìí yóò jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ohun ìrántí àti/tàbí ohun ìtọ́kasí àti ohun-èlò láti fi kún òye wọn lórí oníruurú agbọn tí ìwé náà dá lé. Síwájú sí i, fún àwọn obìnrin olókoòwò  tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń díde tí wọn kò kópa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà, yóò jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìtọ́ni láti ṣe ìfáárà sí àwọn kókó, ìlànà, ìgbésẹ̀ àti ìse onípele-dídára tí pípèsè oúnjẹ pè fún. Ìwé ìtọ́ni náà yóò sí ojú ẹnìkọ̀ọ̀kan sí àwọn ọgbọ́n-inú lórí gbígba ìwé-ẹ̀rí fún ọjà àti ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa ṣíṣe ọjà lọ́jọ̀.

Àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ wọ̀nyí kópa nínú síse àgbékalẹ̀ àkóónú ìwé ìtọ́ni yìí: Ọ̀jọ̀gbọ́n Sanni Lateef, Ọ̀mọ̀wé Adebowale Akande, Ọ̀mọ̀wé Babatunde Kosoko, Ọ̀mọ̀wé Oyelakin Michael, Ọ̀gbẹ́ni Oyewale Abioye, Arábìnrin Iyabo Ojogbede, Ọ̀gbẹ́ni Benu Phillips, Arábìnrin Bola Emmanuel, Ọ̀gbẹ́ni Yinka Adetoyi, Ọ̀mọ̀wé Balami Yusuf, Onímọ̀-ẹ̀rọ Oladimeji Kamaldeen, Apòògùn Dauda D. Gimba, Ọ̀gbẹ́ni Badamasi Yau Barau, Ọ̀gbẹ́ni Zacham Bayei.

Chibueze Stanley Nwachukwu ni ó ṣe àgbékalẹ̀ àti ìhunpọ̀ ìwé ìtọ́ni yìí pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ àgbáríjọpọ̀ ọmọ ìgbìmọ̀ iṣẹ́-àkànṣe SWEAN (Martina Adet Edet, Bolanle Oyindamola Adebayo àti Eucharia Ejowokoghene Obar ni ó ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀) tí Sougrynoma Zainatou Sore darí. Ìfarajìn gbogbo àwọn akópa nínú ṣíṣe àgbékalẹ̀ ìwé ìtọ́ni yìí ni a mọ̀ rírì rẹ̀.

# ẸKỌ KÌÍNÍ

# SÍSỌ DI OÚNJẸ





## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala ẹ̀kọ́ yìí jẹ́ ìtọ́ni. Àwọn olùkọ́ lè ṣe àtúnṣe sí agbọn yòówù láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Wọ́n gbọ́dọ̀ bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí á tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

---

### Àwọn èròǹgbà ní pàtó:

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn akópa gbọ́dọ̀ lè mọ bí a ṣe lè:

- Ṣe ìfàgùn sí iye ìgbà/àsìkò tí àwọn ohun oúnjẹ lè lò ní ìpamọ́.
- Dènà ìdibàjẹ́ oúnjẹ.
- ṣètò kíkó oúnjẹ pamọ́ àti kíkó oúnjẹ lọ sí ìrìn-àjò lọ́nà tó rọrùn.
- Yí àwọn ohun-èlò oúnjẹ títù padà sí àwọn ohun tí ó jojú ní gbèsè tí ó sì ṣe é tà lọ́jà.

---

### Ìlapa èrò

- Sísọ di oúnjẹ
- Àwọn ìsọ-di-oúnjẹ
- Ìjẹun-lọ́nà-àìtọ́ àti Ìró-oúnjẹ Lágbára
- Sísọ Ẹ̀gẹ́ di Oúnjẹ
- Sísọ Ẹja Di Oúnjẹ
- Àwọn ìgbésẹ̀ Ríró Ẹ̀gẹ́ Lágbárá
- Àwọn Ìgbésẹ̀ ríró oúnjẹ lágbára mìíràn

---

# ṢÍṢE OÚNJẸ ÀTI RÍRÓ ÈGÉ ÀTI ẸJA NÍ AGBÁRA


**Ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀:** ipa tó ṣe kókó ni àwọn obìnrin ń kó nínú iṣẹ́ àgbẹ̀. Wọ́n jẹ́ ìdá mẹ́talélógójì nínú ọgọ́rùn-ún àwọn òṣìṣẹ́ iṣẹ́ àgbẹ̀ ní àwọn orílẹ̀-èdè tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dàgbà sókè. Ní ilẹ̀ Adúláwọ̀, àwọn ni wọ́n ń pèsè ìdá ọgọ́rin nínú ọgọ́rùn-ún àwọn oúnjẹ tí à ń jẹ lábẹ́lé. Nítorí náà, ìkópa wọn ṣe pàtàkì sí pípèsè àwọn iṣẹ́ fún pípa owó wọlé àti ìkó-oúnjẹ pamọ́ alálòpẹ́.




**Àwòrán 1:** Ìpín àwọn obìnrin nínú ọ̀wọ́ òṣìṣẹ́ iṣẹ́ àgbẹ̀



**Fig 2:** Ìdá ìpín ọkùnrin àti obìnrin fún pípèsè àti sísọ ègé di oúnjẹ




Orísun: FAO 2011




Orísun: Iṣẹ́ Ìwádìí, Nàìjíría, 2008/09

**Table 1: Awọn iṣẹ obirin ni Afirika (%)**

| S/N | Ìṣe/Iṣẹ́ | Àwọn obìnrin | Àwọn ọkùnrin |
|---|---|---|---|
| 1 | Ọ̀gbìn oúnjẹ | 70 | 30 |
| 2 | Kíkó oúnjẹ pamọ́ | 50 | 50 |
| 3 | Iṣẹ́-Àgbẹ́ṣe Ajẹmáwùjọ | 70 | 30 |
| 4 | Títà àti Pípàárọ̀ èrè oko | 60 | 40 |
| 5 | Lílọ̀ àti sísọ di Oúnjẹ | 100 | - |

## SÍSỌ DI OÚNJẸ


Sísọ di oúnjẹ jẹ́ ọgbọ́n yòówù tí à ń lò láti yí àwọn erè oko tútù padà di ohun tí ó ṣe é jẹ. Àwọn ohun tí ó máa ń wáyé lẹ́yìn ìkórè ni yálà títà tàbí jíjẹ.





Ẹ̀gẹ́ → Sísọ Di Oúnjẹ → Gaàrí

## ÀWỌN ỌNÀ ÌSỌ-DI-OÚNJẸ







Yíyan Gaàrí (Ọ̀nà Ìgbàlóde)



Yíyan Gaàrí (Ọ̀nà Ìbílẹ̀)

## Ìjẹun lọ́nà àìtọ́

Ìjẹun lọ́nà àìtọ́ jẹ́ ìsọ̀rí àwọn ipò kan láàrin àwọn ọmọdé àti àgbà, èyí tí ó ní í ṣe pẹ̀lú àìsí tàbí ọ̀wọ́n oúnjẹ asaralóore.






## Àìpé àwọn èròjà aṣaralóore (MNDs)

Àìpé àwọn èròjà aṣaralóore (MNDs) jẹ́ ìṣòro ajẹmọ́ ètò ìlera àwùjọ àgbáyé, pẹ̀lú àwọn obìnrin alábiyamọ àti àwọn ọmọdé tí ọjọ́-orí wọn kò tíì pé ọdún márùn-ún gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹni tí ewu náà ń wu jùlọ.

### Mẹ́ta nínú àwọn àìpé èròjà aṣaralóore lágbàáyé nìwọ̀nyí:

- Àìṣedéédéé Iodine (IDD)
- Àìpé Fítámì Ìsọ̀rí A (VAD)
- Àìtó/Ìdààmú Ẹ̀jẹ̀ (IDA).

### Àìpé èròjà aṣaralóore ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àyọrísí:

- Ó máa ń dá kún ewu dídíbàjẹ́ àti ikú
- Ó ń fa àdínkù bá ìṣàábò ara kúrò lọ́wọ́ kòkòrò/àrùn
- Àìdàgbàsókè dáradára ní ti ara àti òye ọpọlọ
- Àìṣedéedée àti àìṣe-àṣeyọrí lẹ́nu ẹ̀kọ́
- Pípàdánù ńlá níti ojúṣe

## Jíjẹ oúnjẹ tó kún ojú ìwọ̀n ìṣaralóore (Onírúurú Ìjẹun)



Jíjẹ àwọn oúnjẹ tí a ti yípadà láti kún fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ èròjà ìṣaralóore



**Lílo àwọn òògùn afúnni-ní-fítámì**




**Nípa ṣíṣe àfikún àwọn èròjà aṣaralóore sí àwọn oúnjẹ láti ró wọn lágbára sí i**

## Ríró Oúnjẹ Lágbára

*Ẹ̀yí ni ṣíṣe àfikún èròjà kan tàbí òmíràn sí oúnjẹ kan— oúnjẹ, ọjà oúnjẹ, èròjà, tàbí àwọn ohun èròjà mìíràn láti dènà àìtó àwọn èròjà aṣaralóore  kan tàbí òmíràn nínú ìpele olùgbé (Allen et al. 2006).*



Commonly fortified foods




iyo



suga



Iyefun oka ati ti agbado Flour



Miliki




Condiments



Complementary Foods



## ÌSỌ ÈGÉ DI OÚNJẸ


Ẹ̀gé jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn irúggìn oní-gbòǹgbò tí ó ṣe pàtàkì jùlọ tí ó sì ń pèsè agbára fún ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta mílíọ̀nù ènìyàn ó lé. Ó kún fún èròjà afáralókun ṣùgbọ́n díẹ̀ ni èròjà a-so-ẹ̀mí-ró tí ó ní. Ó jẹ́ irúgbìn oúnjẹ, nítorí náà, ó dára gẹ́gẹ́ bí ohun ìsọ di oúnjẹ.



| Àwọn ìṣe ìsọ di oúnjẹ tí kò dára tó | | Àwọn ìṣe ìsọ di oúnjẹ tí ó dára |
|---|---|---|
|  | Fífọ̀ |  |
|  | Sísá |  |
| Akoko rire (ojo me-ji-si ojo meta) |  | Àsìkò rírẹ sílẹ̀ (ọjọ́ márùn-ún sí méje) |
| Yíyan (kò gbẹ dáadáa) |  | Garifying (Well dried) |

# RIRO EGE LAGBARA






## Fífi sóyà ró ẹ̀gẹ́ lágbára

Sóyà jẹ́ ẹ̀yà erèé tí ó ṣe pàtàkì jùlọ ní àgbáyé. Ní ilẹ̀ Adúláwọ̀, ó ṣe pàtàkì fún ìdí mẹ́ta pàtàkì: iṣẹ́ òòjọ́ àti ìpawó wọlé fún àwọn ènìyàn, àwọn àǹfààní ajẹmọ́ ìjẹun àti ìlera, àti ipa lórí ètò ọ̀gbìn alálòpẹ́.


Ewa-soya



Àwòrán 3: Àwọn èròjà àkóónú sóyà

Àwọn oúnjẹ ajẹmọ́-sóyà kan nìyí ìyẹ̀fun sóyà, wàrà sóyà olómi, wàrà sóyà (Bẹskẹ), dawadawa oní-sóyà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. ìfi sóyà ró ẹ̀gẹ́ lágbára ní í ṣe pẹ̀lú gaàrí onísóyà, láfún oní-sóyà, Tàpíókà sóyà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.




Fig 4: Soy Garri Production





Fig 5: Soy Lafun Production






Fig 6: Soy Tapioca Production


# ÌSỌ ẸJA DI OÚNJẸ



Ipinsi ẹja si jijẹ amuaradagba ẹran jẹ 35% fun awọn olugbe ilu ati igberiko ni Nigeria (Maziya-Dixon et al., 2004). Ṣiṣeto ẹja ati tita ni awọn agbegbe ipeja ni Iwọ-oorun Afirika, pẹlu Nigeria, ti jẹ ijabọ bi iṣẹ ṣiṣe "abo" ti o ni nipataki awọn obinrin (Udong et al., 2010)





Aworan keje: Schematic of fish




Aworan kejo: Siso eja di ounje

## Igbese ti o wa ni akoko yiyan




Yíyan máa ń ṣe àfikún: Òórùn dídùn, Adùn ìtọ́wò àti


Smoked fish


Local fish smoking kiln


Smoking fish locally

### àarò/ohun-èlò ìgbàlódé fún yíyan ẹja



Less Polycyclic Aromatic Hydrocarbons (PAHs



**Àwọn igi tí a dá lábàá fún yíyan ẹja ni;**

- Ikate
- Akun
- Awasa
- Igi – Awonwon
- Igi – Aba
- Igi – Agbon (Coconut tree)
- Padi – Agbon (Coconut husk)



### àarò/ohun-èlò ìbílẹ̀ fún yíyan ẹja



More Polycyclic Aromatic Hydrocarbons PAHs



**Àwọn ohun tí a kò gbọdọ̀ lò láti yan ẹja;**

- Ọ̀rá
- Táyà
- túùbù
- ike, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ





# Àwọn Oúnjẹ ẹlẹ́ja tó ṣe àǹfààní



oúnjẹ ẹlẹ́ja gidi



róòlù ẹlẹ́ja



Oúnjẹ ẹlẹ́ja




róòlù ẹlẹ́ja




epo ẹja



nógẹ́ẹ̀tì ẹlẹ́ja




Àwòrán 9: Pípèsè ògì-onísóyà




Àwòrán 10: Pípèsè ògì-onísóyà








Àwòrán 11 – Pípèsè Túwó-Onísóyà





## ÌYẸ̀FUN ALÁGBÀDO



**ÌSÀPÉJÚWE ÌGBÉṢẸ̀/ỌJÀ:** Àwọn ìyẹ̀fun ọkà, pàápàá jù lọ láti inú àgbàdo àti ọkà bàbà jẹ́ àwọn oúnjẹ kan pàtàkì tí èèyàn ìlú máa ń bèèrè fún jù.A tún lè lò wọ́n fún ìsàgbéjáde àwọn oúnjẹ oníyẹ̀fun alábọ́dé,ìpanu gẹ́gẹ́ ohun ìpèlò fún àwọn oúnjẹ mìíràn. Àwọn ìyẹ̀fun rẹwà tí wọ́n sì funfun (bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àìbáramu ìyàtọ̀ àwọn èèpo mú kí ó yí àwọ̀ padà di elésèé-àlùkò.Ní abẹ́ ìkópamọ́ tí ó dára ìyẹ̀fun lè lo tó bí ọdún méjì ní ìpamọ.

Òfin ìkópamọ́ àti àwọn ìlànà ìgbésẹ̀: Òfin ìkópamọ́ fún ìyẹ̀fun ni láti dín sísomí títí dé ibi tí kòkòrò àìfojúrí àti àrùn yóò ti wọ inú rẹ̀ kù.Ìgbésè náà ní ṣe pẹ̀lú títò,fífọ̀,ipò tí ó wà,bíbó èpò àwọn oúnjẹ adàworo,lílọ di ìyẹ̀fun, àti bíbó èèpo ara rẹ̀ kúrò.

### ÌGBÉṢẸ̀ ÀTẸ ÀWÒRÁN ALÁLÀYÉ

Mímọ́: fífi ọwọ́ sà láti yọ àwọn ewé, òkúta abbl kúrò – nípasẹ̀ lílo ajọ̀ alágbọ̀n

Ipò: Fi omi tútù sí i láti mú kí àgbàdonáà rọ̀

Bíbó: Lo ẹ̀ro ìbó-èèpo

Ríre̩: rẹ àwọn hóró náà sínú omi fún wákàtí méjìlá

Sísá: Fífi òòrùn sá fún wákàtí mẹ́ta sí márùn-ún

Lílọ̀: Lo ẹ̀rọ ìlọ-nǹkan

Sísá: Fífi òòrùn sá fún wákàtí kan sí méjì

Jíjọ̀: Lo ajọ̀ tó dára, bí àpẹẹrẹ, oní-mìlímità kan

Dídì: Lo àwọn báàgì oníke tí a fi èdìdí dì

Ìpamọ́: kó o pamọ́ sí ibi tí ó gbẹ láìlóoru

## ÌSÀKÓSO OJÚLÓWÓ

Ìmọ́tótó: Níwọ̀n ìgbà tí oúnjẹ tútù àti ìyẹ̀fun ti wà ní gbígbẹ ìwọnba ewu àrùn oúnjẹ ní yóò wà. Ìsàmúlò ìmọ̀tótó tí ló dára àti ìkópamọ́ lọ́nà tí ó tọ́ tí tó láti sàmúlò ìmọ̀tótó àgbéjáde oúnjẹ.

**Ìsàkóso oúnjẹ tútù:** Àwọn ọkà gbọ́dọ̀ gbó tàbí pọ́n, kí wọ́n wà lójú kan náà láì jẹ́ pé wọ́n ní ẹrọ̀fọ̀, erùpẹ̀ tàbí àwọn nǹkan mìíràn tí ó lè yí I lára.Ìlànà tí ó darí àwọn ibi ìsàkóso ojúlówó ni:

1. Wíwà ní ipò ẹ̀tọ̀ àwọn ọkà láti lè ri dájú pé àwọn ọmi ara wọn ro kí ó lè ba à ṣe iṣẹ́ tí a fẹ́ kí o se nígbà tí a bá lọ̀ ọ́ (ìyẹn ni pé àwọn ọkà náà ṣe kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ di ìyẹ̀fun lẹ́nu ọlọ láì ṣe pé ó fọ́ sí wẹ́wẹ́ tàbí ó dí ọlọ lẹ́nu),
2. Irú ọlọ, bí ó ṣe ń ṣiṣẹ́ sí ìsàtúntò ètò rẹ̀ jẹ́ àwọn èyí tí ó máa mú ìfàsẹ́yìn bá ojúlówó ìyẹ̀fun tí ó yẹ kí a rí lẹ́nu ọló-ẹ̀rọ,
3. Ojú ihò tí aṣẹ́ ní ni yóò sọ bí ìyẹ̀fun náà yóò ṣe rẹwà lójú sí,
4. Ṣíṣá ìyẹ̀fun bí ó ti tọ́ láti lè rí dáju pé a ri oun tí à ń fẹ́ mú jáde níbẹ̀.

**ÌSÀKÓSO AGBÉJÁDE:** Àwọn nǹkanTí ó ṣe pàtàkì jù lọ́ ní àwọ̀ àti bí ìyẹ̀fun náà ṣe rí lára(bí ó ṣe rẹ̀wà sí). Èyí wà lọ́wọ́ ipò tí ohun tí a fi ṣe ìyẹ̀fun náà wà àti ipò tí àwọn èròjà ara ọlọ wà àti bí a bá ṣe ń ṣe é nígbà tí a bá ń ṣẹ nínú aṣẹ́ These are determined by the extent of conditioning, mill characteristics and extent of bran removal by sieving.

**ÌKÓSÓJÚKAN ÀTI ÌKÓPAMỌ́:** Tí a bá ṣe ìyẹ̀fun náà ní ààyè tàbí agbègbè tí òrinrin tàbí eji kékeré wà a lè kó pamọ́ sínú àwọn àpò-ìdọ̀họ. Tí a bá ṣe ní ibi tí ọ̀rinrin pọ̀ jù sí tàbí à gbé lọ sí ibẹ̀ ó lè nílò kí á kí á gbé wọn sínú àpò-oníke.Tàbí kí ó jẹ́ pé ibi tí á fẹ́ ko pamọ́ sí jẹ́ èyí tí kò lè fààyè gba omi wọlé tàbí, tutù àti ibi tí ẹyẹ, kòkòrò àti àwọn eranko kékèèké kò lè dé.

## ÀWỌN Ẹ̀PÀ YÍYAN



**ÀPÈJÚWE ÌGBÉSÈ:** Ẹ̀pà yíyan jẹ́ ẹ̀pà odidi tàbí ẹ̀pà tí ó wà nínú èpo èyí tí wọ́n áyan tí yóò pọ́n fẹ́ẹ̀rẹ́fẹ́. Wọ́n ṣáábà máa ń fi iyọ̀ sí tí a sì máa n ´lò ó gẹ́gẹ́ bí ìpanu.

**Àwọn ọ̀nà ìṣelọ́jọ̀pamọ́ àti àwọn ọ̀nà ìgbésẹ̀:** Ìṣelọ́jọ̀pamọ́ nígbà tí a bá ń yan-án pẹ̀lú ọmi ara rẹ̀ nígbà tí a bá ṣe é tán.A nílò láti dààbò bó kúró lọ́wọ́ ọ̀rinrin kí n tí à ń fẹ́ lè ba à tẹ̀ wá lọ́wọ́ lọ́pọ̀ yanturu láàrin ọjọ́ péréte, Ṣùgbọ́n àwọn oúnjẹ tí a fi ṣe sáábà máa ń wà fún títa fún àsìkò pérété sí ìgbà tí wọ́n bá ṣe é jáde.

## ÌGBÉṢẸ̀ ÀTẸ ÀWÒRÁN ALÁLÀYÉ

Èèpo: Bíbó èèpo nípa lílo ẹ̀rọ àbéèpo ọlọ́wọ́ tàbí èyí tí ó lagbára

Ìkópamọ́: Kíkópamọ́ sínú àpò ìdọ̀họ , ní yàará tí atẹ́gùn yóó ti fẹ́ si dáadáa; máṣe jẹ́ kí àpò tí a ti so lẹ́nu pa náà wà nílẹ̀. Dààbò bó kúrò lọ́wọ́ àwọn ajẹlóju-onílé àti àwọn kòkòrò tí ó ń súyọ látara ìkópamọ́

Sísà: Sàtúntò láti lè yọ èyí tí ó ní ẹrọ̀fọ̀, àti èèpo tí a ti ṣẹ́ kúrò lára rẹ̀

Ṣíṣẹ́: Ṣẹ kí á lè mú àwọn irú ẹ̀pà kan náà jáde

Sísọdimímọ́: sọ́ di mímọ́ nípa lílo kọ̀ǹkọ̀sọ̀ láti yọ ìdọ̀tí kúrò

Yíyan:Yan àwọn ẹ̀pà náà lórí àwọn abọ́-fífẹ̀ nípa lílo ooru tí o le láti lè fún wa ní àdídùn tí a fẹ́, kí ó pọ́n fẹ́ẹ̀rẹ́fẹ́ pẹ̀lú àwọ̀ tí ó jọjú.

Bíbó: Yọ awọ ara kuro nipa fifọ awọn eso sinu atẹ tabi agbọn fifun nigbati o tutu

Fífẹ́ dànù: Lo kọ̀ǹkọ̀sọ̀

Iyọ: Wọ lori iyọ lati mu itọwo dara.

Kó pamọ́: kíkó ìwọnba sínú rẹ̀ the correct amount; kíkó àwọn sínú báàgì oníke kí a sì de pa bí ó ti tọ́.

Ìkópamọ́: Fi pamọ́ si ibi tí ó tutù tí ó gbẹ.

## ÌSÀKÓSO OJÚLÓWÓ

Ìmọ́tótó: Oúnjẹ́ tútù àti àgbéjáde yóò wà ní gbígbẹ títí tí ìgbésè náà yóò fi parí àti pé ìsòrò ìmọ́tótó yóò díkù fún àwọn oúnjẹ olómi lára.Bákan náà ní ó yẹ́ kí á sàmúlò àwọn òfin ìmọ́tótó tí ó yẹ fún oúnjẹ tí ó ní àlàáfíà.

**ÌSÀKÓSO OÚNJẸ TÚTÙ:** Nígbà tí ẹ̀pà bá gbó ní ó yẹ kí a tó ka.Tí a bá fi ẹ̀pà sí ilẹ̀ fún ìgbà pípẹ́ lẹ́yìn ìgbà tí ó ti gbó wọ́n kò ní ní adùn àti àwọ̀ tí ó dára mọ́.kíká nígbà tí kò gbó máa ń jẹ́ kí ẹ̀pà má lọ́mọ nínú láti fí ṣe oúnjẹ. Àwọn ẹ̀pà gbọ́dọ̀ gbẹ nínú oko nígbà tí wọ́n báwà nínú èèpo, àti ìgbà tí wọ́n bá wà lára igi,àti ìgbà tí wọ́n bá doríkodò. Sísá ẹ̀pà lórí páànù òrùlé tàbí òrí òrùlè kò dára tó tórí ẹ̀pà náà yóò ti yan tí àwọn adùn inú rẹ̀ yóò sì ti bàjẹ́.

**Ìgbésè ìsàkóso:**Ó ṣe pàtàkì kí á yọ èèpo ẹ̀pà kúrò kí á sì sa dáadáa kí á tó kó pamọ́ látí má jẹ́ amọ̀ tí ó bá wà lábẹ́ èèpo náà pọ̀ si. Púpọ̀ àwọn amọ̀ ní ó máa ń fa májèlé tí ó léwu.A gbọ́dọ̀ yọ gbogbo àwọn èèpo, òkútá, ewé,ẹ̀pà tí ó ní amọ̀ kúrò.Bí oúnjẹ tí a ṣe jáde náà yóò ṣe dára sí wà lọ́wọ́ àsìkò àti ìgbéwọ̀n ooru(yíyan) ìwọ̀n àti àwọn bí ẹ̀pà náà ṣe tutù sí. Àwọn ibi ìsàkóso mìíràn jẹ́ èyí ti ó jẹyọ látipaṣẹ̀ yíyọ bébà tí a fi nù-ún nù ní fífi ra tàbí fífẹ́ , àti ìwọ̀n iyọ̀ tí a fi sí oúnjẹ tí a ṣe jáde náà.

**Ìsàkóso Oúnjẹ:** Àwọn pàtàkì yíyàn ẹ̀pà ní àwọ, adùn bí ó ṣe rí àti bí ó ṣe gbéwọ̀n sí.

TheÀwọ adùn àti bí ó ṣe rí lójú wà lọ́wọ́ àkókò àti ìwọ̀n ìgbóná yíyan àti ìwọ̀n nípa gbígbẹ àwọn ẹ̀pà tútù sórí òsùnwọ̀n.

**ÌKÓJỌSÓJÚKAN ÀTI ÌKÓPAMỌ́:** Adùn àti ẹwà oúnjẹ náà máa ń wà síbẹ̀ nígbà tí a bá kó pámọ́ sínú ààbò,àwọn báàgì oníke tí kò ní fààyè gbá ẹ̀kán-omi àti fifi sí ibi ìdákẹ́rọ́ tí ó gbẹ.

## ÌYẸ̀FUN Ẹ̀PÀ



**ÀPÉJÚWE ÌGBÉSẸ̀:** ìyẹ̀fun ẹ̀pà jẹ́ ìyẹ̀fun tí ó rẹwà ní funfun èyí tí a ṣe látara ẹ̀pà lílọ̀,tútù,gbígbẹ ó jẹ́ oun tí ó níye lórí tí àwọn ènìyàn máa ń bèèrè fún lọ́pọ̀lọpọ̀ gẹ́gẹ́ bí oúnjẹ tí ó rọrùn fún ìlò ilé, gẹ́gẹ́ bí èròjà,amóńjẹdùn àti amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ oúnjẹ mìíràn,àwọn oúnjẹ ìpanu,àsáró,àti àwọn oúnjẹ mìíràn.

**Àwọn òfin ìkópamọ́ àti àwọn ọ̀nà ìgbésẹ̀:** Àwọn ẹ̀pà tí wà ní ìpamọ́ tí ní gbígbẹ tí wọ́n sì ní à lò pé látará pé wọ́n pé wọ́n gbẹ dáadáa tí wọ́n sì wà ní ìpamọ́ bí ó ti tọ́ . Nígbà tí a bá fẹ́ ṣe ìyẹ̀fun àwọn ẹ̀pà tútù tí ó ti gbẹ gbọ́dọ̀ di mímọ, lílọ̀,àti ṣíṣẹ́.Nígbà tí a bá gbé ìgbésẹ̀ tí ó tọ́ àti èyí tí ó yẹ lóri rẹ̀ ìyẹ̀fun náà gbọ́dọ̀ wà ní gbígbẹ àti pé kìí sí ààyè fún àwọn kókòrò àìfojúrí àti àrùn tí ó lè wọnú oúnjẹ.

### ÌGBÉSẸ̀ ÀTẸ ÀWÒRÁN ALÁLÀYÉ

**Bíbó: Lo ọwọ́ tàbí ẹ̀rọ alágbára fún bíbó èèpo**

**Ìpamọ́: pamọ́ sí inú àwọn àpò arómiyọ̀ nínú yàrá tí atẹ́gùn wà dáadáa. Gbé àwọn àpò náà sórí pèpélé kúrò nílẹ̀. Dàbòòbò kúrò lọ́wọ́ àwọn eku àti kòkòrò**

**Sísà: fi ọwọ̀ yọ àwọn ẹrọ̀fọ̀, èèpo líle, òkúta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ**

**Mímọ́: fi ajọ alágbọ̀n yọ ìdọ̀tí kúrò. Máṣe yọ gbogbo àwọn èèpo búráànù**

**Jíjọ̀: Kọ́kọ́ fi ẹ̀rọ kékeré kan wẹ́ ẹ (Aworan 1). Fi ajọ̀ kékeré yọ hóró tí o ti wẹ́. Tún fi odó wé àwọn tó tún tóbi díẹ̀, kí o sì tún un jọ̀**

**Dídì: Dì wọ́n sínú àpò arómiyọ̀. Fi iná ṣe èdìdí rẹ̀.**

**Pamọ́: Pamọ́ sí ibi tí ó gbẹ tí kò sì móoru**

**ÌSÀKÓSO OJÚLÓWÓ**

**Ìmọ́tótó:** Oúnjẹ́ tútù àti àgbéjáde yóò wà ní gbígbẹ títí tí ìgbésè náà yóò fi parí àti pé ìsòrò ìmọ́tótó yóò díkù fún àwọn oúnjẹ olómi lára.Bákan náà ní ó yẹ́ kí á sàmúlò àwọn òfin ìmọ́tótó tí ó yẹ fún oúnjẹ tí ó ní àlàáfíà.

**Ìsàkóso Oúnjẹ Tútù:** Nígbà tí ẹ̀pà bá gbó ní ó yẹ kí a tó ka.Tí a bá fi ẹ̀pà sí ilẹ̀ fún ìgbà pípẹ́ lẹ́yìn ìgbà tí ó ti gbó wọ́n kò ní ní adùn àti àwọ̀ tí ó dára mọ́.kíká nígbà tí kò gbó máa ń jẹ́ kí ẹ̀pà má lọ́mọ nínú láti fi ṣe oúnjẹ. Àwọn ẹ̀pà gbọ́dọ̀ gbẹ nínú oko nígbà tí wọ́n báwà nínú èèpo, àti ìgbà tí wọ́n bá wà lára igi,àti ìgbà tí wọ́n bá doríkodò. Sísá ẹ̀pà lórí páànù òrùlé tàbí òrí òrùlè kò dára tó tórí ẹ̀pà náà yóò ti yan tí àwọn adùn inú rẹ̀ yóò sì ti bàjẹ́.

**Ìsàkóso Ìgbésẹ̀:** Ó ṣe pàtàkì kí á yọ èèpo ẹ̀pà kúrò kí á sì sa dáadáa kí á tó kó pamọ́ látí má jẹ́ amọ̀ tí ó bá wà lábẹ́ èèpo náà pọ̀ si. Púpọ̀ àwọn amọ̀ ní ó máa ń fa májèlé tí ó léwu.A gbọ́dọ̀ ṣe ìtọ́jú láti ri pé nígbà trí a bá bó èèpo ara rẹ̀ tán a kò tún fi ọwọ́ tútù kan àwọn ẹ̀pà náà.A gbọ́dọ̀ yọ àwọn ìdòtí èèpo,òkuta,àti àwọn ewé,èpà tí ó jimi tàbí èyí tí ó dì papọ̀. A gbọ́dọ̀ sá gbogbo àwọn ẹbpà náà kí ó lè ba à pèsè ìyẹ̀fun tí ó pọ̀. Tí àwọn ẹ̀pà náà bá jimi wọn á lẹ̀ papọ̀ tí yóò sì rí bí àkàrà-òyìnbó dípò kí ó pèsè ìyẹ̀fun ìyẹ̀fun jáde.Ìwọ̀n bí á ṣe ń lọ̀-ọ́ àti fífẹ̀ ojúaṣẹ́ ní yóò sọ bí ìyẹ̀fun náà yóò ṣe rẹwà sí.A gbọ́dọ̀ wọn náà dáadáa, kí a kó sínuú àpò kí á sì só lẹ́nu pa bí ó ti tó àti bí ó ti yẹ. A gbọ́dọ̀ ṣe àmójútó bí ó ti tọ́ láti má jẹ́ kí ó gbóná ju bí ó ti yẹ lọ nínú agbada, èyí tí ó lè fà á kí ó má ṣiṣẹ́ gidi mọ́.

**Ìsàkóso Oúnjẹ:** Àwọn abala pàtàkì tí ó jẹ́ ojúlówó ni àwọ̀, bí ó ṣe rí lójú,àti adùn oúnjẹ náà. Bí àwọ̀ rẹ̀ yóò ṣe rí wà lọ́wọ́ èso(brown seed coat) tí a lọ̀ papọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹ̀pà . A nílò ìwọ̀nba kékèré láti lè jẹ́ kí ó túbọ̀ gbé àwọ̀ jáde àti kí ó le túbọ̀ fajúmọ́ra. Àwọn adùn rẹ̀ wà lọ́wọ́ ìlànà gbígbẹ tí a lò.

**ÌKÓSÓJÚKAN ÀTI KÍKÓPAMỌ́:** A gbọ́dọ̀ kó ìyẹ̀fun ẹ̀pà pamọ́ sínú kọ̀ntánà tí kò fààyè gba afẹ́fẹ́, bí a bá lè kó sínú báàgì onike tí ó lágbára tí kò fààyè gba ọ̀rinrin tí a sì gbe síbi ìdákẹ́rọ́rọ́ tí ó gbẹ kí bá dára.

## MÍLÎÌKÌ SÓYÀ



**ÀPÈJÚWE ÌGBÉSẸ̀:** Mílîìkì Soy jẹ́ ohun mímu aláwọ̀ funfun olómi tí a ṣe jáde látara ẹ̀wà-sóyà èyí tí a lè lò gẹ́gẹ́ mílîìkì.Ó lè dùn pẹ̀lú ìwọ̀n ìdá-márùn-ún súgà èyí tí a lè mu lásán tàbí kí a fi sínú kọfí,fàníla àti ohun mímu ẹlẹ́rìndòdò.A tún lè ló láti jẹ́ kí mílîìkì pọ̀ sí nípa dídàpọ̀ ní ìdá abọ́ mílîìkì 1 sí abọ́ mílîìkì soy mẹ́rin.

**Àwọn òfin ìkópamọ́ àti ìlànà ìgbésẹ̀:** A lè ṣe ìkópamọ́ nígbà tí a bá fi ooru mú àwọn kòkòrò àìfojúri,àwọn olùdènà asaralóore bí bí olùdènà afúnni -lóhun asaralóore àti àwọn kòkòrò àìfojúrí. láti lè dènà jíjẹ́ kí àrùn wọlé nípa dídé àwọn nǹkan tí a kó sí pa dáadáa. Ìgbéṣẹ̀ inú rẹ̀ ní ṣe pẹ̀lú lílọ ẹ̀wà tí a ti rẹ lómi dáadáa kí a sì ṣẹ̀ pẹ̀lú omi gbígbóná àti kí a fún láti lè fún wa ní mílîìkì.

### ÌGBÉṢẸ̀ ÀTẸ ÀWÒRÁN ALÁLÀYÉ

**Sísọ di Mímọ́: yọ àwọn ohun àjòjì yòówù kí o sì fi omi fọ̀ ọ́**

**Ríre̩: Rẹ sílẹ̀ fún wákàtí mẹ́wàá nínú omi iyọ̀ onídàá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún**

**Lílọ̀: lọ̀ ọ́ pẹ̀lú odó, ẹ̀rọ tàbí bílẹ́ńdà títí tí yóò fi kúnná**

**Sísè/Bíbọ̀: a ó fi omi se ohun tí a ti lọ̀ fún ogún ìṣẹ́jú láti yọ wàrà inú rẹ̀.**

**Títẹ̀: Fi ọwọ̀ tẹ̀ ẹ́ tàbí kí o lo àpò tàbí báàgì kan. Ó sábà máa ń jẹ́ títẹ̀ lẹ́ẹ̀mejì**

**Sísè/Bíbọ̀: Jẹ́ kí wàrà náà di sísè ní kíá kí o sì sè é fún ìṣẹ́jú mẹ́fà. Máa rò ó léraléra**

**Mú kí ó tutù**

**Dídì: rọ ọ́ sínú ìgò tàbí ike.**

### ÌSÀKÓSO OJÚLÓWÓ

**Ìmọ̀tótó:** Mílíìkì soy jẹ́ èyí tí ó ní àsíìdì kékeré nínú èyí tí ó sì lè bàjẹ́ àti kí ó mú àwọn kòkòrò àìfojúrí wọlé fún àwọn ènìyàn.Ipa pàtàkì ni àwọn ọ̀nà tí à ń gbà ṣàgbékalẹ̀ mílíìkì náà ń kó nínú mímọ ojúlówó oúnjẹ tí a fí pèèlò. Ìmọ̀tótó gbọ́dọ̀wà nígbà tí a bá n ṣe mílíìkì náà,pàápàá jù lọ lẹ́yìn ìgbà tí a bá ń gbe gbóná  and èyí tí ó lè ṣe ṣe kí ó tún padà ní àbàwọ́n.

**Àwọn ohun tí a nílò fún ìmọ̀tótó gangan nìwọ̀nyí:**

1. Fífọ̀ dáadáa àti mímú jìnà sí kòkòrò àìfojúrí (pẹ̀lú kilorínìnì tàbí omi gbígbóná)gbogbo  àwọn èròjà àti èèlò tí a lò láti pèèlò mílíìkì (bí àpẹẹrẹ àwọn àpò aṣẹ́,àwọn àtìrọ) kí á tó ṣé àti nígbà tí a bá ṣé tán (a kò gbọdọ̀ fi kilórín-ìn-nì fọ oun èlò nb alumílíọ̀nù),
2. Ṣíṣe àmúlò ìmọ́tótó ara-ẹni.

**ìsàkóso oúnjẹ tútù:** Ẹ̀wà kò gbọdọ̀ wà nínú èèpò, erùpẹ̀ àti àwọn ìdòtí ohun tí ó so mọ́ ẹ̀wà bákan náà ni kò gbọdọ̀ wà ní ibi tí kòkòrò yóò ti bàájẹ́. A gbọ́dọ̀ kó wọn sínú yàárá tí ó dákẹ́ rọ́rọ́ tí ó gbẹ sórí ẹni tí a tẹ́ sílẹ̀ bákan náà ní kí a dààbò bò wọ́n kúrò lọ́wọ́ kòkòrò kékèké,àwọn ẹyẹ àti àwọn ẹranko kékèké.

**Ìsàkóso Ìlànà: Àwọn kókó tí ó ṣe pàtàkì jù lọ ni**

1. Láti rẹ́ àwọn ẹ̀wà sínú omi fún ìwọ̀nba àkókò tí ó yẹ kí ó lè ba à ṣe lọ̀.Bí ẹ̀wà náà bá le látara àìrẹlómi bí ó ti yẹ ìwọ̀nba mílíìkì tí a máa rí yóò kéré àti pé mílíìkì náà yóò ní àwọn ẹ̀wàkékèké nínú,
2. Sísẹ́ àwọn mílíìkì náà nípa lílo àpò-àwọn láti lè ba à dín àwọn àwọn nǹkan líle tí ó wà nínú mílíìkì náà kù. àpọ̀jù pàǹtí líle máa hàn nígbà tí a bá fẹ́ kó mílíìkì pamọ́ èyí tí ó sì lé mú àbùkù ba,
3. A gbọ́dọ̀ mójútó àkókò àti ìwọ̀n tí a máa jẹ́ kí ó gbóná láti lè jẹ́ kí mílíìkì náà bọ́ lọ́wọ́ àrùn àti láti lè dènà àwọn nǹkan tí kò ní jẹ́ kí mílíìkì náà ní àwọn èròjà asaralóore.A gbọ́dọ̀ máa ròó lórí iná láti má jẹ́ kí ó jóná sínú apẹẹrin.

**ÌKÓSÓJÚKAN ÀTI ÌKÓPAMỌ́:** Nígbà tí a bá ń kópamọ́sójúkan oun tí a gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ mú sà lóògùn ni kí a ri dájú pé àwọn ohun-èlò tí a fẹ́ rọ-ọ́ sí,àwọn ìgò àti ìdérí wà ní mímọ́ kí ó má ba à jẹ́ pé àwọn mílíìkì tí a ti ṣè jinà yóò tún padà ní àbùkù lára. Èyí ṣe pàtàkì nígbà tí ó bá jẹ́ pé à ń ṣe àtúnlò ìgò náà lò ni.Ìwọ̀n oun tí a máa rọ sínú ìgò gbọ́dọ̀ wà ní ìwọ̀ntunwọ̀sì.

## ÌYẸ̀FUN SÓYÀ



**ÀPÈJÚWE ÌGBÉSẸ̀:** Ìyẹ̀fun soy jẹ́ ìyẹ̀fun àláwọ̀ ìpara tí ó rẹwà èyí tí a pò papọ̀ pẹ̀lú ìyẹ̀fun àgbàdo tàbí àwọn ìyẹ̀fun ọkà mìíràn látí túbọ̀ jẹ́ kí ó ni èròjà asaraóorè pẹ̀lú àwọn òdiwọ̀n èròja-fúnilasaralóore tí ó yẹ kí ó wà nínú ìyẹ̀fun.Ní ìrísí rẹ̀ yìí a lè ló fún oúnjẹ òwúrọ̀ àti oúnjẹ ìkókó.

**Àwọn Òfin Ìkópamọ́ Àti Àwọn Ọ̀nà Ìgbésẹ̀:** A lè ṣe ìkópamọ́ nígbà tí ìyẹ̀fun náà kò bá ní omi lára púpọ̀ mọ́ èyí tí yóò dènà àrùn àti àwọn kòkòrò àìfojúrí. Àǹfààní pàtàkí tí ó wà nínú dída ìyẹfun pọ̀ kí ó lè fún wa ni ìyẹ̀fun àládàpọ̀ ní pé ọ̀rá tí ó wà nínú ìyẹ̀fun tí a dà papọ̀ máa ń kéré sí tí ìyẹ̀fun ti sóyà nìkan lọ àti pé ó tún máa ń dín àwọn òòrùn tí kò fanimọ́ra kù.

### ÌGBÉSẸ̀ ÀTẸ AYÀWÒRÁN ALÁLÀYE

**Jíjẹ́ kí ó mọ́: Yọ àwọn hùùhùù ara rẹ̀ nípasẹ̀ lílo àwọn ajọ̀ alágbọ̀n**

**Sísè: Fi omi ọsàn wẹ́wẹ́ sè é (calcium hydroxide oní-gíráàmù méjìdínlọ́gbọ̀n/ erèé 4.5kg ni a ó lò. Omí gbọ́dọ̀ jẹ́ ìlọ́po mẹ́ta ohun líle)**

**Bíbó: A ó yọ àwọn èèpo hóró náà nípasẹ̀ fífi ọwọ́ bó**

**Sísá: fi òòrùn sá a lórí àwọn pèpéle**

**Lílọ̀: Fi odó tàbí ẹ̀rọ lọ̀ ọ́**

**Jíjọ̀: Lo àjọ̀ tó dára (oní mìlímità kan)**

**Rírọ̀pọ̀: ro ìyẹfun sóyà ìdá ogún àti ìyẹfun onírú-hóró mìíràn**

**Dídì: Dì sínú pólí baàgì nípasẹ̀ lílo èdìdí oníná**

**Ìpamọ́: Pa á mọ́ sí ibi tí ó gbẹ kí kò sì móoru.**

## ÌSÀKÓSO OJÚLÓWÓ

**Ìmọ́tótó:** Oúnjẹ́ tútù àti àgbéjáde yóò wà ní gbígbẹ títí tí ìgbésè náà yóò fi parí àti pé àwọn ìsòrò ìmọ́tótó yóò díkù fún àwọn oúnjẹ olómi lára.Bákan náà ní ó yẹ́ kí á sàmúlò àwọn òfin ìmọ́tótó tí ó yẹ fún oúnjẹ tí ó ní àlàáfíà.

**Ìsàkóso Oúnjẹ Tútù:** Ẹ̀wà kò gbọdọ̀ wà nínú èèpò, erùpẹ̀ àti àwọn ìdòtí ohun tí ó so mọ́ ẹ̀wà bákan náà ni kò gbọdọ̀ wà ní ibi tí kòkòrò yóò ti bàájẹ́. A gbọ́dọ̀ kó wọn sínú yàárá tí ó dákẹ́ rọ́rọ́ tí ó gbẹ sórí ẹni tí a tẹ́ sílẹ̀ bákan náà ní kí a dàábò bò wọ́n kúrò lọ́wọ́ kòkòrò kékèké,àwọn ẹyẹ àti àwọn ẹranko kékèké.

**Ìsàkóso Ìgbésẹ̀:** Pàtàkì ni gbígbé ẹ̀wà kaná látí lè jẹ́ kí adùn tàbí òórùn ẹ̀wà kúrò nínú rẹ̀, láti pa àwọn olùdènà-asaralóore tí ó wà nínú ẹ̀wà èyí tí ó lè dín àwọn òdiwọn asaralóore tí ó wà nínú ìyẹ̀fun náà kù àti láti tún jẹ́ kí èèpò ẹ̀wà tẹ̀tẹ̀ sí kúrò lára rẹ̀. Sísá títí yóò fi fẹ́rẹ̀ gbẹ tún jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí a fi ń ṣe ìyẹ̀fun nígbà tí a bá lọ̀ ọ́, láì jẹ́ pé ó di ẹnu-ẹ̀rọ.Ojú aṣẹ́ ni yóò sọ bí ìyẹ̀fun náà yóò ṣe rẹwà lójú sí èyí sì yẹ́ kí ó rí bí ti ìyẹ̀fun ọkà mìíràn láti lè bá jẹ́ kí bárámu ní dídàpọ. A gbọ́dọ̀ ṣe ìgbéwọ̀n àwọn ìyẹ̀fun tí a fẹ́ dà papọ̀ dáadáa kí a tó dà wọ́n pọ̀.

**ÌKÓSÓJÚKAN ÀTI ÌKÓPAMỌ́:** Ìyẹ̀fun máa ń faomi mu nítorí náà ní o fi yẹ kí a ko pamọ́ sínú àwọn kọ̀ǹténà tí kò ní fààyè gba ẹ̀kán-omi (b.a. pólí baàgì tí ó lágbára) tí a so lẹ́nu pa.A ní láti sàmójútó ìyẹ̀fun náà kí ooru báàgì oníke má ba à kó bá.À gbọ́dọ́ rọ ìwọ̀nba tí ó bá lè gbà sínú rẹ̀.

**ÌKÓSÓJÚKAN ÀTI ÌKÓPAMỌ́:** Gbogbo àwọn oúnjẹ kọ̀ọ̀kan tí a tí júwe yìí ni ó máa ń dára kí á kó wọn sínú kọ̀ǹténà onígíláàsì.Àwọn ìgbésẹ̀ ìlànà tí ó ṣe pàtàkì jù lọ ni kí a rọ ìwọ̀n tí yóò gbà sínú rẹ̀ (gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àtẹ àlàyé) àti láti ri dájú pé àwọn kọ̀ǹténà náà wà ní ipò àlàáfíà (tí kìí ṣe àkúfọ-ìgò,eyí tí ó ti sán,èyí tíàwọn erùpẹ̀ wà nínú rẹ̀) kí a sì ri dájú pé a déwọn lẹ́nu pa. Ọ̀pọ̀ àwọn oúnjẹ, tí a bá ṣé dáadáa, ó yẹ kí ó lè ló bí osù-mẹ́fà sí ọdún kan tí a bá kó pamọ́ sí àwọn ibi ìdákẹ́rọ́rọ́ tí o sókùnkùn.

**Ìkósójúkan:** Wàhálà máa ń wà nínú kíkó àwọn ounjẹ pamọ́ lẹ́jẹ̀wọ́nlẹ́jẹ̀wọ́n. èelò-ìkópamọ wọ́n, àti pé ó lè má wà ní àrọ́wọ́tó ò sì lè jẹ́ pé òun nìkan náà ni yóò máa gbọ́n wa lówó jù lọ.Àwọn oríṣi tí a máa ń lò fún èsò àti ewébẹ̀ ní àwọn kọ̀ǹténà onígò tàbí onike, tàbí àwọn báàgì oníke.

**Gíláàsì:** Àwọn àǹfààní gíláàsì ni pé ara rẹ̀ dán,wà ní ìmọ́tótó, ó rọrùn láti fọ̀ ,a lè tun lò(pẹ̀lú àwọn ìdérí tuntun) wọ́n ṣé gbé lórí ara wọn.tí ó sì máa ń jẹ́ kí oúnjẹ́ tí a kó sínú rẹ̀ gbé àwọ̀ ọ̀tun wọ̀ èyí tí ó sì máa ń jẹ́ kí àwọn oníbàárà tí wọ́n ń bèèrè fun túbọ̀ pọ̀ si kí ó sì ní iye lórí. Àlèébù tí ó ní ni pé ó máa ń fọ́, ó wọ́n ò sì tún wọ́n (èyí tí ó máa ń mú kí owó ọkọ̀ pọ̀ si. Tí a bá tún àwọn kọ̀ǹténà náà lò à gbọ́dọ̀ sàmójútó láti ri pé wọ́n mọ́ nípa fífí ọṣẹ-olómi fọ̀-ọ́ kí á sì sàn nù nínú omi mímọ́.àwọn oun tí wọ́n fi ń fọ ìgò(bọ́tù) wà. A gbọ́dọ̀ fi omi gbígbóná fọ́ ìgò(bọ́tù) Máṣe gbé àwọn ìgò(bọ́tù) sínú omi gbígbóná nítorí wọ́n máa fọ́.Wọ́n gbọ́dọ̀ wà nínú omi tí ó lọ́ wọ́ọ́rọ́ fún bí i ìsẹ̀jú mẹ́wàá. Àwọn bọ́tù (ìgò) lè tutù nígbà tí a bá ń gbé wọn látinú kúlà kan sí òmíràn nígbà tí a bá ti rọ ohun mímu ẹlẹ́rìndòdò(júùsì), píkúùsì tàbí sósíìsì(sauces). A gbọ́dọ̀ tò wọ́n sí ẹ̀wẹ́ ara wọn latí ba túbọ̀ wọjú.

**Àwọn bọ́tù oníke àti ìkòkò:** Àwọn eléyìí wà ní àwọn agbègbè kọ̀ọ̀kan tí kò sì wọ́n tó ìgò, bákan náà ní wọn kò ṣe tún lò àti pé wọ́n le má ní ìdérí tí ó dára èyí tí ó lè fà á ki kòkòrò wọ inú rẹ̀, tàbí kí òórù rẹ̀ bàjẹ́ tí ó sì lè mú kí ó má pé nílẹ̀ ju bí ó ti yẹ lọ.A gbọ́dọ̀ máa fọ̀wọ́n pẹ̀lú omi gbígbóná,Sùgbọ́n wọn kò lè dúró nínú omi gbígbóná fún ìgbà pípẹ́ . Nítorí náà ní ó ṣe nira láti rọ àwọn oúnjẹ náà sínú rẹ̀ ní gbígbóná ìdí nìyí tí a fi gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ó tutù kí a tó rọ̀ kí ó lè ba à pẹ́ lórí igbá gẹ́gẹ́ bí a ó ṣe yẹ.

**Ọ̀rá:** Èyí dára fún sáṣẹ́ẹ̀tì tàbí àwọn ohun mímu-oníwọ̀n kékeré. Ọ̀rá kò dààbò bo oúnjẹ́ bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn kọ̀ntẹ́nà tí ó le èyí tí ó mú kí oúnjẹ inú rẹ̀ má le pẹ́ lórí igbá jù bí o ti yẹ lọ.
Dídélórí: Ìdérí ọlọ́wọ́ wà àwọn ìkòkò àti bọ́tù.ìdérí oníná ní a fi máa ń lẹ ọ̀rá pa tàbí kí a lo iná àbẹ́là láti fi jo pa.

## Oríṣiríṣi Oúnjẹ Látara Àgbàdo Ìrẹsì Ẹ̀wà Sóyà Àti Ẹ̀pà

| S/N | Àgbàdo | Ẹ̀pà | Ẹ̀wà sóyà | Ìrẹsì |
|---|---|---|---|---|
| 1 | Gúgúrú | Kúlíkúlí | Ẹ̀wà sóyà | Másà |
| 2 | Dakuwa | Ẹ̀pà yíyan | Mílíìkì sóyà | Túwó |
| 3 | Grits | Ẹ̀pà sísè | wàrà | Kùnún gídá |
| 4 | Waina | èkọ | Ẹ̀wà sóyà | Brabisco |
| 5 | Brabisco | Òróró ẹ̀pà | Ọbẹ̀ sóyì | Ìrẹsì aláwọ̀ rẹ́súrẹ́sú Fried rice |
| 6 | Àwọn ìpanu | Dakuwa | Ìyẹfun | Jọ̀lọ́ọ̀fù |
| 7 | Dambun | Kantun gyada | Ìyẹ̀fun aládàpọ̀ | Ìrẹsì àti ẹ̀wà |
| 8 | Àgbàdo ṣíṣè àti sísun | ọbẹ̀ ẹlẹ́pà | | (Ìrẹsì aláṣèpọ̀)Rice pudding |
| 9 | Ẹ̀wà alágbàdo | Pala kobo | | Ìyẹfun |
| 10 | Gúgúru | Kùnún gídá | | Pancake |
| 11 | Pati tsaki | Ìyẹ̀fun | | Ìyẹ̀fun aládàpọ̀ |
| 12 | Túwó | kańdì | | |
| 13 | Ìyẹ̀fun | Bọ́tà | | |
| 14 | Akamu | Mílíìkì ẹlẹ́pà | | |
| 15 | Ìyẹ̀fun aládàpọ̀ | | | |

# ÈKỌ́ KEJÌ

# ÌSỌLÓRÚKỌ-ỌTUN ÀTI ÌṢELỌ́JỌ̀



## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ ìlànà. Àwọn olùkọ́ le ṣe àtúnṣe sí agbọn tó bá wù wọ́n láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Ó yẹ kí wọ́n bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

**Àwọn Èròǹgbà ní pàtó:**

Ní òpin kókó-ọ̀rọ̀ yìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ lè;

- Ní òye ìtumọ̀ ìsọlórúkọ-ọ̀tun
- Tọ́ka sí àwọn èrèdí ìsọlórúkọ-ọ̀tun
- Mọ bí a ṣe ń ṣe àwọn ọjà wọn lọ́jọ̀

**Ìlapa Èrò**

- Ìlapa èrò
- ìsọlórúkọ-ọ̀tun
- Pàtàkì ìsọlórúkọ-ọ̀tun nínú ọjà
- Ìṣelọ́jọ̀
- Àwọn àǹfààní ìṣelọ́jọ̀
- Àwọn Ìsọ̀rí èròjà ìṣelọ́jọ̀
- Àwọn ohun tí ó máa ń sọ èròjà ìṣelọ́jọ̀ tó bójú mu
- Ìṣàmìsí
- Àwọn ìlànà ìṣàmì sí tó pọn dandan




## KÍN NI ÌSỌLÓRÚKỌ-ỌTUN?

Ohun ọ̀tun jẹ́ orúkọ, ọ̀rọ̀, àmì, tàbí àpapọ̀ àwọn ohun wọ̀nyí tí ó ń tọ́ka sí oko-òwò tàbí ọjà kan, tí ó sì ń yà wọ́n nípa sí àwọn orógun mìíràn.

### Ìsọlórúkọ-ọ̀tun ni:

- Ohun tí a mọ oko-òwò, ọjà tàbí ẹnikan mọ̀ láwùjọ.
- Àwọn àwòmọ́ ajẹmọ́ ohun-ìní ìmọ̀ tí ó ya ọjà kan sọ́tọ̀ sí òmíràn.
- Ohun-ìní ìmọ̀: ohun-èlò ajẹmọ́fin tí ó gba níní ohun tuntun láàyè (bí àpẹẹrẹ, àmì ìtajà kan).
- Ohun tuntun jẹ́ ohun gbogbo tí ó máa ya ọjà kan nípa sí òmíràn.

### Ohun/orúkọ tuntun máa ń sọ nípa àwọn àlàyé wọ̀nyí nípa ọjà kan ní ọkàn oníbààrà:

- Ṣíṣe ọjà lọ́jọ̀
- Orísun àti àwọn ìlànà ọjà
- Ìfiwé àti wíwà ọjà náà
- Iye owó ọjà náà
- Dídára ọjà náà

### Àwọn ọ̀rọ̀-ìperí kan nípa Ìsọlórúkọ-ọ̀tun

- **Orúkọ tuntun:** tàbí orúkọ ọjà kan jẹ́ ọ̀rọ̀ kan, tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀, lẹ́tà tàbí òǹkà tí ó ń dúró fún ọjà tàbí iṣẹ́ kan.
- **Orúkọ ìṣòwò kan:** tàbí ààmì àjọ, jẹ́ àpólà ọrọ tàbí
- Àmì tí ó tọ́ka sí tí ó sì ń mú kí ilé-iṣẹ́ tàbí ẹ̀ka àjọ kan gbèrú sí.
- Àmì ọjà tuntun kan: jẹ́ àmì tí ó dá yàtọ̀ kan, ní àwọ̀, ní lẹ́tà, ní àwọ̀ tàbí ohun amúrẹwà mìíràn. Ohun tí ó ṣe é dá mọ̀ lójú ni tí a kò sì nílò láti pè é.
- Àbùdá ìṣòwò kan: jẹ́ àmì ọjà tuntun tí ó ní ìrí tàbí àwọn àbùdá ènìyàn.
- **Àmì ìṣòwò kan:** jẹ́ ọ̀rọ̀ kan, orúkọ kan, àmì kan, ohun-èlò kan, tàbí àpapọ̀ àwọn ohun wọ̀nyí tí ó ní ààbò òfin.
- A máa ń lo àwọn àmì ìṣòwò láti dí àwọn ilé-iṣẹ́ mìíràn lọ́wọ́ lílo àwọn ohun kan náà tí a lè ṣì mú sí ohun tí a ti ṣàmì sí.
- Àmì ìṣòwò ní ààbò òfin láti ọ̀dọ̀ ìjọba tàbí àjọ rẹ̀ lọ́gan tí wọ́n bá ti fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀.

### Ìṣepàtàkì Ìsọlórúkọ-ọ̀tun nínú ọjà

- Láti mú kí ìdámọ̀ ọjà àti ìfọkànsìn oníbààrà dàgbà si.
- Fún dídára àti ìṣedéédéé.

## ṢÍṢE-ỌJÀ-LÓJỌ̀

- Ohun Ìdì kan: jẹ́ kọ̀nténà aláfojúrí tàbí ohun tí a fi pọ́n ọjà kan.
- Ṣíṣe ìdàgbàsókè ohun ìdì ọjà jẹ́ pàtàkì lára ṣíṣe ètò àti mímú gbèrú ọjà nítorí pé ohun ìdì ọjà jẹ́ ohun-èlò fún ìtajà.

### Àwọn àǹfààní ṣíṣe-ọjà-lójọ̀

- Ìdádúró
- Ààbò
- Ìbánisọ̀rọ̀ (Pipèsè àlàyé)
- Ìrọ̀rùn nínú ìpínkiri/gbígbámú
- Níní ìdánilójú ìfijíṣẹ́/lílò aláìléwu
- Ẹ̀dá ọjà ló máa ń sọ àwọn ohun-èlò ìṣe-ọjà-lọ́jọ̀ tó tọ̀nà láti rí pé ó lálòpé.
- Dídára tí ó nílò láti ṣe kódà nínú ṣíṣe-ọjà-lọ́jọ̀.

### Àwọn ìsọ̀rí ohun-èlò ìṣe-ọjà-lọ́jọ̀:

- Fífi-ṣọwọ́: kọ̀nténà, ṣakaṣaka, kádíbọ́ọ̀dù, páálí, kíréétì, àwọn àgbá.
- Gbígbà ọjà tà: agolo onírin, ìgò oníke àti gíláásì àti agbè, ọ̀rá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## ÀWỌN ÀPẸẸRẸ:


• Ìbílẹ̀– ewé, ẹ̀fọ́, aṣọ, igi, awọ, ohun-èlò amọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

•Ajẹmọ́ Ilé-iṣẹ́ – agolo onírin, gíláásì, pépà àti kádíbọ́ọ̀dù, flexible plastic films, cellulose, polythene (LDPE & HDPE), coated films, laminated films, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ



**kín ni ohun tí ó máa ń sọ ohun-èlò ìṣe-ọjà-lọ́jọ̀ tó tọ̀nà**

- Ohun tí ó pamọ́ tí ó sì lálòpẹ́
- Ohun tí ó ṣe é rà tí ó sì rọrùn láti lò
- Ohun tí kò wọ́n láti rí
- Ìbá-àyíká-rẹ́ àti ìbá-òfin-mu
- Ẹ̀dá ọjà




**Kóòdù oní-Báà**

**Kóòdù onísíkáànù**

## Ìṣàmìsí

**Àmì:** jẹ́ èdìdí àlàyé kan, ohun ìdì, èdídí, tàbí ìfiránṣẹ́ tí a tẹ̀ tí a sì sọ mọ́ ọjà kan. Àǹfààní pàtàkì tí ó ní ni láti fi tó àwọn oníbààrà létí nípa àkóónú ọjà náà, àti láti pèsè ìtọ́ni fún lílò rẹ̀.

**Àmì ọjà tuntun:** máa ń pèsè orúkọ ọjà tuntun náà, àmì ìṣòwò, tàbí lógò. Kì í pèsè àlàyé tó tó lórí ọjà.

**Àmì ìṣàpéjúwe:** máa ń pèsè àlàyé nípa ìlò, kíkọ́, ìtọ́jú, iṣẹ́ àti àwọn àbùdá ọjà mìíràn.

Àmì ìṣàpéjúwé máa ń ní déètì àti àlàyé ìpamọ́ fún àwọn ohun oúnjẹ. Ó máa ń pèsè àwọn ìlànà fún ìlò dáadáa àti ìtọ́jú ọjà lórí àwọn ohun tí kì í ṣe oúnjẹ.

**Àmì gíréédì kan:** máa ń tọ́ka sí dídára ọjà náà.



### Àlàyé àmì oúnjẹ

- Orúkọ ọjà
- Ìwọ̀n
- Àwọn èròjà àti àfikún (láti òkè wá sílẹ̀)
- Àlàyé nípa ìṣaralóore àti kálórì (láti inú àtúpalẹ̀ yàrá àyẹ̀wò-sáyẹ́ǹsì)
- Àwọn ìlànà fún lílò
- Orúkọ àti àdírẹ́sì olùṣe/olùpín
- Àwọn ìlànà fún ìpamọ́
- Àlàyé nipa ìpínká, Nọ́ńbà ìdámọ̀
- Traceability / Barcode - (ko si ohun kikọ syst, koodu olupese, koodu ọja & ṣayẹwo nọmba).
- Ọjọ ipari / igbesi aye igbasilẹ
- Nọ́ńbà ìforúkọsílẹ̀ ti NAFDAC
- Iwe-ẹri
- Ikilọ Allergen

### Ṣíṣe àmì: àwọn ìlànà ìṣàmì tó pọn dandan:


- Àlàyé ìṣaralóore tó tọ́nà lórí bí oúnjẹ kan ṣe lè bá gbogbo oúnjẹ òòjọ́ ẹni mu.
- Àwọn oúnjẹ kan pè fún kí olùpèsè àwọn ọjà kan gbé ìkìlọ̀ ajẹmọ́-ìlera lórí wọn.
- Yàgò fún àwọn ẹ̀tọ́ èké tàbí èyí tó ń ṣi ni lọ́nà.
- Awọn iṣedede ofin fun GM, àwọn ọjà alátọwọ́dá àti ìbílẹ̀
- NB: àmì ìṣòwò máa ń rí i dájú pé ọjà jẹ́ gidi
- Dídá àwọn ẹgbẹ́ aláfọwọ́sowọ́pọ̀ sílẹ̀






# ẸKỌ KẸTA

## ÀTÚPALẸ̀ EWU ÀTI ÒGANGAN ÌṢÀKÓSO ALÁGBÁRA (HACCP) PẸ̀LÚ ÈTÒ ÀÀBÒ OÚNJẸ



## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ ìlànà. Àwọn olùkọ́ le ṣe àtúnṣe sí agbọn tó bá wù wọ́n láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Ó yẹ kí wọ́n bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

**Èròǹgbà ní pàtó:**

- Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí olùkópa gbọ́dọ̀ le mọ̀:
- Mọ̀ pàtàkì HACCP
- Ṣàfihàn àǹfààní HACCP
- Sọ òfin méje HACCPw
- Dárúkọ ìgbésè nínú ìlànà HACCP

# ÌTÚPALẸ̀ EWU ÀTI ÀWỌN ÒFIN IBI ÌSÀKÓSO TÍ Ó LAGBÁRA (HACCP) ÀTI ÌGBÉSẸ̀ ÀÀBÒ OÚNJẸ




**ÌFÁÀRÀ:** Láti ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ wọn ní ọdun 1960 gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára arìnrìnàjò-lọ sáfẹ́fẹ́ (space travel), ìsàmúlò òfin HACCP ti nàyẹ́ káàkiri gbogbo iléeṣẹ́ oúnjẹ. Òfin oúnjẹ ìgbàlódé ìrọ̀rùn (Osù Ọ̀pẹ 2010) ni ó yẹ kí ó ṣe atọ́kùn àti lè túbọ̀ ṣe ìgbàwọlé òye èròǹgbà náà. ìwé yìí ṣàfihàn èròngbà HACCP ní bélẹ́ǹjà pẹ̀lú ìdàgbàsókè tí ó mú wọ àgbékalẹ̀ oúnjẹ ìrọ̀rùn.

### Ìtúpalẹ̀ ewu àti ibi ìsàkóso pàtàkì (HACCP)

HACCP ni a lè ṣàpèjúwe gẹ́gẹ́ bí i "ètò oúnjẹ ìrọ̀rùn tí a gbé kalẹ̀ ...fún asèrìnàjò tàbí òsìsẹ́ ojú-òfurufú...; àfojúsùn rẹ̀ ni láti pinwọ́ àwọn ewu tí ó lè fa àìsàn oúnjẹ inú egungun nípa ṣíṣàmúlò ìlànà èyí tí ó dúró lórí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀,bẹ̀rẹ̀ láti inú ohun èlò ìpèèlò ọjà títí tí yóò fi parí ... Ní ti àṣà àti ìṣe, iléesẹ́ àti alábòjútó ti gbárálé sísàbẹ̀wò ẹ̀kọ̀ọ̀kan sí ipò tí bí a ṣé ń ṣe àgbéjáde àwọn ohun-èlò wà pẹ̀lu ṣíṣe àyẹ̀wò sí ọ̀kọ̀ọ̀kan gbogbo ọjà tí wọ́n bá ṣe jádé láti lè jẹ́ kí oúnjẹ náà jẹ́ èyí tí kò ní ìpalára tàbí ewu kankan nínú. Ọ̀nà-ìmúṣe yìí, bákan náà, ní ó fẹ́ látí tún gbérasọ, dípò kí ó jẹ́ olùdáàbòbò tàbí olùpinwọ́ nǹkan, èyí tí ó lè mu kí ó kùnà ju ìgbésẹ̀ tuntun lọ..."

### HACCP fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ àǹfààní sílẹ̀ lórí àwọn ìgbésẹ̀ tí ó ti kọjá. Ní pàtàkì jù lọ, HACCP:

- Àfojúsùn rẹ̀ ni láti ṣàwárí àti pinwọ́ àwọn ewu tí ó le mú kí oúnjẹ wà nínú ìsòrò tàbí ìjàm̀bá
- Ó dúró lórí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó múná dóko
- Ó fààyè gba ìjọba tí ó létò tí ó múnádó látí jẹ́ alákoso àti alábòjútó, oun tí ó fa èyí ni pé ṣíṣe àkọsílẹ̀ bí iṣẹ́ ṣe ń lọ fààyè gba olùwádìí láti rí bí iléesẹ́ kan ṣe ń gbọ́ran tí ó sì ń pa àwọn òfin oúnjẹ́ tí ó lálàáfíà mọ́ àti títẹ̀lé àwọn oun tí yóò máa dẹ́kun ìgbésẹ̀ oúnjẹ tí ó léwù láti ìgbàdégbà dípò kí wọ́n máa wo báwo ní iṣẹ́ ti ṣé ń lọ sí lọ́jọ́kọ́jọ́ àti nígbàkúgbà.
- Ṣíṣe ojúṣe nípa rírí dájú pé oúnjẹ́ wà ní ipò àlàáfíà gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn tí ó ń ṣe oúnjẹ tàbí àwọn tí ó ń pin káàkiri
- Ó ń ran ilé-iṣẹ́ oúnjẹ lọ́wọ́ láti lè bẹ́gbẹ́mu gẹgẹ́ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ lọ́pọ̀lọpọ̀ lọ́jà àgbáyé.
- Ó ń dẹ́kun wàhálà àti ìsòrò okòòwó àgbàyé.

***HACCP (àti àwọn ìlànà àgbékalẹ̀ oúnjẹ tí ó ní àlàáfíà), gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára èrò àti ìwòye, èyí tí ó fa ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn okòòwò oúnjẹ láti lè sàmúlò ọ̀nà láti pinwọ́ oun tí ó ní ṣe pẹ̀lú oúnjẹ tí kò ní ìfọkàntán – èyí tí ó jẹ́ èròǹgbà tí a ti làkalẹ̀.***

# ÌTÚPALẸ̀ EWU ÀTI ÀWỌN ÒFIN IBI ÌSÀKÓSO TÍ Ó LAGBÁRA ÀTI ÀWỌN ÌGBÉSẸ̀ BÍ Á ṢE LÒ Ó




## IntÌfáàrà

"HACCP jẹ́ ètò àgbáríjọ ní ibi tí a ti ń sọ̀rọ̀ nípa oúnjẹ́ tí ó ní àlàáfíà nípa yíyànàná àti dídènà àwọn ewu tí ó jẹmọ́ àgọ́ ara-ẹni, kẹ́míkà(chemical) àti èyí tí a lè fi ojú rí kúrò nínú àwọn èròjà àmúpèèlò,sísàwárí àti ìsọwọ́lo, láti fi pèèlò oun mìíràn ,pipin kákàkiri àti jíjẹ àwọn oún tí a fi gbé jáde. Fún èròǹgbà HACCP láti lè wá sí ìmúsẹ gbogbo àgbárijọ ẹgbẹ́ tàbí àwọn ìgbìmọ̀ gbọ́dọ̀ lè farajìn fún àwọn nǹkan tí ó sodo sínú HACCP.Ilé-iṣẹ́ ní ìfarajìn àti ìfọkànsì sí HACCP nípa pé kí àlákoso àgbà tàbí àwọn adárí ilé-iṣẹ́ tí ó ga ju lọ́ jẹ́ kí àwọn òsìsẹ́ ní àǹfààní sí mímọ pàtàkì pípèsè oúnjẹ tí ó ní àlàáfíà tí kò sì ní ewu.

"A ṣe HACCP ní lílò fún gbogbo ẹ̀ka ilé-iṣẹ́ oúnjẹ kí wọ́n le ba à gbèrú,kórè,tẹ̀síwájú,sísàgbéjádé oun èlò,pínpín ka, àti títa ọjà láti lè sètò oúnjẹ fún jíjẹ.Àwọn ètò ìsaájú bí i kíkọ́ nípa bí a ṣé ń po ọjà tàbí sàgbéjáde ọjà tí ó gbòde kan [current Good Manufacturing Practices (cGMPs).] ni wọ́n jẹ́ ìpìnlẹ̀ pàtàkì fún ìdàgbàsókè àti ìmúsẹ àwọn èrò HACCP láyọ̀ àti àlàáfíà. Ètò oúnjẹ ìrọ̀rùn dúró lórí òfin HACCP tí ó tí dí mímúlò pẹ̀lú ìrọ̀rùn níbi ètò ọ̀gbìn oúnjẹ, ilé-oúnjẹ́ aláràtúntà, àti bí a ṣe ń ṣe oúnjẹ.Òfin méje tí HACCP gbé kalẹ̀ náà ti di ìtẹ́wọ́gbà káàkiri àgbáyé láti ọwọ́ àwọn òsìsẹ́ ìjọba,ẹgbẹ́ onísòwó àti ilé-iṣẹ́ oúnjẹ káàkiri àgbáyé."

HACCP ti di alámójútó ilé-iṣẹ́ tí ó ń ri dájú pé ilé-iṣẹ́ kan gbọ́dọ̀ gbé ìgbésè akin nípa pé bí a sé ń sètò gbígbé oúnjẹ jádé jẹ́ èyí tí kò ní wàhálà tàbí ewu nínú rárá.

- HACCP ni a rí gẹ́gẹ́ bí igbákejì àwọn elétò àyẹ̀wò ìjọba ; ṣùgbọ́n ìjọba sì ń ṣe ojúṣe níbi àwọn ìlànà gbogbo nípa lílo àjọ akóni-níjanu láti ri dájú pé gbogbo àwọn okòòwò ní wọ́n ní èròńgbà HACCP tí wọ́n sì ń ṣàmúlò àwọn èròǹgbà náà gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ.
- Ǹjẹ́ wọ́n tí buwọ́ lu gbogbo àwọn èròǹgbà yìí tẹ́lẹ̀ ni àbí wọ́n ṣe àtúngbéyẹ̀wọ̀ rẹ̀ nígbà tí wọ́n sàyẹ̀wò sí oun èlò àyíká àti àwọn àkọsílẹ̀? Fún bí àpẹẹrẹ, "ìdásílẹ̀ náà gbọ́dọ̀ bẹ̀rẹ̀ àwọn iṣẹ́ tí yóò sọ nípa bí èròǹgbà HACCP ṣe ń ṣiṣẹ́ sí gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe kọ̀wé rẹ̀." Ojúṣe náà wà lọ́wọ́ ilé-iṣẹ́; kìí ṣe lọ́wọ́ àwọn elétò ìjọba.
- HACCP fààyè gbà (bèèrè fún) okòòwò kọ̀ọ̀kan láti dojú kọ iṣẹ́ wọ́n pẹ̀lú àwọn àwòmọ́ wọ́n dípò kí wọ́n ní àwọn ìlànà àyẹ̀wò èyí tí ó le má mu rọrùn láti mọ pàtàkì okoòòwò kọ̀ọ̀kan àti àwọn oúnjẹ kọ̀ọ̀kan tí a gbé jáde. Àfojúsùn HACCP kìí ṣe láti ní àwọn ilànà ìpèsè tí ó dúró déédé bí kò ṣe láti ní ìlànà àmójútó tí ó péye láti rí dájú pé oòkòòwò kọ̀ọ̀kan (lái fi tí ìlànà bí a ti ṣe ń pèsè

nǹkan ṣe) ń ṣe àwọn ọjà tí ó láàáfíà nípa dídẹ́kun wàhálà àti ewu oúnjẹ ìrọ̀rùn.

- Òfin méje HACCP

1. Òfin 1: ṣe ìtúpalẹ̀ wàhálà àti ìsòrò.
2. Ofin 2: Sàfihàn ibi ti ìdàrí tí ó lágbára jù lọ.
3. Òfin 3: Ṣe àgbékalẹ̀ ibi tí ó lágbárá .
4. Òfin 4: Ṣàgbékalẹ̀ ìlànà ìmójútó.
5. Òfin 5: Ṣàgbékalẹ̀ àwọn ìgbésè àtúnse tó yakin.
6. Òfin 6: Ṣe àgbékalẹ̀ ìlànà ìsàmúdájú tàbí ìjẹ́rìí.
7. Òfin 7: Ṣe àgbékalẹ̀ ìlànà ṣíṣe àkọsílẹ̀ gbogbo n tí bá ń sẹlẹ̀ àti ìsàkópamọ́ ìwé àṣẹ.

- Ṣàgbéyẹ̀wò àwọn èrò ìgbéléwọ̀n ewu àti ìsàkóso rẹ̀ láti le mọ ìjọra tí ó ní pẹ̀lú òfin méje HACCP tí a ti dárúkọ sókè yìí.

### O nílò kọjá èròǹgbà ẹyọ kan HACCP bí?

Ètò HACCP ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a nílò fún èròjà oúnjẹ kọ̀ọ̀kan,àti fún ìlànà ìgbésẹ̀ kọ̀ọ̀kan àti àwọn ohun èlò kọ̀ọ̀kan bí ìlànà náà bá gbọ̀nà àrà yọ tàbí ó mú àwọn ewu ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ kọ̀ọ̀kan wá. Bí a bá lo oun ọ̀gbin A láti fi pèsè ọjà M àti ọjà N, ṣùgbọ́n tí ewu tí ó rọ̀ mọ́ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n yàtọ̀,ilé-iṣẹ́ nílò láti sàyẹ̀wò n tí ó le fa ewu lẹ́yọkọ̀ọ̀kan àti àwọn ètò HACCP fún ọja kọ̀ọ̀kan.Tí ilé-iṣẹ́ tàbí okòòwò D ṣàgbéjáde ọjà F ní ọ̀nà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n sì lo oríṣi ìlànà àti ìgbésẹ̀ èyí tí o le fá oríṣi ewu ọ̀ọ̀tọ̀, ilé-iṣẹ́ tàbí okòòwò náà nílò kọjá ìgbésẹ̀ HACCP kan lọ.Ìgbésẹ̀ tàbí ètò HACCP kàn kò lè tó fún gbogbo àwọn ètò náà bí àbájáde rẹ̀ tàbí ìlànà rẹ̀ jẹ́ èyí tí ó ní oríṣiríṣi ewu tàbí èyí tí ó nílò oríṣirísi èròǹgbà láti dojú kọ àwọn ewu náà.

**HACCP** jẹ́ èyí tí a nílò fún àwọn ìlànà àti ìgbésẹ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn oúnjẹ (Sẹ́ẹ̀rẹ́ 2011)

### Òfin àtúnrọ oúnjẹ ìrọ̀rùn ti ọdún 2010 bèèrè fún ètò oúnjẹ ìròrùn fún gbogbo ìlànà àgbékalẹ̀ àwọn yòókù. Ṣùgbọ́n bákan náà

- FDA ń bèèrè fún kí òfin HACCP dí mímúlò lọ́dọ̀ àwọn aláràtúntà àti ibi tí wọ́n ti ń ta oúnjẹ káàkiri ilé iṣẹ́ oúnjẹ oúnjẹ -- ṣàlàyé abala tí ó jẹmọ́ ọjà títà àti òfin tí ó de oúnjẹ jíjẹ àti títà
- HACCP ní a yàn fún b.a abala ibi tí a ti ń gbé nǹkan jáde (àyàfi ìgbà tí a tó mú HACCP wọnu ẹ̀ka ìgbéjáde, ètò ọ̀gbìn tí ó dúró déédé (GAP)ní a ó fẹ́ ṣàmúlò ; a lè sọ pé GAP lè yípadà kó di HACCP).
- Ìfẹnukò àgbàríjọ HACCP dábàa pé ó ṣe é ṣe níjọ́kan kí ó nàyẹ́ káàkiri gbogbo ilé-iṣẹ́ oúnjẹ(Ìsàgbéjáde, ìlànà, ìsètò) àti káàkiri àgbáyé(fún bí àpẹẹrẹ, wo Codex àti ISO) .

### Bu ọwọ́ lu HACCP

- Àjọ akóniníjanu tí wọ́n ní ṣe pẹ̀lú HACCP ni FDA, USDA,àti àwọn àjọ àwọn mìíràn tí ó jẹ́ ti ìpílẹ̀ . Àwọn àgbáyé gan-an náà ń sàtìlẹ́yìn fún HACCP, wo Codex àti ISO.
- Èròǹgbà HACCP ni láti dẹ́kun àwọn ewu tó rọ̀mọ́ àwọn àgbéjáde oúnjẹ àìdára tó,èyí tí ó tún lè mú ìrúgọ́gọ́ bá àwọn oun tí wọ́n ń ṣe jáde.

### Àwọn ìgbésẹ̀ ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀

1. Kó ẹgbẹ́ HACCP jọ,tí ó fi kan èèyàn kan tí ó ti gba ìdánilẹ́kọ̀ọ́ HACCP
2. Ṣe àpèjúwe oúnjẹ àti ọ̀nà tí à ń gbà sé jáde pẹ̀lú bí a ṣe ń pin káàkiri
3. Ṣàgbékalẹ̀ àti àrídájú ìlanà àtẹ áwòrán atọ́ka asàkópò [flow diagram(s)]

4. Ṣe àgbéyẹ̀wò bóyá àwọn oun tí à ń gbé jáde lè ṣe é pín sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ̀ nípa wíwo ìlànà bí a ṣe ń gbé wọn jáde

**ÒFIN I: ṢE ÌTÚPALẸ̀ EWU**

- ÀWỌN EWU ARA
- ÀWỌN EWU KẸ́MÍKÀ
- ÀWỌN EYI TÍ Ó HÀNDE
- ÀKỌSÍLẸ̀ YÌÍ MÁA Ń FẸ̀ SI.

ÒFIN II: ṢE ÀWỌNÀWÁRI IBI TÍ Ó TI LÁGBÁRA JÙ

ÒFIN III: ṢE ÌFÌDÍMÚLẸ̀IBI TI ÀWỌN Ọ̀KỌ̀Ọ̀KAN WỌN LÁGBÁRA DÉ

ÒFIN IV:ṢÀGBÉKALẸ̀ ÀWỌN ÌLÀNÀ ÀMÓJÚTÓ


ÒFIN V: ṢÀGBÉKALẸ̀ ÀWỌN ÌGBÉṢẸ̀ ÌTỌ́SỌ́NÀ

ÒFIN VI: ṢÀGBÉKALẸ̀ ÀWỌN ÌLÀNÀ À Ń GBÀ KỌ NǸKAN PAMỌ́

ÒFIN VII:ṢÀGBÉKALẸ̀ ÀWỌN ÌLÀNÀ ÌJẸ́RÌÍSÍ

- Ìsọdòótọ́
- Ìjẹ́rìísí tí ó n lọ lọ́wọ́
- Àtúngbéyẹ̀wò

## HACCP lè tún jẹ́ bíbuwọ́lù pẹ̀lú àwọn ìlànà méjìlá (12-step process)




**Ìgbésẹ̀ #1** Kó ẹgbẹ́ HACCP jọ

- Ìfọkànsìn láti ọ̀dọ̀ àwọn.
- Ọmọ ẹgbẹ́ tí ólójúṣe tó pọ̀.
- Mọ bí a ṣe ń gbe jáde àti àwọn n tí a fi ń gbé jáde

- Mọ bí a ṣe ń gbé ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà.
- Gbọ́ àgbọ́yé àwọn òfin HACCP .

**Ìgbésẹ̀ #2 Ìlànà àti bí a ṣe ń ṣe àpínká àwọn oúnjẹ**

- Àwọn HACCP ni a nílò fún oun ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí a bá gbé jáde.
- Irú ọgbọ́n wo  ni a lè lò láti fi pín àwọn oun tí a gbé jáde?
- Ǹjẹ́ ohun tí a gbé jáde náà nílò kí ó tutù,ganpa tàbí kí ó wà bí ó ṣe wà?
- Àwọn ìdojúkọ̀ kékèké wo àbí àwọn wàhálà wo ní ó rọ̀ mọ́ oúnjẹ tí a ṣe jáde náà gẹ́gẹ́ bí àdámọ́ rẹ̀?

**Ìgbésẹ̀ kẹta #3** Ohun tí a fẹ́ lò ó fún àti àwọn tí yóò lò

- Ipa wo ni oun èlò náà yóò ní lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn lápapọ̀?
- Ǹjẹ́ ò ń ṣe àfojúsùn fún abala kan ninú ọjà?pàápàá jù lọ àwọn ònrajà?  Ǹ jẹ́ àfojúsùn rẹ̀ jẹ́ àwọn tí ó ń tà á lójú páalí àbí àwọn tí ó ń tàá lẹ́yọ ẹyọ?
- Kí ni àwọn oun àmúpèèlò rẹ̀? Ǹ jẹ́ ọ̀kankan nínú àwọn ohun àmúpèèlò náà léwu fún oúnjẹ bí ?
- Ǹ jẹ́ oúnjẹ́ náà ní àwọn àdámọ́ kan pàto tí ó máa ń ṣe, bí i, àwọn oúnjẹ tí mò ní ọ̀rá tó pọ̀

**Igbéṣẹ̀ #4** Ṣàgbékalẹ̀ àtẹ áwòrán atọ́ka asàkópò

- àtẹ áwòrán atọ́ka tàbí àtẹ atọ́ka asàkópò náà gbọ́dọ̀ kó gbogbo ìlànà bí a ṣe ń ṣe nǹkan jáde sínú. Ti Kìí ṣe èyí tí wọ́n ń fi èrọ yàwòrán rẹ̀.
- ṣe àrídájú ìbámu tàbí ìṣedéédé àti pípépéré tàbí ìṣeparí àwòràn atọ́ka náà.
- Gbé àwòràn atọ́ka náà lọ́ sí ẹ̀ka tí ó máa ń ṣe àgbéjáde láti lè mọ̀/rí àrídájú ìṣedéédé rẹ̀.

**Ìgbésẹ̀ #5** Ṣe ìtúpalẹ̀  àwọn wàhálà tàbí ìsòro

- Ǹ jẹ́ ohun tí ó kàn ọ́ ní àwọn ewu tí ó ní ṣé pẹ̀lú àwọn kòkòrò kéékèèké àgọ́ ara ( microbiological), ewu ti o rọ̀ mọ́ kẹmíka  tàbí àwọn ewu èyí tí ó tí a lè fojú rí  (lẹ́ẹ̀kan sí ,àkọsílẹ̀ yìí máa n gbòòrò )?
- Ṣe ìdámọ̀ àwọn ibi tí ewu ti lè ṣẹlẹ̀ nínú  ìlànà bí a ṣé ń ṣe n lọ́pọ̀kúọ̀yọ̀kú.
- Ro wàhálà ewu àti saburú rẹ̀ tí ó bá ṣẹlẹ̀  (bí ó bá ṣẹlẹ̀).
- Ránti pé – ewu kò lè dúró lẹ́gbẹ̀ẹ́ ààbò ;kì í dojú kọ àwọn òsòro tí ó burú gidi (kódá kí wọ́n jọ́ ní ìbásepọ̀).
- ṣe àfihàn àwọn ọ̀nà ìdáàbòbò àti ìdẹ́kun tí a lè sàmúlò.

Ìgbésẹ̀ #6  Àwọn ààyè ìsàkóso tó ṣe pàtàkì  (CCP)

- CCP – Ibikíbi tí a bá ti lè sàmúlò ìsàkóso láti fi le dènà ewu láàyèkáàyè  níbí ìlànà ìṣekópọ̀ àti àwọn ìlànà bí a ṣe ń pin káàkiri.
- GMPs  ó yẹ kí ó lè dènà àwọn ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ewu àti wàhálà.
- CCP ti ó wà fún ọjà kan lè máa wúlò fún ọjà mìíràn.

**Ìgbésẹ̀ #7** Àwọn ìdíwọ̀n pàtàkì

- Ìdíwọ̀n tí ó gbọ́dọ̀ sẹlẹ̀ láti fi ri dájú pé ohun-èlò náà wà ní àlàáfíà.
- Kíkọjá àwọn ìdíwọ̀n pàtàkì yìí túmọ̀ sí pé ewu tí ó lágbára tí wà.
- Àwọn ìdíwọ̀n pàtàkì yìí lè jẹyọ látara àwọn ìlànà tí ó gbámúsé (b.a., ìwé-àkọsílẹ̀), àwọn ìlànà, àwọn ẹ̀kọ́ kíkọ́, àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́, abbl.
- Àpẹẹrẹ àwọn ìdíwọ̀n pàtàkì: bí nǹkan ṣe gbóná-tutù sí (fún àwọn ohun-èlò kọ̀ọ̀kan wọ́n le jẹ́ èyí tí ó máa ń gbóná gan-an àtí fún àwọn ohun-èlò mìíràn wọ́n lè jẹ́ èyí tí ó máa ń tutu gan-an ni), àkókò, pH,àwọn ìṣẹ́kù,oríṣi àti iye kòkòrò àìfojúrí.

**Ìgbésẹ̀ #8** Ìsàmòjútó/ìsàyẹ̀wò

- Ṣàgbékalẹ̀ àwọn ètò ìwòyesí tàbí àwọn òdiwọ̀n ní sísẹ̀ntẹ̀lẹ́.
- Gbọ́dọ̀ le sàkoso
- Gbọ́dọ̀ lè ṣe n tí a fẹ́ kí ó ṣe.
- Àsìkò ìbójútó gbádọ̀ ṣe é gbẹ́kẹ̀lé.
- Gbọdọ̀ yá kíákía, Kò sí ìtúpalẹ̀ gígun.
- Èrò pípéyé láti rí pé ìbójútó náà wá dí ṣíṣe.

**Igbésẹ̀ #9** Àwọn ìgbésẹ̀ àtúnṣe

- Sọ ìgbésẹ̀ láti gbé nígbà tí ìyapa bá wáyé.
- Agbọ́dọ̀ ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ìgbésẹ̀ àtúnṣe.
- Ìmúkúrò àwọn ewu gangan tabí èyí tí ó farajọ ewu.
- Wà ní ìmúrasílẹ̀ láti dá àwọn ọjà dúró bí ó bá jẹ́ pé ìsòro kan ti fojú hàn.
- Ṣe ìgbésẹ̀ àti dènà ìsẹ̀lẹ̀ irúrẹ̀ lọ́jọ́ iwájú.

**Ìgbésẹ̀ #10** Àwọn àkọsílẹ̀

Gbọ́dọ̀ ní gbogbo abala ètò HACCP, láti ọ̀dọ̀ àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ nípaṣẹ̀ gbogbo ìgbésẹ̀ kìn-ín-ní títí dé ìkejìlá (#1 – 12)

**Ìgbésẹ̀ #11** Ìjẹ́rìísí

- Kún fún oríṣiríṣi àwọn ọ̀nà, ìlànà tàbí àwọn àyẹ̀wò ní ìbámu pẹ̀lú ìsàmòjútó.
- CCP’s wà lábẹ́ ìsàkoso
- A ti ṣe ìyípadà pàtàkì.
- Gbogbo àkọsílẹ̀ pátá ní ó pé pérépéré.
- Ṣíṣe ìtúpalẹ àyẹ̀wò tàbí àpẹ̀ẹrẹ̀ láti lè ní ìdánilójú.
- Ìkẹ́kọ̀ọ́ àti Ìmọ̀.

**Ìgbésẹ̀ #12** Ìkádìí àti Àtúngbéyẹ̀wò

- Ó kéré tán àtúngbéyẹ̀wò ẹ̀ẹ̀kan lọ́dún.
- Ìgbàkígbàtí tí ọ̀nà ìṣelọ́pọ̀ bá yípadà tàbí àwọn ọjà bá yípadà.
- Ìgbàkígbàtí tí àwọn ohun àmúpèèlò tuntun tàbí oríṣun bá di lílò.
- Ìgbàkigbà tí ìlànà àkọsílẹ̀ bá yípadà.
- Ìgbàkigbà tí ohun èlò titun bá ti wà ní àfikún; ní àwọn ààyè kọ̀ọkan, kódà dídínkù iṣẹ́ ohun náà lè jẹ́ èyí tí ó ṣe pàtàkì gẹ́gẹ́ bí àtúngbéyẹ̀wò HACCP..
- Ìgbàkígbà tí ìyípadà tàbí àwọn ìsínípò bá wà láàrin òsìsẹ́.
- Ìgbàkígbà tí ìyípadà bá wà ni ibi ìkópamọ́ tàbí ìpínká.

## HACCP àti òfin oúnjẹ ìrọ̀rùn ìgbàlódé

Títẹ̀lé ìgbésẹ̀ òfin oúnjẹ ìrọ̀rùn ìgbàlódé, ètò oúnjẹ ìrọ̀rùn (HACCP pẹ̀lú orúkọ mìíràn?) ni gbogbo ilé-iṣẹ́ nílò ní ètò ẹ̀ka ilé-iṣẹ́ oúnjẹ́ tí kò wulẹ̀ tí ì tẹ̀lé àṣẹ HACCP tẹ́lẹ̀. Àwọn kókó wọ̀nyí ni a mú láti inú òfin yẹn.




### Àwọn ètò oúnjẹ ìrcrọ̀rùn gbọ́dọ̀ dálórí àwọn kókó wọ̀nyí:

- **Sọ, se ìkádìí àti àgbékalẹ̀ ìtúpalẹ̀ kíkọ́ nípa oun tí a mọ̀ tí ó yẹ tàbí ṣe é ṣe kí ó jẹ́ àwọn ewu** èyí tí ó lè ní ìbásepọ̀ pẹ̀lú ohun-èèlò, pẹ̀lú (A) Àbímọ́, Kẹ́míkà, àfojúrí, and àti àwọn ewu ohun ìjà-olóró (radiological hazards), májèlé adayébá(natural toxins), òògùn-apakòkòrò, òògùn-àlòkù, jíjẹrà, kòkòrò-àìfojúrí, awọn àìsàn látára-fífi ọwọ́ kàn, àti oúnjẹ tí a kò fọwọ́sí pẹ̀lú àwọn àfikún àwọ ; (B) Àwọn ewu tí ó wáyé láìnídìí,tàbí ó ṣẹlẹ̀ láì mọ̀ọ̀mọ̀; àti (C)àwọn ewu tí ó le wáyé pẹ̀lú àmọ̀ọ̀mọ̀, pẹ̀lú nípaṣẹ̀ ìgbésùmọ̀mí.

Àwílé: note ṣàkíyèsí ìkọlù-àmọ̀ọ̀mọ̀ tí ó fojúhànpé a dárúkọ lórí okòòwò oúnjẹ.

- **Ṣàfihàn àti ìfimúlẹ̀ àwọn ọ̀nà ìsàkóso ìdènà,** pẹ̀lú ibi ààyè ìsàkóso pàtàkì, láti lè pèsè ìdánilójú pé àwọn ewu tí a sàwárí nínú àgbéyẹ̀wò ìtúpalẹ̀ ewu yóò dínkù jọjọ tàbí kápá rẹ̀; àwọn oúnjẹ́ tí jẹ́ ṣe lọ́pọ̀ yanturu,èyí tí a ti ṣiṣẹ́ lé lórí, sé pa, tàbí èyí tí ó wáyé nípaṣẹ̀ irú ilé-isẹ́ bẹ́ẹ̀ kò lè ní ìdọ̀tí tàbí kí jẹ́ ayédèr
- **Sàmójútó pàtàkì bí a ṣe ń ṣe àwọn ìsàkóso dídènà tí a ti fọwọ́** to láti ri dájú pé àwọn náà náà dínkù tàbí di yíyẹra fún.

- **Ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìlànà tí a lè múlò láti rídájú pé bí ọ̀nà ìsàkóso dídìnà náà kò bá di mímúlò bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ tàbí kò ṣiṣẹ́ tí ó yẹ kí ó ṣe** (1) ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà ti di gbígbé láti dènà bóyá ó le ṣe é ṣe kí ìjákulẹ̀ ìfimúlẹ̀ náà tún wáyé; (2)gbogbo oúnjẹ tí ọ̀rọ̀ náà kàn ni tí di gbígbéyẹ̀wò fún ààbò (3) Gbogbo àwọn oúnjẹ tí wọ́n tí ní àlèébù ni à kò jẹ́ kí wọ́n wọ ọjà bí okòòwò náà kò bá lè ri dájú pè àwọn oúnjẹ tí ó ní àlèébù náà kò di àìmọ́ tàbí di àyédèrú.
- **Rí dájú pé** (1) àwọn ìsàkóso dídènà náà tí a buwọ́ lù tó láti dènà àwọn ewu tí a tí tọ́ka sí; (2) àmójútó wà fún okòòwò gẹ́gẹ́ bí ó ṣé jẹ́ dandan láti ọwọ́ òfin; (3) okòòwò ń gbé ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà nípa ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà ní gbígbé; (4) the àwọn ọ̀nà dídènà tí a ti buwọ lù náà múná dóko tí wọ́n sì tún ń pinwọ́ tàbí dènà kí àwọn ewu ewú tí ó fojúhàn náà máa ba à tún wáyé mọ́, pẹ̀lú nípa lílo àwọn oun èlò agbègbè àti ètò yíyẹ ohun-àgbéjáde wò àti àwọn ọ̀nà mìíràn tí ó tọ́; àti (5) àkọsílẹ̀, èto àtúngbéyẹ̀wò àtigbàdégbà wà láti rí dájú pé ètò ńàa sì ń ní ìbámu pẹ̀lú àwọn èròjà àmúpèèlò, ààyè tàbí ipò àti ìlànà irinsẹ́(ohun-èlò) àti àwọn àyípadà tuntun tí ó ti dé.
- **ṣè ìtọ́jú,** fún ó kéré tán ọdún méjì, ìwé-àkọsílẹ̀ ń sàkópamọ́ àwọn ìsàmòjútó ìsàkoso dídènà tí a lù ní òǹtẹ̀, àpẹẹrẹ àwọn ohun-èlò tí kò ní ṣe pẹ̀lú ohúnjẹ àlàáfíà,èsì àyẹ̀wò àtì àwọn ọ̀nà tí à ń gbà ní ìdánilójú, àpẹẹrẹ nígbà tí ìfídímúlẹ̀ àwọn ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà, àti àwọn ǹǹkan tí a fẹ́ kí àwọn ìsàkóso dídènà àti àwọn ìgbésẹ̀ tí ó tọ́ ṣe.
- **Sàgbékalẹ̀ ètò kíkọ** tí ó sàkọ́sílẹ̀ àti àpèjúwe ìlànà èyí tí okòòwò náà ń lò láti lè ni ìbámu pẹ̀lú àwọn àlàkalẹ̀ yìí, pẹ̀lú ṣiṣe àtúpalẹ̀ àwọn ewu àti bí a ṣe ń da mọ̀ ọ̀nà ìsàkóso dídènà tí à ń gbà láti fi kojú àwọn ewu náà. Irú àkọsílẹ̀ ètò bẹ́ẹ̀, pẹ̀lú ìsàkọsílẹ̀, gbọ́dọ̀ lè wà ní arọ́wọ́tó àwọn àwọn aláṣẹ asoju tí FDA lórí àwọn ìbéèrè ẹnu tàbi tí ojú-ìwé.
- **Ṣe àtúngbéyẹ̀wò ìtúpalẹ̀** nígbàkígbà tí àyipadà pàtàkì bá wáyé lórí àwọn ohun tí a ṣe lórí àwọn ǹǹkan èlò tí àyípadà náà sì fààyè gba ewu pàtàkì tí ó mọ́gbọ́n dáni tàbí ìrúgọ́gọ́ àwọn ewu ìsaájú tí a ti tọ́ka sí,tàbí kí ó máa wáyé ní ẹ̀ẹ̀kan láàrin ọdún mẹ́taméta, èyí tí ó wù kí ó jẹ́ tẹ́lẹ̀ Irú àtúngbéyẹ̀wò bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ pari pẹ̀lú àfikún àwọn àkóso dídènà tí a nílò láti fi kojú àwọn ewu tí a fojú rẹ̀ han,tí ó bá wà, gbọ́dọ̀ di bíbuwọ́ lù kí ó tó di pé àyípadà iṣẹ́ níbí àwọn ohun èlò náà bẹ̀ẹ̀rẹ̀ sí ni gbéraṣọ. Okòòwò náà gbọ́dọ̀ ṣe àtúngbéyẹ̀wò àkọsílẹ̀ èto tí irú àyípadà bẹ́ẹ̀ bá lọ wáyé tàbí àkọsílẹ̀ tàbí àkópamọ́ láti fi ṣe ìkádìí pe kò sí àfikún tàbí àtúngbéyẹ̀wo ìsàkósó dídèna tí a nílò. The FDA lè bèèrè fún àtúngbéyẹ̀wò ìtúpalẹ̀ ní ìbámu àwọn ewu tuntun àti ìdàgbàsókè àgbọ́yé ìmọ̀-ìjìnlẹ̀,pẹ̀lú, gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́ àtí bí ó ti yẹ, èyí tí ó wáyé látí ọ̀dọ̀ ẹ̀ka ààbọ̀ ìlú-ẹni nípa ohun àbímọ́,kẹ́míkà, àìsàn inú àgọ́ ara(radiological) àti àwọn ìsàgbéyẹ̀wò yíyẹ ewu ìgbésùnmọ̀mí wò.



## Ìsọnísókí

HACCP àti ètò oúnjẹ́ ìrọ̀rùn jẹ́ ìlànà tí okòòwò oúnjẹ́ lè tẹ̀lé láti dẹ́kun ewu tí ó rọ̀mọ́ oúnjẹ tí kò fọkànbalẹ̀. It Ó ti yípadà di òfin ìtọ́sọ́nà pàtàkì fún yíyẹ ewu ti tí o rọ̀ mọ́ ìgbésẹ̀ oúnjẹ àti ìsàkóso. Àgbọ́yé àti ìbuwọ́lù HACCP tí gbáwọ́ mìíràn pẹ̀lú ìrírí. okòòwò oúnjẹ́ ní ó ní ètọ́ láti sàgbékalẹ̀ àti ìfilọ́lẹ̀ ìláàáfíà oúnjẹ/ètò HACCP fún oúnjẹ́ àti ìgbésẹ̀ inú rẹ̀ pẹ̀lú ìṣelọ́pọ̀. Ìwàláláàfíà oúnjẹ/òfin HACCP ni a nílò fún oúnjẹ kọ̀ọ̀kan àti ètò ìgbésẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí okòòwò oúnjẹ́ sàmúlò nítorí pé gbogbo oúnjẹ àti gbogbo ètò ìgbésẹ̀/ìlànà tí ó mú ewu ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ lọ́wọ́tí ó sì nílò èrò ìsàgbéyẹ̀wò ewu ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

- HACCP gbé ojúse àti ipa pàtàkì fún ṣiṣe ipinu tí ó yẹ,ètò ìrọ̀rùn kọ̀ọ̀kan fún oúnjẹ́ lórí okòòwò,dípò etò ìjọba tí ó gbòòrò(“broad-brush”). HACCP jẹ́ ìlànà tí ó ń sètò, sòǹtẹ̀, àti ṣe àrídájú ìlànà tí okòòwò oúnjẹ́ gbọdọ̀ tẹ̀lé; kìí ṣe ìdiwọ̀n òǹkà ní okòòwò náà gbọ́dọ̀ tẹ̀lé. Irúfẹ́àwọn ìdiwọn òǹkà bẹ́ẹ̀ jẹ́ èyí tí okòòwò oúnjẹ kọ̀ọ̀kan gbékalẹ̀ pẹ̀lú òye ìmọ̀-ìjìnlẹ̀.

Oúnjẹ tí a ṣe láì sí ààbò oúnjẹ tàbíètò HACCP tàbí èyí tí ètò rẹ̀ kò tẹ̀lé ètò okòòwò oúnjẹ́ tó ní ààbò jẹ́ èyí tí a gbà gẹ́gẹ́ bí oúnjẹ tí ó ní àbùkù tí ó sì di èèwọ̀ fún títà.

1. Àwọn òfin kàǹpá.
2. ìgbìmọ̀ kò tí ì sè ní kanpá pé kí oko bẹ̀ẹ̀rẹ̀ àti máa tẹ̀lé àwọn ìgbésẹ̀ HACCP,ṣùgbọ́n ààyè tóóró tí wà láàrin oko(b.a àgbéjáde)ìlànà oúnjẹ sì ń tẹ̀síwájú láti máa yí lọ sí ibi àgbéjáde b.a, ní báyìí ọ̀pọ̀ oríṣiríṣi okòòwò oúnjẹ ní ó nílò láti sàmúlò àwọn ètò HACCP. Fún bí àpẹẹrẹ ,oko tí ó jẹ́ pé kìí ṣe àwọn èso àti ewébẹ̀ nìkan ni ó ń gbé jáde, ṣùgbọ́n tí ó tún ń pèsè wọn fún àgbéjáde ọjà tuntun, wọ́n sì wà ní ìbámù àgbékalẹ̀ ìlànà FDA pẹ̀lú ìlànà tí ilé-iṣẹ́ ń lò àti pàápàá díẹ̀ nínú oko tí ó wá ní àgbọ́ni ìgbéjáde.Ìlànà tí ó wà lórí oko kì í ṣe èyí tí ó fi gbogbo ara sàjòjì sí àgbéjáde b.a; fún bí àpẹẹrẹ̀ àkọsílẹ̀ gbogbo ń tí ó bá sẹlẹ̀ lókò jẹ́ ti ìjọba àpapọ̀,ìjọba ìpínlẹ̀ àti ìbílẹ̀ nílò fún ọdún mẹ́wàá. Ìjíròrò nígbàmìíràn ní yóò se àtúntò ohuní ó yẹ kí oko tí ó pèsè àti ìlànà tí a fi ń gbe èso titun tàbí èyí ti a fi ń ṣe òmíràn àti ewébẹ̀ jáde.
3. Àṣẹ FDA gbòòrò, fún bí àpẹẹrẹ, agara ọ̀kà tí a fi ń tọ́jú àlìkámà fún ṣíṣe sí oúnjẹ ènìyàn jẹ́ èyí ó wà ní ìkáwọ́ àṣẹ FDA.
4. Ṣùgbọ́n ilé-iṣẹ́ oúnjẹ ń gbé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìnílò lórí èròjà àti awọn tí ó ta erè oko gẹ́gẹ́ bí ìjọba náà ṣe gbáráléàwọn tí ó ń pin.

# ÈKỌ́ KẸRIN

# ÀWỌN ÌLÀNÀ ÌLÀKALẸ̀ ÀJỌ NAFDAC FÚN ÌFORÚKỌ-SÍLẸ̀ ÀWỌN ỌJÀ OÚNJẸ



## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ ìlànà. Àwọn olùkọ́ le ṣe àtúnṣe sí agbọn tó bá wù wọ́n láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Ó yẹ kí wọ́n bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

---

### Àwọn Èròngbà ní Pàtó:

Èròǹgbà àgbékalẹ̀ yìí ni láti kọ́ àwọn tó ń pèsè oúnjẹ àti àwọn tí ó ń ṣètò ọjà ajẹmọ́-àgbẹ̀ ní àwọn ìlànà tí àjọ NAFDAC gbé kalẹ̀ fún ìforúkọsílẹ̀.

---

### Àkóónú

- Àṣẹ, Ìran, Àfojúsùn àti Èròǹgbà Ìkọ́ni NAFDAC
- Àwọn àǹfààní pàtàkì NAFDAC kan
- Díẹ̀ nínú àwọn ìlànà àti pofin NAFDAC lórí oúnjẹ
- Àwọn ìgbésẹ̀ fífi orúkọ ọjà sílẹ̀ pẹ̀lú Àjọ NAFDAC
- Àwọn Ìwé Ìforúkọsílẹ̀
- Àwọn Ìlànà Gbogbogbòò/ Àwọn ìlàkalẹ̀ fún: ilé /ibùdó, ètò àti òṣìṣẹ́, irinṣẹ́, ìlànà ìṣàmìsí àti pàtàkì rẹ̀ lórí ìpèsè omi
- Oríkì àti àwọn àpẹẹrẹ Ìgbésẹ̀ fún Ìpele Iṣẹ́
- Àwọn Ìwé tí a gbọ́dọ̀ kó pamọ́ nínú Ìtajà oúnjẹ
- Ìkádìí

---

## ÀWỌN ÀǸFÀÀNÍ PÀTÀKÌ NAFDAC KAN




1. **Ìforúkọsílẹ̀:** forúkọsílẹ̀, fífún ni ní àṣe láti tajà àti fífi àwọn déétà àwọn ọjà tí wọ́n ti forúkọ wọ́n sílẹ̀ pamọ́.
2. **Ìwádìí:** Ṣe iwadi ti o yẹ si awọn agbegbe iṣelọpọ ati awọn ohun elo aise fun awọn ọja ti a ṣe ilana.
3. **Àyẹ̀wò:** Ṣe ayewo ti awọn ọja ti a fi ofin ṣe wọle ati ṣeto awọn ọna idaniloju didara to yẹ
4. **Ṣajọ boṣewa:** Ṣajọ awọn ilana alaye ni pato ati awọn itọnisọna fun iṣelọpọ, gbigbe wọle, gbigbe ọja si ilẹ okeere, titaja, pinpin ati iforukọsilẹ awọn ọja ti a ṣe ilana
5. **Ilana ati iṣakoso:** Ṣakoso ati ṣakoso akowọle wọle, gbigbe ọja si ilẹ okeere, iṣelọpọ, ipolowo, pinpin kaakiri, tita ati lilo Awọn ọja ti a ṣe ilana.
6. **Kede lori didara:** Kede lori didara ati ailewu ti Awọn ọja lẹhin igbekale ti o yẹ

### Díẹ̀ nínú àwọn ìlànà àti pofin NAFDAC lórí oúnjẹ

- Àwọn ìlànà fún àyẹ̀wò àti òsùnwọ̀n fún àwọn iṣẹ́ ṣíṣe oúnjẹ lọ́jọ̀ ní Nàìjíríà
- Àwọn ìlànà àyẹ̀wò ìpèsè òṣùwọ̀n fún àwọn iṣẹ́ ṣíṣe oúnjẹ olósùnwọ̀n kékeré ní Nàìjíríà
- Àwọn ìlànà àyẹ̀wò ìpèsè òṣùwọ̀n fún àwọn iṣẹ́ oúnjẹ títà olósùnwọ̀n kékeré ní Nàìjíríà
- Àwọn ìlànà ìdásílẹ̀ ilé ìtajà oúnjẹ ní Nàìjíríà
- Àwọn ìlànà ìṣe tó dára tó sì bágbàmu fún oúnjẹ àti ọjà oúnjẹ
- Àwọn òfin ti 2005 fún ìṣàmìsí oúnjẹ tí a pilẹ̀ ṣe lọ́jọ̀
- Àwọn òfin ìró-oúnjẹ lágbára ti ọdún 2019
- Àwọn òfin ìṣàfikún fún oúnjẹ ti 2019




### Àwọn ìgbésẹ̀ fífi orúkọ ọjà sílẹ̀ pẹ̀lú Àjọ NAFDAC

1. Gbígba àwọn òfin àti ìlànà tí ó tọ̀nà fún ìsọ̀rí ọjà oúnjẹ tí o fẹ́ forúkọ rẹ̀ sílẹ̀ láti orí ìtàkùn àgbáyé ti NAFDAC https://www.nafdac.gov.ng/our-services/micro-small-medium-enterprises-msme1, ní ọ́ọ́físì NAFDAC tàbí kí o fi orúkọ sílẹ̀ fún àyẹ̀wò àkọ́kọ́ (Oníwọ̀fún) kí o sì kàn sí napams.org láti fi àwọn ìwé ìforúkọ sílẹ̀ rẹ sọwọ́ síbẹ̀
2. Fífi àwọn ìwé ajẹmọ́-ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣọwọ́ àti àwọn ìwé mìíràn tí tọ́ sí ọ́ọ́físì NAFDAC ní ìpínlẹ̀ rẹ

3. Ṣètò àyẹwò ọjà àti yíyan ọjà fún ọjọ́ iwájú
4. Ìtúpalẹ̀ yàrá àyẹ̀wò ìmọ̀ sáyẹ́nsì
5. Ìforúkọsílẹ̀ àti gbígba àṣẹ ìtajà (Nọ́ńbà ìforúkọsílẹ̀ NAFDAC)

### Àwọn Ìwé Ìforúkọsílẹ̀

Àwọn ìwé ìsàlẹ̀ wọ̀nyí ni ó nílò fún ìforúkọsílẹ̀  lórí ìtàkùn àgbáyé:

- Lẹ́tà ìbèèrè fún àyẹ̀wò ọjà tí a kọ sórí ìwé ìkọlẹ́tà ilé-iṣẹ́
- Ìwé-ẹ̀rí CAC pẹ̀lú (TIN)
- Ìforúkọsílẹ̀ Àmì-ìṣòwò (Gbígbà àti ìdúpẹ́ ) – WỌ̀FÚN FÚN ÀWỌN OLÓSÙNWỌ̀N KÉKERÉ
- Àmì ọjà/ iṣẹ́ ọnà
- Àbọ̀ Àyẹ̀wò Agbá-oúnjẹ-mú fún àwọn òṣìṣẹ́ (àwọn gègé tí a ní láti yẹwò jẹ́: Sputum Test (àyẹ̀wò kẹ̀lẹ̀bẹ̀), Urine Test (àyẹ̀wò ìtọ̀), Stool Test (àyẹ̀wò ìtọ̀), Chest X-ray (àwòrán igbá-àyà), Widal Test (àyẹ̀wò ibà), Hepatitis A (àyẹ̀wò ẹ̀dọ̀)
- ìwé-ẹ̀rí ìṣèmọ́tótó ní lọ́ọ̀lọ́ọ̀ tí ó ń ṣe àfihàn àwọn ohun-èlò tí a lò.

### Àwọn Ìwé Mìíràn tí a fi ṣọwọ́ sí ọ́ọ́fìsì NAFDAC ìpínlẹ̀

- Àwọn ìgbésẹ̀ ìṣe tó bá ìpele dídára mu fún ìpèsè, ìṣàkóso dídára, ìmọ́tótó, dídásílẹ̀ àti pípè padà, àti ìlò dáradára irinṣẹ́
- Ìlànà ìpele ọjà fún ọjà kọ̀ọ̀kan.
- Ìpele ìṣàkóso ilé-iṣẹ́ náà pẹ̀lú orúkọ àti oyè-ìmọ̀ àwọn adarí tó ṣe pàtàkì
- Àwọn ìwé-ẹ̀rí àwọn òṣìṣẹ́ onímọ̀-ẹ̀rọ (alákòóso ìpèsè)
- Àtúpalẹ̀ àwọn ohun-èlò tútù/ògidì àti ọjà tí a ti ṣe tán (wọ̀fún)
- Èèkàrìkà àwọn àfikún sí oúnjẹ bí ó bá yẹ.

### ÀWỌN ÌLÀNÀ GBOGBOGBÒÒ

### A. ILÉ /IBÙDÓ

- Ilé tí wọ́n ń lò gbọ́dọ̀ wà ní ibùdó tó kún ojú ìwọ̀n, tí wọ́n kọ́ dáadáa tí ó tọ̀nà fún ìmọ́tótó, ìtọ́jú àti ìṣedéédéé àwọn òṣìṣẹ́ àti ohun èlò.
- Ilé náà gbọ́dọ̀ ní ààyè tó ti o peye fun tito lẹsẹsẹ ti awọn ohun elo ati awọn ohun elo lati ṣe idiwọ awọn idapọ laarin awọn ohun elo oriṣiriṣi. (ó kéré tán, yàrá kan àti yàrá-ìkó-ọjà-pamọ́ kan fún ilé-iṣẹ́ olósùnwọ̀n kékeré)
- Ààyè tí wọ́n ti ń ṣiṣẹ́ kò gbọ́dọ̀ ní ìbáṣepọ̀ tààrà pẹ̀lú ibi ẹ̀gbin bí i (ilé-ìgbọ̀nsẹ̀ àti ilé-ìwẹ̀).
- Ó yẹ kí wọ́n fi nẹ́ẹ̀tì sí gbogbo ojú ilẹ̀kùn àti fèrèsé
- Ó yẹ kí ó fi ààyè sílẹ̀ fún atẹ́gùn àti ìmọ́lẹ̀.
- Ilẹ̀ẹ́lẹ̀, ògiri àti àjà gbọ́dọ̀ dán, kí ó le lójú, èyí tí yóò jẹ́ kí ó lè ṣe é fọ̀ mọ́.
- Ààyè ibi iṣẹ́ gbọ́dọ̀ ní;
    1. Awọn ohun elo Iyẹwu / Igbọnsẹ
    2. Yàrá-ìkó àwọn ohun-èlò ògidì sí
    3. Yàrá-ìkó àwọn ohun-èlò ìṣelọ́jọ̀ sí
    4. Yàrá ìpèsè
    5. Yàrá-ìkó àwọn ọjà aṣetán sí

### B. ÈTÒ ÀTI ÒṢÌṢẸ́

- Ó yẹ́ kí iye àwọn òṣìṣẹ́ tó kún ojú ìwọ̀n tó láti ṣe iṣẹ́ tí ayàn fún wọn.
- Iye òṣìṣẹ́ kan sí mẹ́sàn-án ni fún ilé-iṣẹ́ olósùnwọ̀n péréte, nígbà tí òṣìṣẹ́ mẹ́wàá sí mọ́kàndíláàádọ́ta (10 to 49) wà fún àwọn ilé-iṣẹ́ kékeré

- Òṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan tí ó ń kópa nínú oúnjẹ síṣe gbọ́dọ̀ ní ẹ̀kọ́ ìpìlẹ̀ nínú ìpèsè oúnjẹ.
- Àwọn òṣìṣẹ́ gbọ́dọ̀ wọ aṣọ ìdábòbò, bí àpẹẹrẹ ìbòrí, ìbòjú, ìbọ̀wọ́, ìbo-apá láti dáàbò bo ọjà.
- Àwọn òṣìṣẹ́ gbọ́dọ̀ fi àwọn ìwà ìmọ́tótó tó dára kọ́ra.
- Gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ gbọ́dọ̀ ní ẹ̀tọ́ sí ìtọ́jú ìwòsàn àti àyẹ̀wò déédéé fún àwọn àrùn tó ń ràn, wọ́n sì gbọdọ̀ fi àwọn ìwé àyẹ̀wò náà pamọ́.
- Òkọ́ni tó péye gbọ́dọ̀ wà fún àwọn òṣìṣẹ́ nínú àwọn iṣẹ́ pàtó tí wọ́n ń ṣe

## C. IRINṢẸ́

Apẹrẹ, ohun elo, ikole, ipo ati itọju ohun elo yẹ ki o jẹ bii lati jẹ ki o pe deede ati pe o yẹ fun lilo ipinnu rẹ.

Awọn ẹya ti ẹrọ ti o ṣe ifọwọkan pẹlu awọn ọja onjẹ yẹ ki o jẹ ti awọn ohun elo ti kii ṣe majele / aiṣe-ifaseyin gẹgẹbi irin alagbara, irin alagbara.

Ifilelẹ rẹ ati apẹrẹ rẹ gbọdọ ni ifọkansi lati dinku eewu ti awọn idapọpọ ati gba isọdọtun to munadoko ati itọju lati le yago fun idoti agbelebu, ikole ti eruku, eruku, patiku onjẹ tabi eyikeyi idoti miiran ti o le ni ipa lori didara ọja naa.

## D. ÌPÈSÈ OMI

Omi tí à ń lò fún ìpèsè tàbí ṣíṣe oúnjẹ yòówù àti fún fífọ àwọn irinṣẹ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ omi tó mọ́ gaara.

Àwọn ohun-èlò ìtọ́jú ọmi àti fún sísẹ́ omi gbọ́dọ̀ wà nílẹ̀.

## E. Ìlànà Ìṣàmìsí

Àwọn ìlànà ìṣàmìsí yàtọ̀ láti ọjà sí ọjà, ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí ìtọ́ni gbogbogbòò, àwọn àlày;e wọ̀nyí máa ń nílò nínú àmì.

- Orúkọ ọjà oúnjẹ náà
- Iye ìwọ̀n rẹ̀ (ní gíráámù)/fọ́lúùmù(yálà ní ml, cl tàbí ní jálá)
- Àtọ́ka àwọn èròjà
- Nọ́ńbà ìlẹ̀mọ́
- Déètì Ìpèsè
- Déétì tí ọjà dára di
- Ìtọ́ni fún lílò
- Àlàyé ohun ìṣaralóore  (níbi tí a tí ń sọ tẹ́lẹ̀)
- Àlàyé nípa àìbáraré (níbi tí ó ti wúlò)
- Àwọn ipò ìkópamọ́
- Orúkọ àti àdírẹ́sì olùpèsè
- Ipò ìpèsè
- Ìpèsè Nọ́ńbà ìforúkọsílẹ̀ NAFDAC
- Ìtọ́ni fún ìjùdànù

### Àǹfààní ìṣàmì sí oúnjẹ

- Ó ń ran àwọn oníbàárà lọ́wọ́ láti yan ohun lọ́nà tó dára.
- Ó jẹ́ orisun àwọn àlàyé ìsaralóore
- Láti jẹ́rìí sí ẹ̀tọ́ kan lórí àmì náà
- Láti ṣe àfiwé oríṣirísi ọjà onírú kan náà
- Láti ṣe àyẹ̀wò bóyá a ti ṣe àfikún tàbí àyọkúrò àwọn èròjà ìṣaralóore sí ọjà náà
- Ó máa ń dá àwọn oníbàárá lẹ́kọ̀ọ́ nípa oúnjẹ tí wọ́n rà

### Ìgbésẹ̀ Ìṣe Onípele tó dára (SOP)

- Ó jẹ́ ìwé tí ó ń ṣe àpéjúwe bí wọ́n ṣe ń ṣe àwọn iṣẹ́ àti ìṣe.
- Ó máa ń rí i dájú pé wọ́n ṣe iṣẹ́ lọ́nà tó tọ́ ní gbogbo ìgbà ní ọ̀nà kan náà. Ó ní apá méjì (àkọlé àti àkóónú). Ó lè wà ní ìlànà àwòrán.

1. **Àkọlé:** A ó ṣe àwítúnwí èyí lórí gbogbo ojú-ìwé. Ó kún fún: àkọlé, Àwọn ẹ̀ka àkóso, Nọ́ńbà ìtọ́kasí ìwé náà, Déétì ìṣe, Déètì fún àtúnyẹ̀wò, Ìfi-òǹtẹ̀-lù (láti ọwọ́/Tí a fi òǹtẹ̀ lù láti ọwọ́) àti òǹkà ojú-ìwé
2. **Àkóónú SOP:** àkóónú SOP máa ń ní àwọn ẹ̀ka wọ̀nyí:
   - **Èrèdí:** èyí ni ìdí fún SOP náà.
   - **Ọwọ́jà**: tọ́ka sí gbígbòòrò.
   - **Ojúṣe:** mẹ́nuba ẹni tí ó ni ojúṣe iṣẹ́ tàbí àbójútó àti ìṣàkóso (ní àkọlé).
   - **Ìgbésẹ̀:** tọ́ka sí ìpele kọ̀ọ̀kan nínú ìgbésẹ̀ náà àti ṣíṣe àpéjúwe lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ lórí bí àwọn ìgbésẹ̀ náà ṣe wá sí ìmúṣẹ.
   - **Yí ìtàn àti èrèdí padà:** tọ́ka sí ìdí pàtó fún ṣíṣe àfikún sí SOP tó ti wà tẹ́lẹ̀.
   - **Àkọsílẹ̀ ìpín-ọjà-ká:** akọsílẹ̀ àwọn ènìyàn pẹ̀lú ẹ̀dà SOP.
   - **Àwọn ìlànà ìkọ́ni:** tọ́ka sí àwọn ìkọ́ni tí a dábàá fún àwọn òṣìṣẹ́ ní àwọn agbọn tí ó tọ́.
   - **Àkọsílẹ̀ ìkọ́ni:** àkọsílẹ̀ àwọn òṣìṣẹ́ tí a kọ́ àti ìkọ́ni tí a nílò.

### DÍẸ̀ LÁRA ÀWỌN ÌWÉ/ÀKỌSÍLẸ̀ TÍ A GBỌ́DỌ̀ PAMỌ́ NÍLÉ-IṢẸ́ OÚNJẸ

- Àwọn ìgbésẹ̀ ìṣe onípelé dídára (SOPs)
- Akọsílẹ̀ àwọn òṣìṣẹ́
- Àkọsílẹ̀ ìṣàkóso ohun-èlò ògidì/ìṣelọ́jọ̀
- Àkọsílẹ̀ irinṣẹ́ àti ìtọ́jú
- Àkọsílẹ̀ ìṣèmọ́tótó àwọn irinsẹ́ àti ilé-iṣẹ́
- Ìṣàkọ́so ìpèsè àti ìgbésẹ̀
- Àwọn àkọsílẹ̀ ìṣàkóso ìṣedáadáa
- Àwọn àkọsílẹ̀ ìpínká
- Yíyọ̀nda àti pípè-padà
- Ìwíjọ́
- Àwọn àkọsílẹ̀ ilé-ìkó-ọjà-pamọ́ sí, níbi tí ó bá ti nílò.
- Àwọn àkọsílẹ̀ ìṣàkóso ewu

### Ìkádìí

1. Gẹ́gẹ́ bí NAFDAC ṣe tẹ̀síwájú láti máa mú àwọn ìgbésẹ̀ ìṣàkóso wọ gbèrú sí, láti jẹ́ kí wọ́n dáhùn sí àwọn ohun ọ̀tun kí wọ́n sí bá ìṣe àgbáyé rẹ́, mo gbà yín níyànjú láti gbà fún àwọn ìlàkalẹ̀ ìṣàkóso nípasẹ̀ fífi orúkọ àwọn ọjà wọn sílẹ̀ àti nípasẹ̀ ṣíṣètò àwọn ìpele tó dára látàrí àti rí dájú pé o pèsè àwọn oúnjẹ tó dára fún àwùjọ, bí ìwọ náà ti ń mú ètò ìsúná rẹ gbèrú sí i.
2. Ọ́ọ́fíìsì àti àwọn òṣìṣẹ́ NAFDAC máa ń wà ní àrọ́wọ́tó àwọn ènìyàn fún ìbéèrè àti ìwíjọ́.
3. NAFDAC Kò gba lílo àwọn alàgàta níyànjú. Àwọn tó ń lò wọ́n ń ṣe bẹ́ẹ̀ sí ìparun ara wọn.
4. Àwọn ọ́ọ́fíìsì NAFDAC wà ní ìpínlẹ̀ mẹ́rìndínlógójì orílẹ̀-èdè yìí àti olú-ìlú Nàìjíríà lÁbùújá pàápàá.
5. Ojú-òpó ìtànkùn àgbáyé (Website): www.nafdac.gov.ng Email: nafdac@nafdac.gov.ng
6. Ojú-òpó ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀: Fún ìbéèrè: 0700-1-623322 Fún ìwíjọ́: 0800-1-623322

# Ẹ̀KỌ́ KARÙN-ÚN

# Àwọn Ìpèle Dídára Oúnjẹ



## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ ìlànà. Àwọn olùkọ́ le ṣe àtúnṣe sí agbọn tó bá wù wọ́n láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Ó yẹ kí wọ́n bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

### Èròǹgbà nípàtó:

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, Àwọn akópa gbọ́dọ̀ le;

- Sàfàjáde àwọn àǹfààní ìpéwọ̀n
- Sọ ìlànà ìforúkọ okòòwò sílẹ̀ àti bíbuwọ́lù pẹ̀lú SON
- Mọàwọn ìwúrí tí ó wà fún MSME's èyí a pèsè láti ọwọ́ SON

| Àkóónú | Discussion questions | Review question |
|---|---|---|
| • Kí ni ìpéwọ̀n<br>• Àwọn aǹfààní ìpéwọ̀n<br>• Àwọn ìwúrí tí ó wà fún MSME's<br>• Ìjẹ́rììsí ìpéwọ̀n àti ìgbéjáde<br>• Awọn n tí a nílò fún ijẹ́rììsí<br>• Àbùdá ìlànà ìpéwọ̀n tàbí ìsọwọ́ sàgbékalẹ̀rẹ̀<br>• Àwọn ìpéwọ̀n tí ó ní ṣe pẹ̀lú ìlànà bí a ṣe ń fi ẹ̀gẹ́ dárà<br>• Ìpéwọ̀n tí ó ní ṣe pẹ̀lú ẹja àti ohun tí à ń fi ẹja ṣe<br>• Àwọn ìdí fún ìkọ̀sílẹ̀ ohun ọ̀gbìn | 1. Ǹjẹ́ ó gbọ́ nípa SON? I Tí ó bájẹ́ bẹ́ẹ̀ ni, kí ni wọ́n ń ṣe?<br><br>2. Has Ǹjẹ́ àgbéjáde rẹ tí dí ohun ìkọ̀tì tẹ́lẹ̀rí ní ọjà? Kí ni ìdí rẹ̀? | 1. Kí ni àwọn ìgbésẹ̀ tí àgbéjádé rẹ̀ yóò fi di fífọwọ́sí láti ọ̀dọ̀ SON?<br>2. Àǹfààní wo ní ó wà nínú kí SON fọwọ́sí?<br>3. Dárúkọ díẹ̀ lára n tí o nílo láti gbé àwọn ọjà rẹ lọ sí òkèrè.<br>4. Kí ni àwọn ìdí tí ìkọ̀tì fi dé bá erè-oko ní ọjà àgbáyé?<br>5. irú ẹ̀kọ́ wo ni o ti kọ́? |

| Training method | Activity | Materials |
|---|---|---|
| 1. Ìgbéjáde<br>2. Fídíò onífọ́nrán kékeré<br>3. Ìṣehanni<br>4. Isẹ́ àdìjọṣe<br>5. Ìfere kọ́ni (uló ó kéré tán ọ̀nà méta nínú sàgbékalẹ̀. Mú ọ̀kan nínú àwọn ọ̀nà yìí ní ibi tí ó bá ti yẹ) | 1. Eré ṣíṣe nípa bí àwọn oníbàárà ṣe máa ń kọ ohun tí a gbé jáde látara ohun-ọ̀gbìn sílẹ̀ lọ́jà àti ìdí fún ìkọ̀sílẹ̀ wọn. | • Ẹ̀rọ àgbáwòránỵọ<br>• Ẹ̀rọ ayàrabíàsá-alágbéléṣẹ̀<br>• Ẹ̀rọ afidànǹdán-hàn<br>• Àtẹ agbáwòrán-tàn<br>• Ẹ̀rọ amóhùnbúgbẹ̀mù |



## KÍ NI ÌPÉWỌ̀N?

**Ìpéwọ̀n** jẹ́ ìwé àdéhùn ìsọ̀kan tí ó ní àbùdá,ìbéèrè fún(ìnílò),ìsàpèjúwe-kíkún tàbí ìlànà tí a lè lò láti ìgbàdégbà láti ri dájú pé àwọn àgbéjáde,èlò,iṣẹ́, pẹ̀lú ìlànà wà ní ipò tí  a fẹ́.

- Ìpéwọ̀n ilé-iṣẹ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà jẹ́ àdéhùn èyí tí ìfẹnukò ìgbìmọ̀ gbékalẹ̀ tí ẹgbẹ́ ìpéwọ̀n orílẹ̀-èdè nàìjírà buwọ́(Standards Organization Of Nigeria) (SON).
- Ìpéwọ̀n ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn àgbẹ̀  àti olùsètò oúnjẹ́/olùpèsè láti lè ṣe ọjà tí ó wà ní pípé-pérépé nípa àìléwu àti dídára.
- Àwọn, nítorí náà,sèrànwọ́ láti ri dájú pé ọjà àti iṣẹ́  ń ṣe ohun tí ó yẹ ní ṣíṣe tí wọ́n sí sé é fiwé ara wọn pẹ̀lú níní ìbáramu.

### ÀǸFÀÀNÍ ÌPÉWỌ̀N

### Ìpéwọ̀n rí dájú:

- Itẹ́lọ́rùn oníbàárà
- ìbámu pẹ̀lú àwọn ìbéèrè ìlànà àti àwọn àyípadà ìlọsíwájú
- Níní àǹfààní sí ìfigagbága lábẹ́lé àti lágbàyé
- Gbígbòòrò okòòwò Ìmúdúró àti ìdàgbàsókè okòòwò)
- Ìsètò àgbékalẹ̀ okòòwò,ìfilọ́lẹ̀,àmójútó,ìkádìí àti àyípadà ìtẹ̀síwàju
- Ṣàgbéga  àwọn ìmọ̀ tuntun tuntun (ṣíṣe afihàn tí ó gúnrégé àti ṣiṣe àkóso àgbéjáde tuntun wọ ọjà orílẹ̀ èdè)
- Dín àsìkò kù,dídín ìfisòfò kù àti ìnáwó(ìmúgbòòrò àgbéjáde)

### Àwọn ìwúrí tí ó wà fún Msmes

- Jíjáwálẹ̀ owó ìgbéwọ̀n sí MSMEs ní 25% (50% ní ilé-iṣẹ́ MSMEs káàkiri àgbáyé)
- Ìjáwálẹ̀ owó ìwé-ẹ̀ri sí 50%
- Ìjáwálẹ̀ owó àyẹ̀wò ní iyàará àyẹ̀wò sí 50%
- SONCAP import fààyè gba owóosẹ̀ tí kò gunpá lórí ìpèèlò àti irin-iṣẹ́(ohun èlò) tí wọ́n bá gbé wọlé.
- Àfikún ní gbogbo àwọn ìgbìmọ ìmọ̀-ẹ̀rọ lórí àwọn ìmúgbòòrò ìpéwọ̀n.
- Àbá gbogbo MSMEs pẹ̀lú àwọn èròjà tí a ti ìfọwọsí fún ìsúná.

## ÒSÙWỌ̀N ÀTI BÍBUWỌ́ LU ÈRÒJÀ

- Ìbọwọ́ lu èròjà jẹ́ ètò láti ri dájú pé àwọn ohuntí aṣe jáde lábẹ́lé ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà mú ìtẹ́kọ́rùn tí ó tó wá fún àwọn oníbààrà ní ìbámu pẹ̀lú òfin ìjọba lórí ìdíwọ̀n àyẹ̀wò ìbámu.
- Ìdí ni láti sàgbéga ìfigagbága àgbáyé láàrin àwọn olùpèsè ilé-isẹ abélé àti láti ṣe ìwúrí fún àyípadà ìtẹ̀síwájú lórí dídára àwọn ohun-èlò ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ àṣẹ ẹwẹ ìpéwọ̀n tí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà(Standards Organisation of Nigeria).
- Èròǹgbà gbogbo gbò ni láti mú ìtẹ̀sìwájú bá ilé-isẹ́ àti ètò ọrọ̀-ajé nípa ríri dájú pé àwọn ohun tí à ń gbé jáde ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí ilé-iṣẹ́ tó jíire nílò pẹ̀lú àyípadà ìtẹ̀síwájú lórí dídára ohun tí a ṣe jáde nipa níní ìfọwọ́sowọ́pò mú yányán pẹ̀lú àwọn tí ọ̀rọ̀ kan láti lè ní ìbáṣepọ̀ tó gúnrégé àti àwọn àǹfààní aláìlẹ́gbẹ́.

## ÈTÒ ÀYẸ̀WÒ ONÍBAMU DANDAN (MANCAP)

Ètò àyẹ̀wò oníbámu dandan(MANCAP) jẹ́ ètò ajẹ́rìísi ohun àgbéjáde dandan láti ọwọ́ ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà láti ri dájú pé àwọn ohun tí a ṣe jáde lábẹ́lé ní orílẹ̀-èdè ní ìbámu pẹ̀lú ìgbéwọ̀n ilé-iṣẹ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà(Nigerian Industrial Standards (NIS)) kí ó tó di pé ohun tí a ṣe jáde náà yóò di gbígbé jáde fún títà ni ọjà tàbí gbé lọ sí ibòmíràn.

## ÌLÀNÀ FÚN GBÍGBA ÌWÉ ẸRÍ

- Ríra fọ́ọ̀mù ìforúkọsílẹ̀ ìpéwọ̀n àti MANCAP tí ó wà ní ìbámu ní ilé-iṣẹ́ SON tí ìpínlẹ̀ tí ó bá sún mọ agbègbèrẹ̀.
- Ìsàyẹ̀wò ìlànà bí a ṣe ń sàgbéjáde.
- Títọ́wò àti yíyẹ̀wò àwọn ohun tí a ṣe jáde gẹ́gẹ́ bí ìbámu rẹ̀ pẹ̀lú ilé-iṣẹ ìpéwọ̀n tí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà (Nigerian Industrial Standards (NIS)).
- Ìjábọ̀ àyẹ̀wò àti àwọn àbájáde ìdánwò jẹ́ ti ọfíìsì ìpínlẹ̀  pẹ̀lú mímú lọ sí ọ̀dọ̀ alásẹ́ ìbuwọ́lù fún ìkádìí àti  ìfọwọ́sọ̀yà.
- Tí ọjà náà bá se é faramọ́, iwé-ẹ̀rí MANCAP pẹ̀lú àmì ìdánimọ̀(logo) ń fi nọ́mbà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ sí ọjà kọ̀ọ̀kan,nípa sísan owó tí ó yẹ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn àlásẹ .
- Ìwé-ẹ̀rí MANCAP wúlò fún ọdún méta lẹ́yìn tí ohun-àgbéjáde náà yóò tún ṣe ìgbésẹ̀ ìlànà àti ní ìwé ẹ̀rí mìíràn.
- MANCAP lógò gbọ́dọ̀ wà ní lórí àpò kékeré àlẹ̀mọ́  kí ó tó sísàfihàn lọ́jà.
- Àjọ SON ní ó ń sàmójútó ọjà nípa ṣíṣe àbẹ̀wò ẹ̀kọ̀ọ̀kan sí àwọn sí ilé-isẹ àti àyẹ̀wò  láti ní ìfọwọ́sọ̀yà ìbámu àtìgbàdégbà pẹlu àwọn ìkójú-òsùwọ̀n ilé-isẹ orílẹ̀èdè Nàìjíríà

## OHUN TÍ O NÍLÒ FÚN  (ÌGBÉWỌ̀N)  ÌJẸ́RÌÍSÍ /ÌGBÉKỌJÁ

- Ṣíṣegbọràn sí ìgbéwọ̀n tí ó tọ́: Gbogbo ohun-èlò tàbí tí a ṣe jáde láti fún gbígbé lọ sí ibòmíràn gbọ́dọ̀ yege pẹ̀lú ìlànà ìgbéwọ̀n tí ó tọ́.  ìdánilójú dídára àti àìléwu ohun-èlo pẹ̀lú pípèsè àǹfààní aláìlẹ́gbẹ́ àti kí ó mú àǹfààní àti wọ àwọn ọjà tí a ti ń kó nǹkan wọle.
- **Ìkójọ/Làlàyé-ìsàmísí:** Ìsàmìsí àkójọ gbọ́dọ̀ sàmúlò àwọn àmúyẹ rẹ̀. Àwọn ohun-èlò tí ó tọ́ tí a kó jọ gbọ́dọ́ di lílọ́,pẹ̀lú pípèsè àlàyé tí ó kún kẹ́kẹ́ nípa ìsàmísi.Àlàyé ìsàmísí gbọ́dọ̀ yéni yékéyéké,kò gbọdọ̀ jẹ́ ẹ̀tàn bákan náà ni abẹ́rẹ́ rẹ̀ gbọ̀dọ̀ lókùn nídìí.
- **Ohun ìrìnsẹ̀ irọ̀rùn  àti àwọn ipò ìkóǹkanpamọ́sí/Ilé-ìkẹ́rùsí:** Ro ewu ńlá tí ó le fà nípa títọ́jú àwọn àmúpèèlò àti àwọn n tí a gbéjáde / ṣe jáde. Gbogbo àwọn iṣẹ́ yìí gbọdọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú ìgbéwọ̀n tí ó tọ́. Àwọn ohun-èlò ìrìnsè ,ipò,àkókò. Gbọ́dọ̀ yàgò fún ìdiwọ̀n ìgbéléra. Ibi ìkẹ́rù sí tí ó yẹ gbọ́dọ̀ di pípèsè gẹ́gẹ́ bí a ṣe ba àkàìmọye ohun-èlò jẹ nítorí pé wọn bàjẹ́. Where required Nibi ti nílò, appropriate fumigation Ìfògùnpakòkòrò tí ó tọ̀nà gbọ́dọ̀ wáyé ní ibi tí à ń kó nǹkan

pamọ́ sí pẹ̀lú àwọn ohun- ìpakòkòrò tí ó yẹ ni ààyè tí ó lásẹ láti ṣe bẹ́ẹ̀.

- **Àyẹ̀wò:** Ohun ti ọjà àgbáyé bá fẹ́ ní yóò sọ irú yàárá-àyẹ̀wò tí èsì àyẹ̀wò yóò ti wá tàbí ibi tí ó dáńtọ́ láti ṣe àyẹ̀wò. Esì àyẹ̀wò gbọ́dọ̀ wá láti yàárá àyẹ̀wò tí a fún lásẹ (ISO 17025) ní a ó gbà wọlé si orílẹ̀-èdè EU.Ìdí nìyí tí àwọn àgbà fi máa ń sọ pé "àyẹ̀wò ẹ̀ẹkan ìgbàwọlé níbikíbi"
- **Ìsàfọ̀mọ́ ohun-èlò:** DemonstrateṢàfihàn sí àwọn oníbààrà tàbí àwọn àlásẹ pé ìsọwọ́ ṣiṣẹ́ àti ọjà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn àmuyẹ fún ìjẹ́rìísi si àmì-ìfọwọ́sọ̀yà ojúlówó pé ohun-èlò tí a sọ yìí ti ni àwọn àmúyẹ tí ó ṣe pàtàkì.Ìdámọ̀ káàkiri àwọn àmì ìjẹ́rìísí wa
- **Ìbuwọ́lù tí ó ṣe pàtàkì láti ọ̀dọ̀ àwọn àláṣẹ tí ó tọ̀nà /alámòjútó-ẹ̀ka:** Gba ìwé-ẹ̀rí tí ó yẹ láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹ̀ka tí ó yẹ kí ó tó gbé ohun-elo tàbi ọjà náà kọjá sí ibòmíràn. Máse dọ́gbọ́n yẹra fún àwọn ìgbésẹ̀ tàbí ìlànà tí ó yẹ láti gbé tí yóò sì wúlò ní ọ̀nà mìíràn

### Àbùdà oúnjẹ tí ó péwọ̀n

Oúnjẹ tí o péwọ̀n yóò sàfihan:

- Àpèjúwe tí ó kún tí ó sì tọ̀nà nípa oúnjẹ
- Àwọn ìlànà àti àwọn ètò tí ó rọ̀mọ́ ohun-èlò ná
- Ìpèèlò (èròjà pàtàkì àti èyí tí kò pàtàkì)
- Àwọn èròjà oúnjẹ tí a gbà láàyè àti ìpele ìgbàláàyè wọn
- ojúlówó àmúyẹ fún ohun-èlò èyí tí o kó kẹ́míkà-àfojúrí,ìdiwọ̀n àwọn kòkòrò-àìfojúrí; nǹkan olóró àbàwọ́n àti àwọn ìdiwọ̀n òògùn apakòkòrò abbl.
- Ìmọ̀tótó
- Ṣísàmì àti àmúyẹ ìsàmísí
- Àwọn àmúyẹ fún kíkópamọ́
- Àmúyẹ ìtọ́júpamọ́
- Àmúyẹ fún ìtọ́wò

### Àbùdá ìlànà ìpéwọ̀n /Ìlànà bí a ṣe ń se

Ìlànà bí a ṣe ń se sàpéjúwe àmúyẹ fún àwọn tí kò bẹ́gbẹ́ mu láàrin àwọn yòókù:

- Àwọn ohun-èlò isẹ́ àgbẹ̀ bí e.g. amúlẹ̀lọ́ràá,òògùn-apakòkòrò, asàmójútó bí ewéko ṣe ń dàgbà.
- Àmójútó lákòókò ígbéjáde,ìkórè,ìkópamọ́
- Ìlànà ìpele àti àwọn ìgbésẹ̀
- Àwọn èèlò-ìgbésẹ̀ àtí àtúnrọ
- Ìkójọsójúkan
- Ètò lílọ-bíbọ̀ (níbi tí ó bá tí nílò)

### Díẹ̀ lára àwọn ìpéwọ̀n tó ní ṣe pẹ̀lú ohun tí à ń fi pákí(Cassava) ṣe ní:

- ìpéwọ̀n fún ẹ̀ta Pákí NIS 459:2004
- ìpéwọ̀n fún èlùbọ́ ojúlówó tí ó ga jù lọ (HQCF) NIS 795:2004
- ìpéwọ̀n fún èlùbọ́ NIS 344:2020
- Ẹ̀gé tí a lè rí nínú ounjẹ – Ìnílò NIS ARS 846:2020
- ìpéwọ̀n fún Garri NIS 181: 2004
- ìpéwọ̀n fún ipanu tí a fi pákí ṣe(Cassava Chips) NIS 343:2004
- ìpéwọ̀n fún ẹ̀gẹ́ ilé-iṣẹ́ NIS 386:2020
- Code of Ọgbọ́n Ìlànà bí a ṣe ń pákí àti awọn n tí à ń fi pákí ṣe NCP 048:2020

- ìpéwọ̀n fún awọn ẹ̀ta pákí NIS 459:2004
- ìpéwọ̀n fún wîtì tí a fi ń ṣe búrẹ́dì NIS 807:2015

### Ìpéwọ̀n tí ó ní ṣe pẹ̀lú ẹja àti àwọn odò ẹja

- Ìlànà ìsọwọ́sisẹ́ ẹja àti ohun-ó jẹmọ́ odò ẹja NCP 24:2004
- ìpéwọ̀n fún Ìtutù kíakía gẹgẹ́ bí oku àwọn ẹja tí kò léègun NIS 597:2008
- ìpéwọ̀n fún gígan odidi ẹja Fish NIS 598:2008
- Ìlànà ìmọ́tótó fún ẹja yíyan
- ìpéwọ̀n fún  gígan kíákía fún edé pupa àti edé funfun
- ìpéwọ̀n fún ẹja inú-agolo NIS 279:1990
- ìpéwọ̀n fún gígan odidi ẹja NIS 596:2008

### Àwọn ìdí fún ìkọ̀sílẹ̀ àwọn erè oko

- Àwọn erè oko tí kò dára tó
- Áwọn àbàwọ́n tí ó ga jù lọ
- Lilòjù àwọn òògùn apakòkòrò
- ìsàmìsí àti ìkósójúkan  lọ́nà tí kò tọ̀nà
- Èrè oko tí kò ní àwọn ìjẹ́rìísí tàbí ìbuwọ́lù tí ó yẹ.

Gbogbo àwọn wọ̀nyí ni ó lè di títẹ́tí sí nípa gbígbọ́ràn sí àwọn àmúyẹ àwọn ìgbéwọ̀n tí ó yẹ

### ÌKÁDÌÍ

- The consciousnessÌwòyesí àwọn àgbẹ̀,olùsàgbéjáde-oúnjẹ,àwọn ará-ìlú nipá àwọn ìkúnwọ̀n àti ìyanjúìsòro wa láti lè ní  o ìbámu pẹ̀lú àmúyẹ ìkójú-òsùwọ̀n fún àgbéjáde wa láti lè:
- Ìlọsíwájú ìgbòkègbodò MSMEs lórí ilé-iṣẹ́
- Ran Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lọ́wọ́ láti túbọ̀ tẹ̀síwájú nínú níni ìgboyà nínú ọjà,kó ipa tí ó ní ìtumọ̀ ní ọjà-àgbáye kí ó sì mú ìgbé -ayé ìrọ̀rùn wá fún olùgbé Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láti túbọ̀ mú ayé gbẹdẹkẹ si.

# ẸKỌ KẸFÀ

# ÀWỌN ÌTAJÀ ELÉTÒ ÀTI TÍTAJÀ FÚN MSMES



## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ ìlànà. Àwọn olùkọ́ le  ṣe àtúnṣe sí agbọn tó bá wù wọ́n láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Ó yẹ kí wọ́n bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

### Àwọn Èròǹgbà ní pàtó:

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn olùkópa yóò lè;

- Sààmì àwọn ìlànà ìtajà tó wúlò àti bí a ṣe le lò wọ́n nínú ilé-iṣẹ́ wọn.
- Wá nípa ẹni tí olùbárà rẹ jẹ́.
- Ohun tí wọ́n nípò àti ohun tí wọ́n fẹ́.
- Bí o ṣe lè tẹ́ wọn lọ́rùn àìní wọn.
- Bí o ṣe le rí èrè lórí ìdúnàdúrà kan.
- Bí o ṣe le ṣe ìtọ́jú ìbátan èrè.
- Sààmì àwọn ìwúlò pàtàkì fún títa gbàgúdá ati ọjà ẹja.
- Ṣe ìdánímọ̀ àwọn ọnà títà àti àwọn àṣàyàn láti le ṣe àlékún ìlọsókè nínú òwò wíwọlé.

### Àkóónú

- Títajà, àwọn ẹ̀wọ́n iye àti ààbò oúnjẹ
- Àwọn ìfọkànsí títajá
- Àwọn irinṣẹ́ ọjà títà
- Báwo ni o ṣe ta ọjà àti fún taa ni?
- Títa ọjà ẹja ati gbàgúdá, àwọn ohun tó péye.
- Ẹja tí a ṣàkóso àti ọjà gbàgúdá
- Àwọn ìdojúkọ títa ọjà ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà
- Àwọn ìlànà fún títa ọjà ẹja àti gbàgúdá
- Àṣà tuntun fún ẹja títà
- Ọjà ẹja/gbàgúdá (Ìbílẹ̀)
- Àwọn ànfààní ọjà òkèèrè
- Ìkádìí



## KÍNNI ỌJÀ TÍTÀ?

Ó kan gbogbo àwọn iṣẹ́ tí ilé-iṣẹ́ gbà láti ṣe ìgbéga ìfẹ́ sí àti títa ọjà tàbí àwọn ẹrù. It involves all activities a company takes to promote the buying or selling of a product service or good. Ní àkókò yìí, àfikún iyì máa ń bá ọjà tó ní iye tẹ́lẹ̀. Èròngbà láti gbé iṣẹ́ náà ga àti láti sopọ̀ pẹ̀lú àwọn oníbàárà tuntun. Nítorí náà, ọjà títà máa ń fún ni ní anfàànì sí oúnjẹ tó dára ní ìpele gíga, ilé oníkálukú àti ní ìpele bí ènìyàn ṣe mọ fún ìgbé ayé àlàáfíà ní owó tí kò ga ju ara lọ

**Marketing is everything you do to find out:**

- Ẹni tí olùbárà rẹ jẹ́,
- Bí o ṣe le jèrè ìbárà wọn
- Ọ̀nà tí o le gbà láti ríi dájú pé wọ́n ń ra ọjà lọ́wọ́ rẹ lemọ́lemọ́ pẹ̀lú wíwo ti níní èrè.

**Èròngbà ọjà títà**

- Láti ṣe ìpolongo.
- Láti ṣẹ̀dá iṣẹ́.
- Láti bá àìní àti láti dé ọ̀dọ̀ àwọn àṣàyàn olùgbọ́

**Ìlànà títà ọjà?**

- Àwọn olùbárà nílò ìdánimọ̀
- Pípèsè ohun tí wọ́n nípọ̀.
- Gbígbé iye lé ọjà tí wọ́n ń fẹ́ àti èyí tí wọ́n yóò le san.
- Jíjẹ́ kí ọjà kàn wọ́n lára
- Fífi tóni létí àti fífa ojú wọ́n mọ́nra láti ra ọjà.



**Irinṣẹ́ ọjà títà**

**Fún òntàjà**

- **Ọjà:** Èyí ni aṣojú rẹ, o sọ ohun tí o ní láti pèsè
- **Iye:** Iye ọjà rẹ kò gbọdọ̀ pọ̀jù fún ìfanimọ́ra, bẹ́ẹ̀ kò gbọdọ̀ kéré jù kí èrè le yọ dáradára. Agbègbè

ni yóò sọ iye. Iye gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí yóò kó gbogbo àpapọ̀ owó iṣẹ́ àti ìdá èrè. Bí owó ọjà bá ṣe pọ̀ sí, bẹ́ẹ̀ ní bíbéèrè rẹ̀ yóò ṣe kéré. Fojúsí bí àwọn èèyàn ṣe yọjú sí.

- **Ìgbéga:** Ohun tí o ṣe láti fa olùbárà mọ́ra díẹ̀ sí. Fífitó àwọn olùbárà tó múná dóko létí nípa ilé-iṣẹ́ àti àwọn ọjà rẹ̀. Sísa ipá láti jẹ́ kí wọ́n ra ohun tí ò ń tà. Ìpolówó, ọ̀nà, ìbáṣepọ̀ láwùjọ. Lo àwọn ìfihàn pàtàkì láti ta àwọn ọjà ìgbàdégbà, ọjà ọdọọdún tàbí ọjà tuntun àti àwọn ọjà tó ti ń pẹ́ lórí igbá jù. Àfihàn pàtàkì rẹ̀ gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí o rọrùn fún àwọn ènìyàn láti rí. Ṣe àwòrán láti sọ fún àwọn olùbárà nípa àwọn pàtàkì ìfilọ̀. Gbé àwòrán náà sí ẹ̀gbẹ́ ìfihàn. Ìmọràn mìíràn tó dára ni láti gbé àwòrán sí iwájú ilé-ìtàjà láti jẹ́ kí àwọn ènìyàn tó nífẹ̀ẹ́sìí wọlé wá. Àwòrán tó bá dára yóò jẹ́ kí ọjà yá.
- **Ibi ìtajà:** Èyí túmọ̀ sí ìráyè sí àwọn olùbárà nípasẹ̀ àwọn ìkànnì pínpín. Mọ àwọn tó jẹ́ olùbárà rẹ. Ibi ìtajà yóò ya àwòrán sí ọkàn àwọn olùbárà. Ṣe òwò lórí ẹ̀rọ ayélujára. Jẹ́ kí ó rọrùn fún olùpèsè láti pín ọjà wọn nípasẹ̀ rẹ. Ronú nípa ìsúnmọ́ sí ọjà àti orísun àwọn ohun èlò iṣẹ́. Pinnu àwọn ìkànnì pínpín yálà tààrà/àtọwọ́dọ́wọ́
- **Àwọn Ènìyàn**: Ọjà ìfojúsùn, àwọn òǹtajà tó ti ṣe àṣeyọrí máa ń gbìyànjú láti wo àwọn ohun nípasẹ̀ oníbàárà wọn. Fi ara rẹ sí ipò oníbàárà. Ṣe àwọn oníbàárà rẹ bí o ṣe fẹ́ jẹ́ kí wọ́n ṣe ìwọ náà tí o bá jẹ́ oníbàárà. Kí àwọn oníbàárà rẹ. Pè wọ́n ní orúkọ wọn. Tí o bá ń dá oníbàárà kan lọ́wọ́ lóhùn, kí àwọn oníbàárà mìíràn tó bá wọlé kí o sì sọ fún wọn pé ò ń wá yọjú sí wọn láìpẹ́. Ní ìwà pẹ̀lẹ́ àti ìwà ọ̀yàyà kí ọkàn àwọn oníbàárà le balẹ̀ àti láti lè máa yọjú ní ìgbà mìíràn. Ẹ̀rín àti ìwà ọ̀yàyà kò jẹ́ nǹkankan. Wọ aṣọ tó dára- múra dáadáa kí o sì tún wà ní ìmọ́tótó. Pèsè ìrànlọ́wọ́. Tẹ́tísílẹ̀ dáradára láti mọ ohun tí wọ́n fẹ́. Jẹ́ onísùúrù. Fún àwọn oníbàárà ní ààyè láti bèrè ìbéèrè àti láti pinnu lórí ohun tí wọ́n fẹ́ rà. Jẹ́ olóòótọ́ àti onígbẹ̀kẹ̀lé. Fi tó àwọn oníbàárà rẹ létí lórí ohun tí ó dára àti àwọn ohun tí kò dára nípa ọjà tàbí iṣẹ́ kan. Má ṣe kọ etí dídi sí àwọn oníbàárà rẹ tí wọ́n bá pinnu láti má ra ọjà kan. Fún wọn ní àǹfààní láti sọ rárá. Má ṣe bá oníbàárà rẹ jiyàn. Jẹ kí àwọn oníbàárà rẹ mọ̀ pé àwọn já sọ́nà. Dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn oníbàárà rẹ fún wíwá sí ilé ìtajà rẹ.

### Fún oníbàárà

- Ọ̀nà àbáyọ̀ fún àwọn oníbàárà
- Iye owó
- Ìrọ̀rùn

### Àwọn ohun tí ó yẹ kí o ní lọ́kàn lákòókò tò ń ṣe àfihàn òwò rẹ

- O ṣe kókó nínú òwò rẹ ṣùgbọ́n àwọn oníbàárà rẹ ṣe pàtàkì jùlọ
- Àwọn oníbàárà tó tẹ́ lọ́rùn yóò padà wá rà si tí wọ́n yóò tún ṣe ìtọ́kasí.
- Ọ̀pọ̀ oníbàárà tó tẹ́lọ́rùn, ọ̀pọ̀ títà, ọ̀pọ̀ èrè.
- Wá nípa àwọn oníbàárà rẹ àti àwọn olùdíje rẹ
- Láti wà nínú òwò ṣíṣe, àwọn oníbàárà gbọdọ̀ máa wá déédéé
- Oníbàárà ń sòwò àkókò, iye àti ìtùnú.

### Àwọn ìgbésẹ̀ tó wúlò fún ṣíṣe àfihàn ọjà

### Ṣíṣe ìwádìí nípa ọjà

- Irú àwọn oníbàárà rẹ
- Iye ọjà
- Ibi ìtajà
- Ọ̀pọ̀ (bí wọ́n ń ṣe ń rà a ní ìgbà gbogbo àti iye tí wọ́n rà)
- Àwọn ọjà mìíràn, iye àti dídára.
- Ṣàlàyé ìpín ọjà rẹ.

**Ṣíṣe àfihàn gbàgúdá àti ẹja: Ohun tí o nílò láti mọ̀**

- **Ọjà náà:** The raw materials/source(s), Àwọn ohun èlò/orísun, àwọn ìlànà (GAP), àwọn ìwé ẹ̀rí tí a bèèrè, títọpasẹ̀ àti nípa ọjà. Èèpo gbàgúdá àti ikùn ẹja).
- **Àlàyé nípa ọjà:** Orísun, àgbékalẹ̀ dátà àwọn oníbàárà, àwọn olùdíje, àwọn ilé-iṣẹ́, àwọn oníyìípadà ọjà mìíràn.
- **Ṣíṣàkójọpọ̀ àti ìsàmìsí:** Èdè, alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀/ girama/gíga, kóódùù, àrokò, ìwọ̀n, (1kg/ pounds/oz), ìwúlò, àkóónú oúnjẹ aṣaralóore, agbègbè/ìlú àbínibí abbl.
- **Ìdíyelé:** Àwọn èdè ìtajà tó bá ọjà náà mú, iye ohun èlò, ṣíṣe, pínpín iṣẹ́ láàrin ara wọn, ìfipamọ́, gbígbé, awọn èdè ìtajà àgbááyé (INCOTERMS), àwọn ipá ọjà àti agbára rírà.
- **Ìgbéga:** Ìpolówó, kíkópa nínú àwọn ètò ìṣòwò (Abẹ́lẹ́ àti òkè òkun), àwọn oníbàárà, àwọn ẹ̀dínwó, àwọn ẹ̀bùn.
- **Àwọn ìlànà àti àkọsílẹ̀:** Mọ ìlànà àti òfin tó de gbígbé ọjà wọlé àti jáde. Tẹ̀lé àwọn ìlànà tó dára jùlọ àti gbígba àwọn ìwé ẹ̀rí tó dáńgájíá kí ó jẹ́ ẹ̀rí fún títà/gbígbé ọjà.
- **Ṣe ìdánwò ẹrú gbígbé:** Wá olùtajà ẹrù tí ó ṣe gbẹ́kẹ̀lé àti ẹni tí yóò gbé ọjà kọjá





**Báwo ni o ṣe lè ṣe àfihàn ẹja fún títà àti gbàgúdá àti fún táa ní?**

**Báwo ni o ṣe ní ìmọ̀ tí o nílò láti ta ọjà rẹ?**

- Ṣe ìwádìí lórí ohun tí àwọn oníbàárà tó ṣe kókó ń fẹ́.
- Lórí àwọn ìtàkùn àgbáyé bíi: tradekey.com, tradeford.com, globalresourceonline.com, alibaba.com, goforward.com etc.
- Ìwé ìròyìn ìṣòwò
- Àwọn oníbàárà lọ́wọ́lọ́wọ́
- Àwọn ilé-iṣẹ́ ìjọba
- Gbà àwọn ànfààní fún títà tí wọ́n bá gbé kalẹ̀
- Báwo ni o ṣe lè tẹ́ wọn lọ́rùn?
- Pèsè àwọn ọjà tó dára tó sì gbéwọ̀n kí ó sì tún wà ní iye owó tí kò pọ̀ jù.

**Fún taa ni?**

- Ilé-oúnjẹ, ilé ìtura, ẹgbẹ́, ilé ìtajà ìgbàlódé, àwọn ilé-iṣẹ́, ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ ọ̀sìn ẹja, àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní òkèèrè, ìwọ̀ òòrùn Áfíríkà àti àgbáyé.
- Àwọn ilé-iṣẹ́ ìpọntí- Nigeria Breweries Ltd. abbl.

- Àwọn ilé-iṣẹ́ ike- TIPA, ECOWARE (olùpèsè sîìpù àti àpò ìdọ̀tí)
- Àwọn ilé-iṣẹ́ gọ́ọ̀mù- Gum Arabic Company Nig. Ltd
- Àwọn ilé-iṣẹ́ òògùn- Ilé-iṣẹ́ Emzor àti soft health

Lákòókò tí ó ti lo sítáàṣì fún kápúsúùlù Gelatin, ó tún ṣiṣẹ́ bákan náà gẹ́gẹ́ bíi ìdíbàjẹ́ nínú àgbékalẹ̀. À ń lo ẹja fún òróró tí a fún lára ẹ̀dọ̀ kọ́ọ̀dù.

### Títa ọjà ẹja àti gbàgúdá

- **Àwọn ìbéèrè tó ṣe kókó tó kan onírúurú ènìyàn láti bèèrè**
  1. Ǹjẹ́ mò ń wá àlàyé lórí ìfẹ́ àwọn oníbàárà àti yíyan ìyàsọ́tọ̀ fún àwọn ọjà mi?
  2. Báwo ni mo ṣè le ṣe àwárí awọn oníbàárà mi àti àwọn ọjà tó dá lórí ìní wọn?
  3. Ǹjẹ́ mò ń ṣe àmúlò ọjà tó wà ní agbègbè mi lọ́wọ́lọ́wọ́ àti wíwò kọjá ọjà àpéjọ lásán?
  4. Ǹjẹ́ mò ń ṣẹ́dàá bíbéèrè fún àwọn ọjà mi?
  5. Ǹjẹ́ mó ń wá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlàyé lórí àwọn ọjà abẹ́lé àti ọjà òkèèrè (tí ìdáhùn rẹ bá jẹ́ rárá, ilé-iṣẹ́ wo yálà ti ìjọba/aládàáni ló lè ṣe àtìlẹ́yìn fún iṣẹ́ ìwádìí mi?
- **Àwọn ìbéèrè ọrọ̀-ajé pàtàkì láti bèèrè**
  1. Báwo ni mo ṣe lè ṣe ìdiwọ̀n àwọn ìdènà tí ó ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ìdíyelé àti ètò pípadà sí ọjà (pàápàá jùlọ díndín iye owó tí ó jẹ mọ ohuń amáyédẹrùn láti oko sí ọjà fún níní ìgbé ayé?
  2. Báwo ni mo ṣe lè gbé ọjà mi kọjá (láti ìpele àkọ́kọ́ sí ìparí) láti ṣe àlékún èrè lórí ọjà?

### Àwọn àdojúkọ tó ń dojú kọ títa ẹja àti gbàgúdá

### ÀWỌN ÀDOJÚKỌ

- Ọjà  tí kò dára tó.
- Àìní àwọn ọgbọ̀n ìbáraẹnisọ̀rọ̀.
- Àìsí ìpolówó.
- Àwọn iṣẹ́ ìjàmbá láti ọwọ́ àwọn alágbàtà
- Iye owó gíga tí ọkọ̀ ń gbé e.
- Ìpàdánù ìkórè.
- Ìfipamọ́/ ibi ìfi ọjà pamọ́ sí.
- Àìní àwọn ọgbọ́n tí ó nílò àti àwọn irinṣẹ́.
- Àìlo àwọn irinṣẹ́ tí a ti ní láti lò dáradára.
- Àìní ètò títà àti ètò ìṣúná/owó láti le ṣe kùkàárí ọjà títà.
- Dídá ọjà tí ó yẹ mọ̀.
- Àìní àwòrán ìyàsọ́tọ̀.
- Àìsí lórí ẹ̀rọ ayélujára.

### Àwọn ọ̀nà àbáyọ sí ọjà títà

### Àbáláyé

Ẹlẹ́yọkọ̀ọ̀kan, Ìtọ́kasí, Lílo àtẹ̀jíṣẹ́, lílo ìsọ̀, fífún ní, àwọn ètò ìsopọ̀mọ́, abbl máa ń so èso rere díẹ̀.

### Ọ̀nà ìgbàlódé

Lílo ẹ̀rọ ayélujára pẹ̀lú àkóónú tó dára, Àwọn fídíò tó bá ọjà títà mu, lílo ìtàkùn ìbánidọ́ọ̀rẹ́ bíi: – WhatsApp, Instagram, Twitter, Facebook, Linked abbl. Yíyan àwọn ọjà tí kò ní ìtẹ́lọ́rùn, Google Ad-words, Àmì ìyàsọ́tọ̀ tó dára, títo ọjà àti ìsàmìsí. Àwọn ọ̀nà wọ̀nyìí máa ń so èso réré púpọ̀.

### Some fish markets in Nigeria

- Ọjà ẹja ti Ẹ̀pẹ́ - Èkó
- Ọjà ẹja ti Màkókó - Èkó
- Ọjà ẹja ti Àjá - Èkó
- Ọjà ẹja ti Yábàá - Èkó
- Ọjà ẹja ti Muṣin - Èkó
- Ọjà ẹja ti Mile 12 - Èkó
- Ọjà ẹja ti Àjínde - Èkó
- Abúlé ìpẹja Agúngù – Kebi

### Ọjà gbàgúdá ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́

- Ọjà Ìgàngàn ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́
- Ìdásílẹ̀ oko gbàgúdá ní ìlú Ìlọràá.
- Fasola


Makoko Fish Market

### Àǹfààní ọjà òkèèrè: Gbígba ìwé-àṣẹ sí ilẹ̀ òkèèrè

- Wọlé sí ojú òpó NEPC: www.nepc.gov.ng
- Forúkọsílẹ̀ bíi olùtàjà òkèèrè
- Lọ sí ìsàlẹ̀ kí o tẹ pẹpẹ e-reg. Tẹ ṣẹ̀dá àkọọ́lẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi olùtajà òkèèrè tuntun
- O gbọdọ̀ ni ilé-iṣẹ́/ẹgbẹ́/àjọ tí kìí ṣe ti ìjọba tí ìjọba fi òǹtẹ̀ lù pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì ímeèlì. Lọ́gán tí o bá fi àdírẹ́ẹ̀sì ímeèlì rẹ ni wàá gba àtẹ̀jiṣẹ́ láti ọwọ́ àjọ NEPC láàrin ìṣẹ́jú mẹ́ta.
- Tẹ àtẹ̀jíṣẹ́ tí o gbà láti ọwọ́ àjọ NEPC èyí tí yóò gbé ọ lọ sí ojúewé tuntun mìíràn láti ṣe ìforúkọsílẹ̀.
- Fi gbogbo àwọn ìwé nípa ilé-iṣẹ́ rẹ tó bá yẹ síbẹ̀.
- Ohun tó kàn ní ojú ibi tí wàá ti san owó èyí tí ó le jẹ́ pẹ̀lú káàdì ìgbawó tàbí ní ilé-ìfowópamọ́
- Fi àwọn àlàyé lórí káàdì ìgbawó rẹ sí. Dúró fún wákàtí mẹ́rìnlélógún-méjìdínláàdọ́ta fún ìfọwọ́sí. Lọ́gán tí wọ́n bá ti fọwọ́ síi, wàá rí ìwé-ẹ̀rí ọjà òkèèrè lórí dáṣíbọ̀ọ̀dù NEPC.
- Tẹ ìwé-ẹ̀rí ọjà òkèèrè rẹ (ìwé-àṣẹ) láti orí ẹ̀rọ ayélujára tí àjọ tó ń rí sí ìgbòkègbodò ọjà òkèèrè lórílẹ̀ èdè Nàìjíríà.



### ÀWỌN ÌGBÉSẸ̀ FÚN GBÍGBÉ ERÈ OKO LỌ SÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ - GBÀGÚDÁ

- A gbọdọ̀ mọ orísun èpo igi
- Ṣe ìtọjú èpo igi pẹ̀lú omí gbígbóná tàbí òògùn apa kòkòrò láti pá àwọn kòkòrò àìfojúrí kí á tó gbìn-ín.
- Yẹ ilẹ̀ tí o fẹ́ gbin nǹkan sí kí o fi rí àrídájú wí pé kò sí òògùn apa kòkòrò níbẹ̀ àti àwọn ohun tí kò yẹ níbẹ̀.
- Tọ́jú ilẹ̀ tàbí kí ọ wá ilẹ̀ tí o dára. (Èyí yóò jẹ́ ṣíṣe láti ọwọ́ àjọ tó ń rí sí ìpa kòkòrò ohun ọ̀gbìn tí ilẹ̀ Nàìjíríà- NAQS).
- Gbin àwọn èpo igi tí a tọ́jú, àjọ NAQS gbọdọ̀ fín oko léèmejì kí a tó kó èrè oko. Èkínní nígbà tí ó ń dàgbà àti èkejì kí a tó kó erè oko.
- Fọ iṣu ní ìta gbangba kí ìyèpẹ̀ má sì í níbẹ̀ kí o sì ṣetán láti tá á lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ kí ó má bàjẹ́.
- Gba àwọn ìwé tó péye láti fọwọ́ sí ìrìnnà b.a. Ìwé tí ó péye -Ìwé-ẹ̀rí ìlera ohun ọ̀gbìn láti ọwọ́ àjọ NAQS, Ìwé-àṣẹ ìrìnnà láti ọwọ́ NEPC, Fọ́ọ̀mù NXP, Ìwé-ẹ̀rí ọmọ ìlú, Ìwé-àtẹ àkójọ, Ìwé-ẹ̀rí àyẹ̀wò tó mọ́ń láti ọwọ́ àjọ Nerolli Technologies Ltd, Fífí ara hàn dá lórí ọjàt, ìwé òfin láti ọwọ́ àjọ ìrìnnà kí ọjà tó lọ sí ilẹ̀ òkèèrè tàbí jáde abbl.
- Yan àwọn alákòóso ẹrù àti àwọn asojú pípa ẹrù mọ́n. Gba ìwé ìrìnnà ọkọ̀ òfúrufú.



**Ǹjẹ́ o kò ní ṣe/bu iyì fún gbàgúdá rẹ kí o tó gbé e lọ sí òkè òkun? Títa ọjà ẹja: Àwọn olùsàkóso àti àwọn ìlànà tó péye**

- NAFDAC/FDA
- NEPC
- Ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ ọ̀sìn ẹja ti ìjọba àpapọ̀ - Ìwé-ẹ̀rí ìmọ́tótó tó péye
- Irin àdìrọ tí a fi ń yan nǹkan
- Ibi ìpamọ́/ yàrá tútù

**Pínpín ọjà sí ilẹ̀ òkèèrè**

- Àwọn ìlú aláwọ̀ dúdú (Some African countries)
- Ìlú Yúróòpù (Europe)
- Ìlú Amẹ́ríkà (America)
- Ìlú Kánádà (Canada)

**Àkíyèsí:** Ìgbà tí àjọ tó ń ṣe kòkáárí ohun ọ̀gbìn nílẹ̀ Amẹ́ríkà (USDA) bá gbé ẹsẹ̀ kúrò lórí òfin tó dé gbígbé ẹja àrọ̀ àti ohun ẹja láti orílẹ̀-èdè Nàìjíría wọ ìlú Amẹ́ríkà, kò ṣeéṣe láti gbé e wọ inú ìlú Amẹ́ríkà.

### ỌNÀ LÁTI WỌ INÚ OJÀ ÀGBÁYÉ PẸ̀LÚ ÀWỌN ỌJÀ ORÍLẸ̀-ÈDÈ NÀÌJÍRÍÀ FÚN GBÍGBÉ LỌ SÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ

Ilé-iṣẹ́ àjọ tó ń rí sí àgbéga ọjà ilẹ̀ òkèèrè (NEPC) jẹ́ ilé-iṣẹ́ ìjọba àpapọ̀ èyí tí wọ́n dá sílẹ̀ ní ọdún 1976 pẹ̀lú èròngbà láti máa ṣe àgbéga fún àwọn ọjà tí kìí ṣe epo láti ìlú Nàìjíríà lọ sí ilẹ̀ òkèèrè. Ó ní olú ilé-iṣẹ́ ní Àbújá, ẹ̀ka mẹ́fà ní agbègbè bíi (ìpínlẹ̀Èkó, River, Kánò, Enúgu, Yólà, Plateau) àti ọ́fíìsì tó ń

rí sí ọjà òkèèrè mẹ́tàlélọ́gbọ̀n (33) káàkiri orílẹ̀-èdè.

Lákọ̀ọ́kọ́, láti jẹ awọn àǹfààní tí àjọ NEPC máa ń fún àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè, ilé-iṣẹ́ náà gbọdọ̀ fi orúkọ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè pẹ̀lú àjọ náà. Ní báyìí, ó ní oríṣiríṣi ọ̀nà tí à ń gbà láti forúkọ ilé-iṣẹ́  sílẹ̀, àwọn náà ni:

- **Ilé-iṣẹ́ onígbèsè tó mọ níwọ̀n (Limited Liability Company)**
    1. Ìwé ẹ̀rí ìforúkọsílẹ̀
    2. Fọ́ọ̀mù CO7 tàbí CA2 tàbí CAC1.1, (A nílò "Abala C", èyí tó ń ṣàlàyé nípa àwọn olùsàkóso ilé-iṣẹ́)
    3. Ẹ̀dà ìwé-ẹ̀rí àkọsílẹ̀ tó tọ̀ àti ìwé àjọṣepọ̀. (A nílò ojú-ìwé tó ní orúkọ àti ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àwọn olùsàkóso ilé-iṣẹ́)
- **Gẹ́gẹ́ bíi ẹgbẹ́ (As a cooperative society)**
    1. Ìwé-ẹ̀rí ìforúkọsílẹ̀ (Láti ọwọ́ àjọ tó ń rí sí ọrọ̀ ajé, ìjọba ìbílẹ̀ tàbí àwọn àjọ ìjọba àpapọ̀).
    2. Pẹ̀lú àwọn òfin ẹgbẹ́
- **Gẹ́gẹ́ bíi àjọ tí kìí ṣe ti ìjọba (As a None Governmental Organization) (NGO)**
    1. Ìwé-ẹ̀rí ìforúkọsílẹ̀ (Láti ọwọ́ àjọ tó ń rí sí ètò ilé-iṣẹ́)
    2. Ìwé-òfin ti NGO
    3. Ìwé àkọsílẹ gẹ́gẹ́ bíi ìtọ́sọ́nà fún olùkópa.

Ní gbogbo rẹ̀,  ẹgbẹ̀rún mẹ́tàlá àbọ̀ (#13,500) ni owó ìforúkọsílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè tuntun. Gbígba ìwé-ẹ̀rí ìsọdọ̀tun mìíràn jẹ́ ẹgbẹ̀rún méje àbọ̀ (#7,500), sísọ ìwé-ẹ̀rí nù tàbí bíba ìwé-ẹ̀rí jẹ́ jẹ́ ẹgbẹ̀rún méjìlá àbọ̀ (#12,500) èyí tó jẹ́ wí pé orí ẹ̀rọ ayélujára ní gbogbo owó náà yóò ti jẹ́ sísan. Ọdún méjì (oṣù mẹ́rìnlélógún) ni ìwé-àṣẹ NEPC yóò fi jẹ́ lílò. Lẹ́yìn ìgbà náà, ọdọọdun ni ìsọdọ̀tun ìwé-àṣẹ náà yóò máa wáyé. Àkíyèsí, tí gbogbo ìwé tí o fi sílẹ̀ lásìkò ìforúkọsílẹ̀ jẹ́ àtẹ́wọ́gbà, ìwé-ẹ̀ri yóò wá fún títẹ̀ jáde nínú dáṣíbọ̀ọ̀dù òǹtàjà lẹ́yìn wákàtí mẹ́rìnlélógún.

Lẹ́yìn ìyẹn, àjọ NEPC ti ṣe àlàkalẹ̀ àwọn ọ̀nà tí wọn yóò gbà láti ran àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè lọ́wọ́ kí gbígbé ọjà wọn lọ sí ilẹ̀ òkèèrè lè máa lọ geere. Díẹ̀ lára àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe ni wiwà ọjà fún àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè..

- ọn Ọjà Àgbáyé (International Trade Fairs): Àjọ NEPC yóò mú òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè ní àgbáyé pẹ̀lú àwọn ọjà wọn fún ìgbélárugẹ ní ọjà àgbáyé. Fún ìdí èyí, ẹ̀dínwó yóò bá owó ìrìnnà fún àwọn òǹtàjà tí wọ́n bá mú, wọn yóò gba atúmọ̀ èdè fún wọn tí kìí bá ṣe ìlú tí wọ́n ti ń sọ èdè òyìnbó àti ilé tó ní ìta gbángba láti pàtẹ ọjà wọn sí fún àwọn olùbárà wọn. Nípa èyí, ọjà jẹ́ dídá sílẹ̀ fún òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè láti ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn tó ń gbé ọjà wọlé níbi àfihàn náà.
- Ìtanilólobó láti ọwọ́ akọ́jàwọlé tó le ti kàn sí àjọ NEPC fún òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè tó bá le ní iye àti irú ọjà tí wọ́n ń bèrè. Olú ilé-iṣẹ́ NEPC ni yóò fi irú ìtanilólobó yìí sí gbogbo ẹ̀ka àti àwọn ọ́fìsì kéékèèké níbi tí àwọn náà yóò fi tó gbogbo àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè tó forùkọ sílẹ̀ ní ìpínlẹ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.
- Bákan náà, àjọ NEPC tún máa ń lo àǹfààní àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìlú òkèèrè láti fi tó wọn létí láti máa ra àwọn ọjà tí wọ́n gbé wá láti ìlú Nàìjíríà. Àwọn òǹtàjà tún lo ọgbọ́n láti máa gbé àwọn ọjà oúnjẹ ilẹ̀ Nàìjíríà fún àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tó wà nílùú òkèèrè kí wọ́n le máa rí oúnjẹ ilẹ̀ wa jẹ.
- Ìtàkùn ìbáni-dọ́rẹ̀ẹ́ náà jẹ́ ọ̀nà mìíràn tí àjọ NEPC máa ń gba àwọn òntàjà ilẹ̀ òkèèrè níyànjú láti lo àǹfààní rẹ̀ àti láti wá àwọn ọjà ní ìlú òkèèrè tí wọ́n ti ń tá irú ọjà wọn.
- Àjọ NEPC tún ní àjọsọpọ̀ pẹ̀lú àwọn aṣojú ìlú kọ̀ọ̀kan láti máa wá ibi ìtajà fún àwọn ọjà ilú Nàìjíríà. Tí wọ́n bá ti rí irú àwọn ọjà wọ̀nyìí, wọn yóò fi tó àwọn òǹtàjà ìlú òkèèrè.

## OHUN TÍ O NÍ LÁTI MỌ̀ NÍPA ỌJÀ ÒKÈÈRÈ

- IO dára kí òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè ṣe ìwádìí lórí ìlànà gbígbé ọjà wọlé, yíyànnà àwọn òwò, owó-ori sísan àti ohun mìíràn lọ́pọ̀lọpọ̀.
- Òǹtàjà òkèèrè gbọdọ̀ gbájúmọ́ iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ lórí ọjà kan ní pàtó.
- Ṣe ìwádìí lórí àwọn ọjà àwọn olùdíje rẹ. Wádìí ohun tí wọ́n ń ṣe tó dára.
- Lọ sí àwọn àpéjọ lórí àwọn ọjà kọ̀ọ̀kan.
- Gba ìmọ̀ràn lọ́wọ́ àwọn òǹtàjà ìlú òkèèrè tó ti ní ìrírí.
- Gbìyànjú láti dá bá àwọn oníbàárà tó ṣe kókó sọ̀rọ̀. O le ṣe àmúlò èyí pẹ̀lú àwọn àlàkalẹ̀ orí ẹ̀rọ ayélujára.
- Ní ìmọ̀ àdúgbò ọjà náà (àṣà, ènìyàn, ẹ̀sìn àti iru owó...)
- Ibi àfihàn ọjà (Trade fairs) tó papọ̀ mọ́ ọjà ẹni àti ọ̀dọ aṣojú ìlú kọ̀ọ̀kan jẹ́ ibi pàtàkì kan láti mọ̀ nípa ọjà tó dára.

Ní àfikún sí àwọn ohun ọ̀gbìn tí a tò sílẹ̀ láti ṣe ìgbèlárugẹ́ wọn, mo dábàá Jíǹjà (Ginger), Ata ìjọ̀sì (Chili pepper), Àwọn Tòmátò (Tomatoes), Mọ̀ríǹgà (Moringa), Túmẹ́ríìkì (Turmeric), Ewé sóbò (Hisbiscus flower) le jẹ́ àfikún nítorí pé ìpínlẹ̀ Kàdúná ní àfiwé àwọn àǹfààní lórí àwọn ohun ọ̀gbìn wọ̀nyìí àti wí pé wọ́n ní owó lórí ní ọjà òkèèrè. Gbígbé ọjà lọ sí ìlú mìíràn, iṣẹ́òjọ́ ọ̀la ni.....

### Àṣàyàn iṣẹ́-ṣíṣe

Mú èyíkéyìí nínú ọjà rẹ kí o sì ṣàlàyé àǹfààní tí àwọn ọ̀nà tí ò ń gbà láti polówó ọjà rè gẹ́gẹ́ bíi òǹtàjà:

1. Àwọn ènìyàn: Táa ni yóò rà a?
2. Ibùdó: buy Ibo ni wọn yóò tí rà á?
3. Ọjà: Báwo ni wọ́n ṣe fẹ́ ẹ sí?
4. Iye: what price are they willing/able to buy Èlò ni wọ́n fẹ́/rà ó?
5. Ìpolówó: Kílódé tí wọn yóò fi rà á?

## Ọ̀NÀ LÁTI WỌ INÚ OJÀ ÀGBÁYÉ PẸ̀LÚ ÀWỌN ỌJÀ ORÍLẸ̀-ÈDÈ NÀÌJÍRÍÀ FÚN GBÍGBÉ LỌ SÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ

Ilé-iṣẹ́ àjọ tó ń rí sí àgbéga ọjà ilẹ̀ òkèèrè (NEPC) jẹ́ ilé-iṣẹ́ ìjọba àpapọ̀ èyí tí wọ́n dá sílẹ̀ ní ọdún 1976 pẹ̀lú èròngbà láti máa ṣe àgbéga fún àwọn ọjà tí kìí ṣe epo láti ìlú Nàìjíríà lọ sí ilẹ̀ òkèèrè. Ó ní olú ilé-iṣẹ́ ní Àbújá, ẹ̀ka mẹ́fà ní agbègbè bíi (ìpínlẹ̀Èkó, River, Kánò, Enúgu, Yólà, Plateau) àti ọ́fíìsì tó ń rí sí ọjà òkèèrè mẹ́tàlélọ́gbọ̀n (33) káàkiri orílẹ̀-èdè.

Lákọ̀ọ́kọ́, láti jẹ awọn àǹfààní tí àjọ NEPC máa ń fún àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè, ilé-iṣẹ́ náà gbọdọ̀ fi orúkọ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè pẹ̀lú àjọ náà. Ní báyìí, ó ní oríṣiríṣi ọ̀nà tí à ń gbà láti forúkọ ilé-iṣẹ́ sílẹ̀, àwọn náà ni:

- **Ilé-iṣẹ́ onígbèsè tó mọ̀ níwọ̀n (Limited Liability Company)**
    1. Ìwé ẹ̀rí ìforúkọsílẹ̀
    2. Fọ́ọ̀mù CO7 tàbí CA2 tàbí CAC1.1, (A nílò “Abala C”, èyí tó ń ṣàlàyé nípa àwọn olùsàkóso ilé-iṣẹ́)
    3. Ẹ̀dà ìwé-ẹ̀rí àkọsílẹ̀ tó tọ̀ àti ìwé àjọṣepọ̀. (A nílò ojú-ìwé tó ní orúkọ àti ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àwọn olùsàkóso ilé-iṣẹ́
- **Gẹ́gẹ́ bíi àjọ (As a Cooperative Society)**
    1. Ìwé-ẹ̀rí ìforúkọsílẹ̀ (Láti ọwọ́ àjọ tó ń rí sí ọrọ̀ ajé, ìjọba ìbílẹ̀ tàbí àwọn àjọ ìjọba àpapọ̀).
    2. Pẹ̀lú àwọn òfin ẹgbẹ́
- **Gẹ́gẹ́ bíi àjọ tí kìí ṣe ti ìjọba As a None Governmental Organization (NGO)**
    1. Ìwé-ẹ̀rí ìforúkọsílẹ̀ (Láti ọwọ́ àjọ tó ń rí sí ètò ilé-iṣẹ́)

2. Ìwé-òfin ti NGO
3. Ìwé àkọsílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi ìtọ́sọ́nà fún olùkópa.

Ní gbogbo rẹ̀, ẹgbẹ̀rún mẹ́tàlá àbọ̀ (#13,500) ni owó ìforúkọsílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè tuntun. Gbígba ìwé-ẹ̀rí ìsọdọ̀tun mìíràn jẹ́ ẹgbẹ̀rún méje àbọ̀ (#7,500), sísọ ìwé-ẹ̀rí nù tàbí bíba ìwé-ẹ̀rí jẹ́ jẹ́ ẹgbẹ̀rún méjìlá àbọ̀ (#12,500) èyí tó jẹ́ wí pé orí ẹ̀rọ ayélujára ní gbogbo owó náà yóò ti jẹ́ sísan. Ọdún méjì (oṣù mẹ́rìnlélógún) ni ìwé-àṣẹ NEPC yóò fi jẹ́ lílò. Lẹ́yìn ìgbà náà, ọdọọdun ni ìsọdọ̀tun ìwé-àṣẹ náà yóò máa wáyé. Àkíyèsí, tí gbogbo ìwé tí o fi sílẹ̀ lásìkò ìforúkọsílẹ̀ jẹ́ àtẹ́wọ́gbà, ìwé-ẹ̀ri yóò wá fún títẹ̀ jáde nínú dáṣíbọ̀ọ̀dù òǹtàjà lẹ́yìn wákàtí mẹ́rìnlélógún.

Lẹ́yìn ìyẹn, àjọ NEPC ti ṣe àlàkalẹ̀ àwọn ọ̀nà tí wọn yóò gbà láti ran àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè lọ́wọ́ kí gbígbé ọjà wọn lọ sí ilẹ̀ òkèèrè lè máa lọ geere. Díẹ̀ lára àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe ni wiwà ọjà fún àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè

- Àfihàn ní àwọn Ọjà Àgbáyé (International Trade Fairs): Àjọ NEPC yóò mú òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè ní àgbáyé pẹ̀lú àwọn ọjà wọn fún ìgbéláругẹ ní ọjà àgbáyé. Fún ìdí èyí, ẹ̀dínwó yóò bá owó ìrìnnà fún àwọn òǹtàjà tí wọ́n bá mú, wọn yóò gba atúmọ̀ èdè fún wọn tí kìí bá ṣe ìlú tí wọ́n ti ń sọ èdè òyìnbó àti ilé tó ní ìta gbángba láti pàtẹ ọjà wọn sí fún àwọn olùbárà wọn. Nípa èyí, ọjà jẹ́ dídá sílẹ̀ fún òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè láti ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn tó ń gbé ọjà wọlé níbi àfihàn náà.
- Ìtanilólobó láti ọwọ́ akọ́jàwọlé tó le ti kàn sí àjọ NEPC fún òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè tó bá le ní iye àti irú ọjà tí wọ́n ń bèrè. Olú ilé-iṣẹ́ NEPC ni yóò fi irú ìtanilólobó yìí sí gbogbo ẹ̀ka àti àwọn ọ́fìsì kéékèèké níbi tí àwọn náà yóò fi tó gbogbo àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè tó forùkọ sílẹ̀ ní ìpínlẹ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.
- Bákan náà, àjọ NEPC tún máa ń lo àǹfààní àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìlú òkèèrè láti fi tó wọn létí láti máa ra àwọn ọjà tí wọ́n gbé wá láti ìlú Nàìjíríà. Àwọn òǹtàjà tún lo ọgbọ́n láti máa gbé àwọn ọjà oúnjẹ ilẹ̀ Nàìjíríà fún àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tó wà nílùú òkèèrè kí wọ́n le máa rí oúnjẹ ilẹ̀ wa jẹ.
- Ìtàkùn ìbáni-dọ́rẹ̀ẹ́ náà jẹ́ ọ̀nà mìíràn tí àjọ NEPC máa ń gba àwọn òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè níyànjú láti lo àǹfààní rẹ̀ àti láti wá àwọn ọjà ní ìlú òkèèrè tí wọ́n ti ń tá irú ọjà wọn.
- Àjọ NEPC tún ní àjọṣọpọ̀ pẹ̀lú àwọn aṣojú ìlú kọ̀ọ̀kan láti máa wá ibi ìtajà fún àwọn ọjà ilú Nàìjíríà. Tí wọ́n bá ti rí irú àwọn ọjà wọ̀nyìí, wọn yóò fi tó àwọn òǹtàjà ìlú òkèèrè.


## OHUN TÍ O NÍ LÁTI MỌ̀ NÍPA ỌJÀ ÒKÈÈRÈ

- O dára kí òǹtàjà ilẹ̀ òkèèrè ṣe ìwádìí lórí ìlànà gbígbé ọjà wọlé, yíyànnà àwọn òwò, owó-ori sísan àti ohun mìíràn lọ́pọ̀lọpọ̀.
- Òǹtàjà òkèèrè gbọdọ̀ gbájúmọ́ iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ lórí ọjà kan ní pàtó.
- Ṣe ìwádìí lórí àwọn ọjà àwọn olùdíje rẹ. Wádìí ohun tí wọ́n ń ṣe tó dára.
- Lọ sí àwọn àpéjọ lórí àwọn ọjà kọ̀ọ̀kan.
- Gba ìmọ̀ràn lọ́wọ́ àwọn òǹtàjà ìlú òkèèrè tó ti ní ìrírí.
- Gbìyànjú láti dá bá àwọn oníbààrà tó ṣe kókó sọ̀rọ̀. O le ṣe àmúlò èyí pẹ̀lú àwọn àlàkalẹ̀ orí ẹ̀rọ ayélujára.
- Ní ìmọ̀ àdúgbò ọjà náà (àṣà, ènìyàn, ẹ̀sìn àti iru owó...)
- Ibi àfihàn ọjà (Trade fairs) tó papọ̀ mọ́ ọjà ẹni àti ọ̀dọ aṣojú ìlú kọ̀ọ̀kan jẹ́ ibi pàtàkì kan láti mọ̀ nípa ọjà tó dára

Ní àfikún sí àwọn ohun ọ̀gbìn tí a tò sílẹ̀ láti ṣe ìgbéláругẹ́ wọn, mo dábàá Jíńjà (Ginger), Ata ìjọ̀sì (Chili pepper), Àwọn Tòmátò (Tomatoes), Mọ̀ríńgà (Moringa), Túmẹ́rîkì (Turmeric), Ewé sóbò (Hisbiscus flower) le jẹ́ àfikún nítorí pé ìpínlẹ̀ Kàdúná ní àfiwé àwọn àǹfààní lórí àwọn ohun ọ̀gbìn wọ̀nyìí àti wí pé wọ́n ní owó lórí ní ọjà òkèèrè. Gbígbé ọjà lọ sí ìlú mìíràn, iṣẹ́ ọjọ́ ọ̀la ni.....

# ẸKỌ KEJE

# ÀKỌSÍLẸ̀ ÀTI ÌKÓWÈÉPAMỌ́



## ÈTÒ FÚN ABALA Ẹ̀KỌ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ ìlànà. Àwọn olùkọ́ le ṣe àtúnṣe sí agbọn tó bá wù wọ́n láti jẹ́ kí ó bá ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́ mu. Ó yẹ kí wọ́n bèèrè àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

### Àwọn àfọkànsí pàtàkì:

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn olùkópa yóò le;

- Àǹfààní tó wà nínú ṣíṣe àkọsílẹ̀.
- TÀwọn ìwé tó yẹ kí á kọ silẹ̀.
- Bí wọ́n ṣe máa ń ṣe àkọsílẹ̀.

### Ìlànà

- Kínní ṣíṣe àkọsílẹ̀?
- Ìdí tí a fi ń ṣe àkọsílẹ̀
- Ìwé àti àkọsílẹ̀ ṣíṣe
- Àwọn àwòmọ́ tó yẹ kí á wò kí á tó bẹ̀rẹ̀ òwò.
- Àǹfààní ṣíṣe àkọsílẹ̀
- Oríṣiríṣi àkọsílẹ̀ tí àwọn àgbẹ̀ máa ń ṣe
- Ìdí owó orí àti àǹfààní rẹ̀.
- Báwo lo ṣe le ṣe àkọsílẹ̀ rẹ dáadáa?
- Irú àkọsílẹ̀ wo lo lè ṣe láti le fi ìdí owó sísan múlẹ̀?
- Àwọn ìdènà wo ló lè mú ènìyàn láti má lè ṣe àkọsílẹ̀ tó dára àti ní déédé?
- Àwọn ọ̀nà wo ló dára láti ṣe àkọsílẹ̀??
- Àwọn òfin fún ṣíṣe àkọsílẹ̀ tó dára
- Kínní àwọn ohun tó yẹ kí o ṣóra fún tí o bá ń ta ọjà àwìn?
- Kínní àwọn ohun tó yẹ kí o ṣóra fún tí o bá ń ra ọjà àwìn?
- Báwo ni wà á ṣe ṣe àkọsílẹ̀ ọjà títà àti rírà ní àwìn?
- Àwọn àdojúkọ wo ni àwọn obìnrin máa ń dojú kọ nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àkọsílẹ̀ àti tí wọ́n bá ń ṣe àkọsílẹ̀ owó níná?
- Àwọn kókó ọrọ
- Iṣẹ́ àyànṣe



## KÍN NI ÀKỌSÍLẸ̀ ṢÍṢE?

Ṣíṣe àkọsílẹ̀ túmọ̀ sí ohun méjì: it refers to writing down all the money that comes into yoó túmọ̀ sí ṣíṣe àkọsílẹ̀ gbogbo owó tó wọ inú òwò àti àpò ẹni àti gbogbo owó tó jáde láti inú òwò àti àpò ẹni. Ṣíṣe àkọsílẹ̀ tún túmọ̀ sí fífi gbogbo ìwé tó dá lórí ìgbòkègbodò òwò pamọ́ (àwọn ìwé àgbàsílẹ̀, àwọn ìwé tó ṣe kókó) sí nínú èyí tí a gbà tí a bá ń ṣe ọ̀rọ̀ ajé (b.a. rírà tàbí títa ọjà, ṣíṣe ìrànlọ́wọ́, gbígba owó tàbí fífi owó ráńṣẹ́ abbl.).

### Àǹfààní Ṣíṣe Àkọsílẹ̀

- Ìwọ yóò mọ iye owó tí o ti gbà.
- Ìwọ yóò mọ iye owó tí o ti ná àti bí o ṣe ná a.
- O lè ṣe ìṣirò bóyá ò ń ṣe èrè tàbí ò ń pàdánù.
- Yóò fún ọ ní àǹfààní láti ṣe ìpinnu tó dára lórí ohun tí o fẹ́ rà àti tà àti ìgbà.
- Láti lè mọ̀ bí owó níná ṣe ń lọ.
- Láti yàgò fún àríyànjiyàn lórí ìsanwó.
- Láti tọpinpin gbèsè.
- Fún ètò ìnáwó.
- Láti yàgò fún níná owó ní ìnákùná.
- Láti ṣe àlékún ìgboyà nínú àwọn olùdòkóòwó bíi àwọn ilé-ìfowópamọ́.

### Ìwé àti Àkọsílẹ̀ ṣíṣe

- Ìwé àkọsílẹ̀ àwọn owó
- Ìwé àkọsílẹ̀ owó níná
- Ìwé àkọsílẹ̀ ọjà títà
- Ìwé àkọsílẹ̀ ọjà rírà
- Ìwé àkọsílẹ̀ owó sísan
- Ìwé àkọsílẹ̀ irinṣẹ́
- Ìwé àkójọ ọjà
- Ìwé àkọsílẹ̀ àwọn onígbèsè
- Ìwé àkọsílẹ̀ àwọn aláwìn



### Àwọn àwòmọ́ tó yẹ kí á wò kí á tó bẹ̀rẹ̀ òwò

- Èrò òwò (Business Idea)
- Owó tó wà nílẹ̀ (pẹ̀lú owó èlé tó kéré)
- Ìdúróṣinṣin òwò náà
- Ẹni náà gbọdọ̀ ní ìfẹ́ sí òwò náà
- Ẹni náà gbọdọ̀ ní ìmọ lórí ọ̀nà ìtajà ọjà tó ní lọ́kàn.

### Advantages of Record Keeping

- Ó máa ń fi ẹ̀rí gbogbo àwọn ìdúnàdúrà pamọ́
- Fífi àwọn ẹ̀rí owó sísàn pamọ́ láti yàgò fún wàhálà
- Ó máa ń jẹ́ kí o mójútó ìlera òwò rẹ.
- Ó máa ń rán òwò lọ́wọ́ nípa níní àkọsílẹ̀ òwò tó péye
- Ó máa ń ràn ènìyàn lọ́wọ́ láti ṣe apákan ìṣòwò láti bèèrè fún ẹ̀dínwó àti láti ṣe ìṣirò ọjà tí a lò.
- Ó tún jẹ́ ọ̀nà kan tí ó dára láti mójútó ìlọsíwájú òwò àti láti mọ ibi tí owó ti ń bọ̀.
- Àkọsílẹ̀ ìwé owó (Cash book record)
- Ìwé jọ́nà (Journal ledger book)
- Ìwé àkọsílẹ̀ owó níná (Purchase record book)
- Ìwé àkọsílẹ̀ ọjà títà (Sales record book)
- Ìwé àkọsílẹ̀ owó olójú mẹ́ta (Three Colum cash book)
- Ínfọ̀ìsì àti ìwé ìsanwó (Invoice and receipt slip)

### Ìdí Owó Orí àti Àǹfààní rẹ̀

- Àjọ FIRS ló ń rí sí gbígba owó orí
- Owó orí jẹ́ owó tí ènìyàn gbọdọ̀ san fún ìjọba láti fi pèsè ohun amáyérọrùn fún ará ìlú

### Oríṣiríṣi owó orí

Àwọn owó orí tó ṣe kókó tó jọ mọ́ òwò kéékèèké ni wọ̀nyìí:

- Owó orí ara ẹni (Personal income tax)
- Owó orí ilé-iṣẹ́ (Company tax)
- Àfikún Owó orí iye (Value added tax)
- Owó orí àìsan (With holding tax and)
- Owó orí ilé-ẹ̀kọ́ (Educational tax)

### Àǹfààní owó orí ni

- Fún owó láti pèsè àwọn ohun amáyérọrùn fún ará ìlú.
- Fún ìdàgbàsókè àti ṣíṣe iṣẹ́ àkànṣe ìrànlọ́wọ́
- Fún ìrìnnà ará ìlú
- àti gbé ayé ọjà sókè ju bóṣewà tẹ́lẹ̀ lọ




### Ìlànà Ìwé àti Ìpamọ́ Àkọsílẹ̀ (Principle of Book and Record Keeping)

- Ó gbọdọ̀ rọrùn fún lílò
- Ó gbọdọ̀ yé ni olú ìrọ̀rún
- Ó gbọdọ̀ péye
- Ó gbọdọ̀ bá ọjọ́ mu

Láti yàgò fún wàhálà, ṣe àkọsílẹ̀ kí o sì tò o dáradára.

### Kín ni o nílò láti ṣe àkọsílẹ̀ tó dára?

1. Bíírò (Pen)
2. Ìwé tó nípọn (Hard cover big note)
3. Ohun ìṣirò (Calculator) àti
4. Ẹ̀rọ àgbélétan (Laptop)

### Àkọsílẹ̀ wo lo lè fi ṣe ẹ̀rí owó sísan?

1. Receipts
2. Ínfọ́ìsì (Invoices)
3. Tẹ́là báńkì (Bank tellers)
4. Tẹ́là POS (POS Tellers)
5. Fọ́húṣà (Vouchers)
6. Wábíílì àti ọ́dà (Waybill and orders)

### Àwọn ohun wo ló lè máa dí àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láti má lè ṣe àkọsílẹ̀ tó dára àti nígbà gbogbo?

1. Àìní òye tó kún/àìmọ́kọ-mọ̀ọ́kà
2. Àìsàn owó orí
3. Àṣà (àìkà á kún)
4. Àìsì àkókò àti tàbí owó láti ra ohun èlò (Ìwé, ìkọ̀wé (Pen), ohun ìṣirò (Calculator), ẹ̀rọ àgbélétan (Laptop) )

### Awọn ìṣe wo ló dára jù ní ṣíṣe àkọsílẹ̀?

1. Ṣe àkọsílẹ̀ gbogbo owó tó ń wọlé àti èyí tó ń jáde sí inú ìwé owó rẹ. Mo gbà ọ́ níyànjú wí pé kí o ní ìwé àkọsílẹ̀ méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀: ọ̀kan fún iṣẹ́ ilé, ọ̀kan fún òwò.
2. Sẹ àkọsílẹ̀ àwọn ọjà tí wọ́n sanwó fún nìkan sí inú ìwé owó. Ya ojú- ìwé mìíràn nínú ìwé owó rẹ sọ́tọ̀ fún ṣíṣe àkọsílẹ̀ àwọn ọjà tí wọ́n rà àti tà ní àwìn.
3. Bákan náà, ṣe àfikún àwọn ọjà tí o fún àwọn ẹbí àti ọ̀rẹ́ ní ọ̀fẹ̀ẹ́.
4. Yẹ àwọn àkọsílẹ̀ rẹ déédéé. Ṣe ìṣirò owó tó ṣẹ́kù, Rántí wí pé owó tó sẹ́kù gbọdọ̀ wà ní kíkọ sílẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ ojú-ìwé tuntun. Ní àsùnwọ̀n àpamọ́ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ilé-ìfowópamọ́ fún ti ara rẹ àti ti òwò.
5. Tí o bá fí owó sí ilé-ìfowópamọ́, bèèrè fún ẹ̀rí ìwé owó rẹ (Statement) láti mọ iye owó tó ti ń wọlé àti iye owó tó ń jáde. Ní àsùnwọ̀n àpamọ́ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ilé-ìfowópamọ́ fún ti ara rẹ àti ti òwò.

### Kín ni àwọn ohun tó yẹ kí o ṣọ́ra fún tí o bá ń ta ọjà ní àwìn?

1. Títa ọjà àwìn dára láti mú àwọn oníbàárà déédéé mọ́lẹ̀ ṣùgbọ́n ó ní àwọn àléébù:
2. Ó le gba àwọn oníbàárà ní àkókò tó pẹ́ láti san owó padà tàbí kí wọ́n má san-án mọ́.
3. TÀríyànjiyàn le wáyé lórí owó sísan.
4. Títa ọjà olówó kéékèèké máa ń padà di owó ńlá.
5. Má ṣe ta ọjà àwìn fún àwọn oníbàárà tí kìí ra ọjà déédé
6. Títa ọjà àwìn máa ǹ da owó sísan rú èyí tí ó lè jẹ́ kí òwò rẹ ní ìṣòro owó níná nígbà tí ìnáwó òjijì bá yọjú.
7. Ṣe òfin fún títa ọjà ní àwìn bí àpẹẹrẹ, fún àwọn oníbàárà tó ṣe gbẹ́kẹ̀lé tí yóò san owó ní àsìkò nìkan, béèrè fún owó díẹ̀ fún sísan nínú gbogbo rẹ̀, máa tọjú owó tó tó láti fi rà ọjà tuntun.

### Kín ni àwọn ohun tó yẹ kí o ṣọ́ra fún tí o bá ń ra ọjà ní àwìn?

1. Ní àfiwé, ríra ọjà ní àwìn le ran òwò rẹ lọ́wọ́ nípa fífún ọ ní àǹfààní láti ra ọjà ní ìgbà tí kò wọ́n, tọ́jú rẹ̀ àti tà á nígbà tí ó bá wọ́n. Ó' tún lè ràn ọ́ lọ́wọ́ láti rà ojà ní odidi àti láti bo ìnáwó ọdọọdún tó máa ń pọ̀.
2. Síbẹ̀síbẹ̀, ó ní àwọn àdojúkọ̀ wọ̀nyìí:
    - Ẹ le já lórí owó sísan.
    - O le gbàgbé nípa rẹ̀.
    - O lè ra ìràkurà.
    - Nígbà mìíràn, o ní láti san ju iye owó lọ nítorí owó èlé/àfikún owó.
    - Nígbà gbogbo, o ní láti jẹ́ oníbàárà déédéé lọ́dọ̀ olùpèsè, èyí tí yóò fún ọ ní àǹfààní ọ̀nà mìíràn/àṣàyàn ìfigagbága.
3. Tí o bá gbìyànjú láti ra ọjà ní àwìn, ríi dájú pé o san owó ọjà àwìn náà lásìkò!
4. Ríra ọjà ní àwìn fún ara rẹ tàbí àwọn ará ilé rẹ lè kó ọ sí wàhálà. Kí o tó ra ọjà ní àwìn,.wádìí èrè tí wà á  rí pẹ̀lú òwò rẹ. Èrè náà le tó fún sísan gbèsè, ó sì tún le ṣẹ́kù àwọn owó láti fi pamọ́.

### Báwo ni o ṣe lè ṣe àkọsílẹ̀ rírà àti títa ọjà ní àwìn?

- Ìwé gbèsè ni a fi máa ń ṣe àkọsílẹ̀ gbogbo owó tí oníbàárà jẹ ọ́ àti owó tí o jẹ olùpèsè.
- O lè tọ́jú ojú-ìwé fún àwọn oníbàárà tó sábà máa ń ra ọjà ní àwìn. Gbogbo ìgbà tí ẹni bá ra ọjà àwìn tàbí san díẹ̀ nínú owó tó jẹ, wà á ṣe àkọsílẹ̀ rẹ̀ tí wà á sí ṣe ìṣirò owó tuntun tó wà nílẹ̀.
- Tí ìdúnàádúrà pẹ̀lú owó bá wáyé, (oníbàárà ń san owó padà, ìwọ náà ń san owó fún olùpèsè), ṣe àkọsílẹ̀ owó tuntun sí inú ìwé gbèsè kí o sì ṣe àkọsílẹ̀ owó tí ó ń wọlé/jáde sínú ìwé owó.

### Àwọn àdojúkọ wo ni àwọn obìnrin máa ń dojúkọ tí wọ́n bá ń ṣe ìpamọ́ àkọsílẹ̀ àti àmójútó owó níná?

- Wọn kìí jẹ́ kí àwọn obìnrin nígbà mìíránmójútó owó níná nínú ilé àti ṣíṣe àkọsílẹ̀. Èyí lè jẹ́ nípa àìní òye púpọ̀ nípa gbogbo ìnáwó mọ́lẹ́bí.
- Àwọn obìnrin nígbà mìíràn máa ń ní ìtẹ́lọ́rùn nípa kí ọkọ wọ́n máa mójútó bí wọ́n ṣe ń ná owó nínú ilé àti ṣíṣe àkọsílẹ̀.
- Àwọn obìnrin nígbà mìíràn ní díẹ̀ nínú (owó) ẹ̀kọ́ mọ̀ọ́kọ-mọ̀ọ́kà (látàrí àìfún wọn ni àyè púpọ̀) èyí tó lè jẹ́ kí ó jẹ́ àdojúkọ fún wọn láti mọ nípa ṣíṣe àkọsílẹ̀ owó.

### Àwọn kókó ọ̀rọ̀

- Gbé ní sàkání bí o ṣe mọ.
- Ná owó dáadáa.
- Wá ọ̀nà tí owó tí yóò wọlé yóò fi pọ̀.
- Fi owó pamọ́ déédéé.
- Ṣe òwò pẹ̀lú ọ̀gbọ́n
- Ṣe àkọsílẹ̀ gbogbo owó tí ó wọlé àti jáde nígbà tí ó ṣẹlẹ̀.
- Fí ẹ̀rí owó sísan pamọ́.
- Yẹ ìwé rẹ wò ní ẹ̀ẹ̀kan lọ́sẹ̀.
- Olùdókòwò gidi lọ́kùnrin/lóbìnrin máa ń ṣe àkọsílẹ̀ owó tó wọlé àti òwò tó jáde, ṣe àkọsílẹ̀ owó ilé níná àti owó òwò níná lọ̀tọ̀ tí yóò sì ríi dájú pé owó tó ń ná kò pa òwò lára.

### Iṣẹ́ àyànṣe

Ìpamọ́-àkọsílẹ̀ òní ọ̀sìn ẹja

Ní òwúrọ̀ kùtùkùtù 1/9, abilékọ Tọ̀lá  ní ẹgbẹ̀rún lọ́nà ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́rún (#900,000) nínú òwò ẹja rẹ̀. 1/9; Abiléko Tọ̀lá ta ẹja tó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọgbọ̀n níye (#30,000) fún Abiléko Témì.

1/9: Abiléko Tọ̀lá ra oúnjẹ ẹja tó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà igba (#200,000) fún àgbẹ̀ rẹ̀.

3/9: Abileko Tọ̀lá gbé ọjà ẹja tó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà márùndílọ́gọ̀sán (#175,000) lọ sí ibùsọ̀ Fasad.

3/9: Ọ̀gbẹ́ni James gbé irinṣẹ́ tó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọ̀rìnlélégbà (#280,000) fún àgbẹ̀ Abiléko Tọ̀lá.

5/9: Abiléko Tọ̀lá ta ẹja tó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọgọ́fà (#120,000) fún oníbààrà kan.

6/9 Abiléko Tọ̀lá san owó àtúnṣe ẹ̀rọ omi fífà àti ẹ̀rọ̀ amúnáwá nínú oko rẹ ní ẹgbẹ̀rún lọ́nà márùndínlógójì (#35,000).

Ṣe àkọsílẹ̀ owó Abiléko tó ṣẹ́kù ní ìparí 6/9.

### Simple Basic Cashbook

| NO | DÉÈTÌ | ACC | TRANSACTION (ÌNÁWÓ) | Owó tó wọlé | Owó tó jáde | Iye Owó tó kù |
|---|---|---|---|---|---|---|
| **1** | | **10** | | | | |
| **2** | | **51** | | | | |
| **3** | | **52** | | | | |
| **4** | | **10** | | | | |
| **5** | | **53** | | | | |
| **6** | | **10** | | | | |
| **7** | | **61** | | | | |
| **8** | | **10** | | | | |
| **9** | | **61** | | | | |
| **10** | | **51** | | | | |
| | | | **Sum Balance** | | | |

# ẸKỌ KẸJỌ

# ÀWỌN ÌLÀNÀ ÌṢÚNÁ ÀTI ÌṢIRÒ-OWÓ FÚN OKO-ÒWÒ



### Ètò fún Abala Ẹ̀kọ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ atọ́nà. Àwọn olùkọ́ni lè ṣe àtúnṣe sí èyíkéyìí abala láti mú kí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́. Àwọn ìbéèrè àgbéyẹ̀wò gbọdọ̀ jẹ́ bíbèèrè kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

---

**Àwọn àfojúsùn gbòógì:**

Ní ìparí ẹ̀kọ́ yìí, ó yẹ kí àwọ akópa lè:

- Ní òye àwọn ìlàna- à-ń-tẹ̀lé fún ìṣirò ètò-ìṣúná
- Àwọn orísun ìdàgbàsókè okòwò
- Àwọn ìlàna- à-ń-tẹ̀lé fún ìṣàkóso ètò-Ìṣúná okòwò

---

**Àkóónú**

- Ètò-Ìṣúná
- Àwọn ìlanilọ́yẹ̀ nípa owó
- Ìwúlò Ìṣúná
- Àwọn orísun ìṣúná
- Orísun láti ọ̀dọ̀ ìjọba
- Àwọn orísun mìíràn
- Ojú òpó mẹ́fà fún ìṣúná
- Ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ilé ìfowópamọ́
- Ofin márùn-ún yíyánilówó
- Kín ni ohun àmúṣe láti rí i dájú pé o ni àwọn àmúsọrọ̀ ìṣúná láti mú àlá rẹ ṣẹ?
- Àwọn ojú òpó ìṣiro owó
- Iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe
- Ọ̀rọ̀ ìparí

---




## KÍN NI ÈTÒ ÌṢÚNÁ?

Ìṣúná ni àkóso owó tó pẹ̀lú àwọn akitiyan bí i ìdókòwò, yíyá owó, yíyá ẹlòmìíràn lówó, ìpinnu ìṣúná àti ìfowópamọ́. Ìṣúná ni lílò àti ìdarí owó. Wíwá owó jẹ́ òpó kan pàtàkì ìṣúnà. Bí o kò bá ní owó tó tó láti gbọ́ bùkátà okòwò rẹ, ohun tó kan ni owó àwọn ẹlòmìíràn( Other People Money (OPM))

Ọ̀nà méjì ni à ń gbà wá OPM. Ọ̀na méjèèjì ni ó ń nípa lórí okòwò lọ́na ọ̀tọ̀tọ̀

- **Gbèsè:** Okòwò náà máa ń yá owó tí yóò sì san-án padà lẹ́yìn àkókò àti èlé tí a ti là kalẹ̀
- **Àjọni:** Okòwò náa yóò fi iyé ìpín ìní  kan sílẹ̀ láti gba owó



### Ìlanilọ́yẹ̀ nípa owó

- Ojú-Ìwòye tí ó tọ̀nà
- Owó jẹ́ àmúṣọrọ̀ tí ó sọ̀wọ́n, ó nílò kí a da ààbò bò ó dáa dáa
- Ṣe ìpinyà lááárín ìgbésíayé rẹ àti owó tí ó yá
- Nì àìtíîsan gbogbo gbèsè okòwò náà kò tí i di tìrẹ nìkan.
- Ní òye nípa ewu tó rọ̀ mọ́ lílo owó àwọn ẹlòmìíràn.
- Má ṣe dá ìmọ̀ràn láti gba ìsinmi ọlọ́jọ gbọ̀ọrọ lẹ́nu okòwò , pàápàá jùlọ tí gbèsè púpọ̀ bá wà nílẹ̀
- Má ṣe pa ojú rẹ̀ dé nígbà tí o bá ń ka àdéhùn ẹ̀yáwó, má sì ṣe kùnà láti bèèrè fún ìmọ̀ràn nígbà tí ó bá nílò rẹ̀

### Ìwúlò Ìṣuná

- Láti lé kápá ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ iṣẹ́
- Láti lè bẹ̀rẹ̀: (àpẹ̀ẹrẹ. San owó fún ààyè iṣẹ́, ṣe àkójọ àwọn ohun èlò pàtàkì)
- Láti mú kí ọwọ́ iṣẹ́ gbòòrò sí i  : (àpẹ̀ẹrẹ. ṣe àkójọ àwọn ẹ̀rọ tuntun, ṣe àfikún ohun èlò ìṣehunlọ́jọ̀, abbl)
- Láti sọ iṣẹ́ di ti ìgbàlódé: (ṣe ìṣípòrọpò àwọn ohun èlò àtijọ́, dókòwò nínú ayélujára, dókòwò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àwọn òṣìṣẹ́ àti ìdánilójú pípéye )
- Láti bá àwọn àìní pàjáwìrì pàdé nígbà tí iṣẹ́ bá fẹ́ bẹ̀rẹ̀

### Àwọn ọ̀nà Ìṣúná gbòógì

- Owó tó wà ní ìpamọ́ ẹni (ṣíṣe iṣẹ́ fún àwọn ẹlòmìíràn, fífi ohun ìní ẹni jìn)
- Ẹbí àti àwọn ọ̀rẹ́
- Owó yíyá
- Ẹ̀yáwó láti ọwọ́ ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù
- Àjọ ọjọọjúmọ́, ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ tàbí oṣooṣù (Àjọ tàbí Esúsú)
- Àgbàtà  ọja àwìn
- Àyàlò tàbí san díẹ̀díẹ̀
- Ètò Àjùmọ̀ni

### Other sources

### Non-governmental sources

- Owó ìdàgbàsókè CBN N220b MSME
- Ilé ìfowópamọ́ àwọn ilé-iṣẹ́
- Ilé ìfowópamọ́ àwọn àgbẹ̀ pàápàá fún àwọn ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́
- Àwọn ètò àkànṣe bí i  ITF, ẹ̀yáwó pàjáwìrì  fún COVID 19
- NDE
- Ètò ìrànwọ́ CBN
- Ètò ìdókòwò fún àwọn àgbẹ̀ olókòwò kéékèèké (AGSMEIS) fún olóríjorí tí iye tí ó pọ̀jù jẹ́ #10.000.000 èlé orí rẹ̀ jẹ́ 9%, osù mẹ́fà sí ọdún kan gẹ́gẹ́ bí i àkókò ìdádúró , láì fi nǹkankan ṣe ìdúró, pẹ̀lú onídùúró méjì
- SMEDAN
- Ilé ìfowópamọ́ àwọn àgbẹ̀ tí ó ń da owó pọ̀ mọ́  ẹ̀yáwó SMEDAN. Ẹ̀yáwó náà wà láàrín #1.2m sí #5m. Èlé orí rẹ̀ jẹ́ 5%, onídùúró méjì, àwọn ẹ̀ka tí ó ń pèsè oúnjẹ gbọdọ̀ ní (SUIN) Ìwé ẹ̀rí SMEDAN, CAC, TIN, àti òǹkà NAFDAC.

- Ìjọba ìbílẹ̀ kan ọjà kan (OLOP) Ẹ̀yáwó fún àwọn ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù Ẹ̀yáwó70% àti owó ìrànwọ́ 30% pẹ̀lú èlé 7%. Ẹ̀yáwó yìí wà fún ohun èlò, owó iṣẹ́ àti ààyè iṣẹ́.

### Òpó Ètò Ìṣúná

### Àwọn òpó ìṣúná mẹ́fà tí o gbọ́dọ̀ mọ̀ gẹ́gẹ́ bí olókòwò ni

1. Ewu àti èrè: Bí ewu bá ṣe ga ni èrè yóò ṣe ga, bí ewu bá ṣe kéré ni èrè yóò ṣe kéré
2. Iyì ara owó máa ń dínkù bí ọjọ́ ṣe ń gorí ọjọ́
3. Ìrìn owó, bí owó ṣe ń wọlé àti bí ó ṣe ń jáde nínú okòwò. Owó tó wọlé yóò máa pọ̀ tí àdínkú yóò máa bá èyí tí ó ń jáde
4. Èrè jíjẹ àti yíyá kánkán ọjà ṣe pàtàkì nínú òwò ṣíṣe. ó ń ṣe àfihàn bí okòwò náà ṣe ń yá sí
5. Ìdáyàtọ̀, ó máa ń ṣe àdínkù ewu tó nínú okòwò
6. Adójútòfò , èyí ni láti máa yá owó láti ibi tí ó tọ́ láti ṣe òwò

### Bíbẹ̀rẹ̀ àjọṣepọ̀ tó so èso rere pẹ̀lú ilé ìfowópamọ́

- Fi orúkọ okòwò rẹ sílẹ̀ pẹ̀lú CAC
- Ìwé ẹ̀rí owó orí àti TIN láti ọ̀dọ̀ FIRS
- Ṣí àpò àṣùwọ̀n owó pẹ̀lú ilé-iṣẹ́ ìfowópamọ́ tó wù ọ́
- Níní àkọsílẹ̀ owó tó mọ́yán lórí

### Ofin Márùn-ún yíyánilówó

- **Ìwà:** Ìgbìyànjù láti dá owó padà, mímú àdéhùn ṣẹ
- **Agbára:** Agbára láti dá owó padà, ṣíṣe ìdámọ̀ ọ̀na láti rí owó san padà, àgbéyẹ̀wò ọ̀nà bí owó ti ń rìn fún ọjọ́ iwájú , àti ipá láti lè ṣe àwọn ojúṣe ẹ̀náwó yàtọ̀ fún ẹ̀yáwó.
- **Ìdúró:** Ní àìfepo bọyọ̀, ohun ìdúró ṣe pàtàkì fún yíyá owó. A gbọ́dọ̀ ṣe adójútòfò tó tọ́, ó gbọ́dọ̀ ṣe é tà, kò gbọ̀dọ̀ ní ẹrù kankan lọ́rùn, mọ̀ bọ́yá ó ṣe é tì kúrò lójú kan tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́, Ìrìnsí-owó: pàápàá , bí owó ṣe ń sàn nínú okòwò náà, ẹ̀rí láti fi agbára láti kojú àwọn ojúṣe ẹ̀náwó bí i èlé àti ojú owó sísan, Ọ̀nà bí owó ṣe ń sàn dúró fún ìlerà okòwò




**Kín ni ohun àmúṣe láti rí i dájú pé o ni àwọn àmúsọrọ̀ ìṣúná láti mú àlá rẹ ṣẹ?**

- Ṣe àgbéró ọ̀nà bí owó ṣe ń sàn àti dùkìá ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ
- Ní àwọn àfojúsùn fún ara rẹ̀ (tayọ rékọjá tòní kí o sì rí i dájú pé àwọn àfojúsùn rẹ mọ́yán lórí (SMART): ṣe pàtó, ní òdiwọn, ní àkitiyan, ṣíṣeéṣe àti gbèdéke àsìkò ) máa se ètò fún bí o ó ṣe mu àwọn àfojúsùn ìṣúná rẹ ṣẹ
- Máa ṣe ìpinnu àwọn ẹ̀náwó tó jàjù fún ọjọ́ iwájú
- Kó ara rẹ̀ ní ìjánú lórí ẹ̀náwó àti ìfowópamọ́ rẹ
- Máa yàgò fún ẹ̀náwó tí kò ní ìtumọ̀ nígbà gbogbo

**Àwọn ohun tí ó wọ́pọ̀ nínú òpó ìṣirò owó.**

1. **Àwọn Dúkìá:** Àwọn ohun tí ó ní iye lórí tí ṣe ti olókoòwò tí ó ń lò láti ṣe okòwò náà. Àpeèrẹ. Dúkìà tí kìí paradà, ilẹ̀, ilé, àwọn ẹ̀rọ ńláńlá àti dúkìá tọwọ́- owó, onígbèsè. Àsansílẹ̀ owó.
2. **Gbèsè:** Ẹ̀yí ni iyé gbèsè tí ó jẹ́ gẹ́gẹ́ bí i olùdókòwò .Àpeèrẹ. gbèsè tọwọ́- gbèsè tí o ò tí i san
3. **Owó ìdókòwò:** Ẹ̀yí ni owó tí a ti lò tàbí tí a ó lò láti bẹ̀rẹ̀ okòwò .
4. **Owó tí ó wọlé:** Ẹ̀yí ni owó tí o rí nígbà tí o bá ta ọjà tàbí ṣe iṣẹ́ kan fún oníbàárà
5. Owó tí a ná: Ẹ̀yí ni owó tí a ná látí pawó wọlé, fún àpẹẹ̀rẹ owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ rẹ tàbí owó ilé tí o san fún onílé
6. **Èrè:** èyí ni èlé tí ó wà nínú owó tí o pa wọlé tó borí gbogbo ẹ̀náwó, tàbí kí a yọ owó tí a ná lórí okòwò nínú owó tí a pa wọlé.
7. **Òfò:** èyí ni nígbà tí owó tí o ná jáde pọ̀ ju owó tí o pa wọlé.
8. **Àkọsílẹ̀ ọ̀jà àwìn àwọn oníbàárà:** Àksílẹ̀ owó tí à ń lò làti wádìí ọjà tí a tà fún àwọn oníbàárà ní àwìn
9. **Àkọsílẹ̀ àjẹ́sílẹ̀ owó:** Àkọsílẹ̀ tí à ń lò láti wádìí gbogbo àjẹsílẹ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn olùpèsè ọjà, agbaṣẹ́ṣe abbl.
10. **Ọ̀nà ìwádìí iye ìgbà tí dúkìá ti lò:** Ọ̀nà tí à ń gbà wádìí ọjọ́ tí dúkìá tí lò nílẹ̀ pẹ̀lú ìlò wọn.
11. **Àkọsílẹ̀ fún ìwádìí gbogbo ọjà:** Àkọsílẹ tí ó ń wádìí gbogbo ọjà tí a fẹ́ tà fún àwọn oníbàárà.

## OFIN TI IṢIRO



### Idánrawò

Abiléko̩ Àdàmú ti ń dókòwò fún ọdún méjì, ó ń ṣíṣé ní ìgbéléwọ̀n 20%. O ń gbìmọ̀ láti fi kún ìpèsè ọjà rẹ̀ pèlú 20%. Àmọ́ ṣá, ó ń kojú ìṣòrò owó. Abiléko̩ Àdàmú ti wá fún ìmọ̀ràn àti ìṣeéṣe láti rí ìrànlọ́wọ́ owó lọ́dọ́ ẹgbẹ́ yín  fún ìmúdàgbàsókè okòwò rẹ̀.

### Ìbéèrè

1. Ṣàlàyé ipò tí okòwò Abiléko̩ Àdàmú wà lọ́wọ́lọ́wọ́
2. ṣe àfihàn ọ̀nà tí ó ṣe é ṣe láti rí owó ṣe ìmúdàgbàsókè okòwò rẹ̀
3. 3ṣe àfihan àwọn ohun tí ó nílò láti ṣe kí ó lè rí owó lò fún okòwò rẹ̀

### Ìkáàdìí

- Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbọ́n òkòwò ló ti di èrò ọkan lásán nítorí àìsówó
- Ọ̀pọ̀lọpọ̀ okòwò gidi ni wọ́n ti já kúrò lágbo nítorí àìsówó to tówó
- Bí ó bá ṣe dandan kí o yá owó, rí i dájú pé o ní òye kíkún nípa ìdí pàtàkì tí ó fi fẹ́ ya owó, àjọsọ kí o sì rí i dájú pé ẹ dìjọ sọ àsọgún lórí èlé ẹ̀yáwó
- Ẹ̀yáwó ni ó yẹ ká máa kà sí ohun tó gbẹ̀yìn ní ṣíṣe. Àmọ́ ṣá, rónu ohun ńlá kí o sì bẹ̀rẹ̀ díẹ̀ díẹ̀ nísìnsìn yìí pẹ̀lú ohun àmúsọrọ̀ díẹ̀ tó ń bẹ nílẹ̀

# ÈKỌ́ 9

# ATỌ́NÀ ÈTO OKÒWÒ



## Ètò fún Abala Ẹ̀kọ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ atọ́nà. Àwọn olùkọ́ni lè ṣe àtúnṣe sí èyíkéyìí abala láti mú kí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́. Àwọn ìbéèrè àgbéyẹ̀wò gbọdọ̀ jẹ́ bíbèèrè kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

### Lórí àyélujára

Kín ni Ètò Okòwò

Pàtàkì Ètò Okòwò

### Ẹ̀ka Ètò okòwò

- Ìwòye gbogbogbò nípa okòwò
- Ìwádìí nípa ọja
- Ọjà títà
- Iṣẹ́
- Àtúpalẹ̀ ìsúná



# ÌFÁÀRÀ

## KÍN NI ÈTÒ OKÒWÒ

- Àkótán àpèjúwe okòwò, pípèsè àlàyé lórí ọjà tàbí iṣẹ́, ọjà títà àti ètò ìsúná
- Ó jẹ́ àwòrán ọ̀nà tó ń ṣe atọ́nà okòwò sí àfojúsùn rẹ̀
- Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àwọn èrò àti àníyàn olùdókòwò

## Pàtàkì Ètò okówò

1. Ó jẹ́ ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ nígbà tí a bá fẹ́ bẹ̀rẹ̀ òwò ṣíṣe
2. Ó ṣe ìrànwọ́ láti ní àfojúsùn èrò rẹ
3. Ó ń ràn ọ́ lọ́wọ́ láti yanjú àfojúsùn rẹ àti ọ̀nà tí o ó gbà ṣe é
4. Ó ń ṣe ìrànwọ́ láti mọ̀ bóya ọjà rẹ yóò ta
5. Ó ń ṣe ìrànwọ́ láti mọ̀ ìfagagbága tí ó wà nílẹ̀
6. Ó ń ṣe ìrànwọ́ láti ṣírò iye owó ìbẹ̀rẹ̀ òwò, owó tó ń wọlé, owó ti o ó ná àti èrè
7. Ó ń fi hàn bóyá èròńgbà okòwò rẹ yẹ láti ṣiṣẹ́ tò
8. Ó ń jẹ́ kí o mọ àwọn ewu tó wà níbẹ̀ àti ọ̀nà láti ṣe àdínkù rẹ̀
9. Ó ń ṣe ìrànwọ́ láti rí owó gbà fún òwò
10. Ó n ṣe ìrànwọ́ láti ṣàkóso okòwò nípa yíyẹ̀ẹ́wò lóòrèkóòrè
11. O lè lò ó láti ṣe àgbékalẹ̀ èròńgbà

## Abala 1: Ìwòye gbogbogbò nípa okòwò

1. Àlàyé lórí Òwo- Èyí ni àwọn àlàyé bí i Orúkọ, àdírẹ́sì, ipò òwò àti ọ̀nà ì-kan-síra-ẹni
2. Ìsọníṣókí òwò. Èyí ni a máa ń kọ kẹ́hìn
- Ìdí tí o fi fẹ́ bẹ̀rẹ̀ òwò náà- irú ọjà wo ni ẹ̀ ń tà tàbí irú iṣẹ́ wo ni ẹ ń ṣe?
- Báwo ní ẹ ṣe fẹ́ gbé e jáde?
3. Àfojúsùn òwò náà
- Kín ni o rò pé yóò jẹ́ ọjọ́ iwájú òwò náà?
4. Ohun tàbí iṣẹ́ tí òwò náà ń pèsè
- Àlàyé nípa Ohun tàbí iṣẹ́ tí ẹ̀ ń pèsè

- Kín ló mú Ohun tàbí iṣé tí ẹ̀ ń pèsè yàtọ̀ sí ti àwọn ẹlòmìíràn?
- Àwọn ànfàní Ohun tàbí iṣé tí ẹ̀ ń pèsè

### Abala 2: Ìwádìí nípa ọjà

1. Ọjà

- **Kín ni ìwọ̀n títóbi ọjà fún ohun tí ẹ ń ṣe**
- **Ẹ̀ka wo ni òwò náà wà?**
- **Kín ni àfojúsùn ọjà rẹ?**
- **Njẹ́ orísun ìmọ rẹ jẹ́ tààrà tàbí tẹ̀lé ǹ tẹ̀lé?**

2. Ìtakànǹgbọ̀n

- **Kín ni ọjà tàbí iṣẹ́ tí àwọn orogún rẹ ń tà/ṣe?**
- **Kín ni ó mú ọ yàtọ̀sí àwọn orogún rẹ?**
- **Báwo ni àwọn tó fẹ́ di oníbààrà rẹ ra ọjà lọ́dọ̀ rẹ dípò ti àwọn orogún rẹ?**

3. Àyíká

- **Ǹjẹ́ àyíká òwò náà dára fún okòwò rẹ?**
- **Ǹjẹ́ ílána ìjọba kankan nípa lóri okòwò rẹ?**
- **Ǹjẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ òṣelú nípa lóri okòwò rẹ?**
- **Ìmọ̀ nípa àwọn Olùpèsè ọjà**

**4. Ní ìmọ̀ nípa orísìírísìí Olùpèsèọjà?**

- **Ǹjẹ́ wọ́n lè ta àwìn àti pé ṣe wọ́n ṣe é gbé àrà lé?**
- **Ṣe ìwádìí bóyá ìṣòwò wọn bá tìrẹ mu kí o tó pinnu láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú wọn.**

### Abala 3: Títà Ọjà

**1. Ọgbọ́n ìtajà**

- Kín ni ọ̀nà ìtajà rẹ̀ tí ó jẹ́ àrà ọ̀tọ̀
- Se àmúlò àwọn "P" márùn-ún ọ̀jà títà (5Ps of marketing)
- Ọjà, iyé orí ọjà, ibùdó ọjà, ìpolówó ọjà, àwọn enìyàn

**2. Irú ọ̀nà ìpolówó ọjà wo ni o fẹ́ ṣàmúlò (Káàdì ìpolówó ọjà, Ìwé àlẹ̀mógiri, ìwé ìròyìn, Rédío àti Tẹlifísàn.**

**3. Ọgbọ́n ìdíye lé ọjà**

- Iye tí ó ná + èrè mi
- Iye tí àwọn orogún rẹ dá lé ọjà wọn

### Abala 4: Àmúṣe àwọn iṣẹ́

**1. Àkóso**

- Ta ni yóò ṣakóso òwò náà?
- Kín ni ìrírí àti ọgbọ́n wọn?
- Tà ni yóò máa ṣe àkóso àwọn agbègbè tí ó ṣe pàtàkì bí i ẹ̀ka ípèsè ọjà, ọjà títà, ẹ̀ka ìṣúná àti ìṣàkóso?

**2. Òṣìṣẹ́**

- Òṣìṣẹ́ mélòó ni o nílò?
- Kín ni ìpele ọgbọ́n wọn?
- Ìlànà lílo òṣìṣẹ́

**3. Àyíká Okòwò/ ibi iṣẹ́**

- Ibo ni wọn yóò ti máa ṣiṣẹ́ náà?
- Ààyè ńlá ni o nílò àbí kékeré?

- Ǹjẹ́ ààyè náà mú ọ ta kàǹgbàn?

**4. Àwọn ẹ̀ro àti ohun èlò**

- Àlàyé lórí bí o ṣe fẹ́ pèsè ọjà tàbí iṣẹ́ rẹ
- Ọjọ́/ọ̀sẹ̀ mélòó ni òwò náà yóò fi máa lọ?

**5. Àwọn Ìlànà-à-ń-tẹ̀lé**

- Àwọn àjọ wo ni o nílò ìwé àṣe wọn ?

**6. Àwọn àfojúsùn ọjọ́ iwájú**

**Abala 5: Ìṣuná**

- Iye owó láti fi bẹ̀rẹ̀
- Gbogbo Ẹ̀náwó
- Àsọtẹ́lẹ̀ bí owó yóò ṣe rìn
- Àsọtẹ́lẹ̀ èrè àti àdánù
- Àsọtẹ́lẹ̀ Ìwé owó

**ÌṢIRÒ ÌṢÚNÁ**

- Ibùdó
- Dúkìá tí kìí paradà àti àwọn ohun èlò

| S/N | Ẹ̀yà | Òǹkà iye tí à ń retí | Iye tí ó ná wa lápapọ̀(N) | Àpapọ̀ |
|---|---|---|---|---|
| | | | | |

- Ètò fún Ọ̀ṣìṣẹ́

| S/N | Ipò | Ìpele Ẹ̀kọ́ àti ìrírí | òǹkà ní ipò | Owó oṣù(N) | Owó ọ̀yà oṣooṣù(N) |
|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | |

- Àwọn ohun èlò gbàrọgùdù

| S/N | Ẹ̀yà | Iye fún oṣù 2 | Iye tí ó ná wa(N) |
|---|---|---|---|
| | | | |

- Orísun àwọn Èlò- ní abẹ́lé tàbí ní òkè ókun

**ÌYÈ ÀPAPỌ̀ OWÓ TÍ YÓÒ PARÍ ÌDÓKÒWÒ**

| S/N | Ìdókòwò | Àpapọ̀ owó tí a ná(N) |
|---|---|---|
| 1 | Dúkìá ojú kan àti àwọn ohun èlò | |
| 2 | Àwọn ohun èlò gbàrọgùdù(2 months) | |
| 3 | Owó oṣù àti owó ọ̀yà ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ ( 3 months) | |
| 4 | Ẹ̀náwó ìṣáájú ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ | |
| | **Apapọ̀** | |

## ÀWỌN ÈRÒ FÚN OKÒWÒ ÀTI ÀÀYÈ TÓ ṢÍ SÍLẸ̀ ÌDÓKÒWÒ



Ilé iṣẹ́ Bàtà kan rán àwọn aṣojú méjì láti lọ ta àwọn ọjà wọn ní ìgbèríkò kan. Wọ́n fún ọ̀kọ̀ọ̀kan aṣojú ní bàtà mẹ̀wàá mẹ́wàá láti tà.

Ní ìgbà tí wọ́n dé abúlé náà, wọ́n ṣe àkíyèsí pé àwọn ará abúlé náà kìí wọ bàtà.

Aṣojú àkókó pé ọ́fíìsì, ó sì sọ pé " ọ̀gá, a ṣe àṣìṣe ńlá; àwọn ènìyàn yìí kìí wọ bàtà. Torí èyí mò ń padà bọ̀ sí ọ́fíìsì lẹ́yẹ̀ọ̀sọkà".


Aṣojú kejì pe ọ́fîìsì, ó sọ pé "Ọ̀gá, àwọn ènìyàn yìí kìí wọ bàtà; ẹ bá mi kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ bàtà sí i wá torí mo fẹ́ ta bàtà fún gbogbo wọn!!!



### Kín ni ààyè tó ṣí ṣílẹ̀ nínú okòwò

- Àwọn okòwò tó lààmìlaka máa ń bẹ̀rẹ̀ nípa dídí àwọn àlàfo tó wa nínú ààyè okòwò tàbí Ìbéèrè tuntun fún ọjà tàbí iṣẹ́ tuntun.
- Ǹjẹ́ ààyè fún okòwò wà ní agbègbè rẹ?

**Orísun Èrò fún**




## Kín ló ń ṣàfihàn ààyè tó ṣí ṣílẹ̀ nínú okòwò

1. Kùdìẹ̀kudiẹ nínú ìpèsè ọjà/ iṣẹ́
2. Ọjà tàbí iṣẹ́ tó gbowó lórí jù
3. Ìmọ̀-ẹ̀rọ tuntun
4. Ọjà tuntun (agbo-ilé, káńpọ̀sì, àwọn ọ́fíísì abbl)
5. Ìyàtọ̀ nínú ìwà àwùjọ, ìṣesí àti ààyò
6. Iyàtọ̀ nínú sáà ìlànà-à-ń-tẹ̀lé (fífí òfin de kíkó àwọn ọtí ẹlẹ́rìndòdò wọlé, lílo pakí láti ṣe búrẹ́dì, ẹja tútù gígàn
7. Ìjàǹbá òjijì bí i ẹ̀kún omi, ìyàtọ̀ ojú ọjọ́ abbl.

## Àwọn Ọkọ̀ tó ṣe àfihàn ààyè tó ṣí ṣílẹ̀ nínú okòwò

1. Irú ẹni tí olùdókòwò jẹ́- Ìwọ
2. Mímọ àwọn ìgbésẹ̀ fún ìdámọ̀
3. Títẹ̀lé ipa ìgbésẹ̀ náà

## KNOWING THE PROCESS FOR BUSINESS OPPORTUNITY

### ENTREPRENEUR
- Social Economic Profile
- Back ground
- Interest
- Preference
- Resources
- Skills

### ENVIRONMENT
- Location peculiarities
- Infrastructure
- Competition
- Social Cultural factors
- Resources available
- Economic conditions
- Local market potentials

### ENTERPRISE
**Types of Economic Activities**
- Nature of activity like manufacturing, services,trading etc.
- Size of investment
- Product
- Technology

### Àwọn ìpa okòwò tó lè ṣelẹ̀

**1. "Tẹ̀lé ẹ̀bùn rẹ"**
Àpẹ́ẹrẹ. Messi, Okocha

**2. Máà sá tọ ohun tí o nífẹ̀ẹ́ sí**
Àpẹ́ẹrẹ. Olórin, òṣèré

**3. Tèlé**
Àpẹ́ẹrẹ. ilé ẹ̀kọ́, ìlera, ìrànlọ́wọ́, Lájọlájọ

**4. Gbígbọ́kàn lé dùkìá**
E.g. ogún, ìrànlọ́wọ́ Ìjọba



## Atọ́ka ààyè

- Ó lè ṣẹ̀dá iye pàtó tó fojú hàn nítorí ó ń yànjú ìṣòro tó fojú hàn
- Ó lè mú èrè gọbọyi wá fún olùdásílẹ̀ àti olókoòwò
- Ó bá ọgbgbọ́n àti ìkápá olùdásílẹ̀ àti ìgbìmọ̀ olùdarí mu
- Alágbèéró (Êrè tó ń tẹ̀síwájú)
- Ànfàní wà fún owó tó wa nílẹ̀

## Abala Ìdánrawò

- Sọ àwọn èròńgbà àgbàyanu 3 tó lè yíra padà di ààyè fún okòwò
- Ránti àwọn kókó márùnún fún ààyè okòwò rere

Rí I dájú pé àwọn èròńgbà òwò rẹ ní...

**Jẹ́ Pàtó**

**Ní odiwọ̀n**

**Ṣe é yanjú**

**Gbájúmọ́ èsì**

**Ní àfojúsùn**



# NÍNÍ ÒYE NÍPA ÌDÁṢẸ́SÍLẸ̀A



**Àfojúsùn Ẹ̀kọ́:**

**Ní ìparí abala yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:**

- Ní òye ìtumọ̀ "Ìdáṣẹ́sílẹ̀" àti "Olùdásílẹ̀"
- Ṣe ìgbéléwọ̀n àwọn àwòmọ́ Olùdásílẹ̀
- Ní òye ohun tí à ń pè ní Ìfaradà
- ṣe àmúlò àkókò lọ́nà tó dára jù
- ṣe àtòjọ àwọn àfojúsùn tó mọ́yámlóri (SMART)
- Ní ìgbàgbọ́ nínú ara rẹ

## 1.0 Ìdáṣẹ́sílẹ̀

Ọ̀rọ̀ tí à ń pè ní ìdáṣẹ́sílẹ̀ ni a mú láti inú ọ̀rọ̀-ìṣe Faransé entreprendre tó túnmọ̀ sí "láti ṣe nǹkan", Ọ̀rọ̀ tí à ń pè ní ìdáṣẹ́sílẹ̀ tún lè túnmọ̀ sí àwọn wọ̀nyìí:

- Ìgbésẹ̀ ṣíṣe ìdámọ̀ àwọn ààyè tó yọ sílẹ̀ nínú ọjà, ṣíṣe àtòjọ àwọn ohun àmúṣọrọ̀ tí ó nílò láti ṣiṣẹ́ tọ àwọn ààyè náà, da àwọn ohun àmúṣọrọ̀ sínú òwò náà láti lè rí èrè fún ìgbà pípẹ́
- Ìgbésẹ̀ bí àwọn ènìyàn ṣe máa mọ̀ nípa níní okòwò  tí wọn yóò sì ṣe àgbékalẹ̀ àwọn èróńgbà àti láti bẹ̀rẹ̀ okòwò náà
- ṣíṣe ìdámọ̀ ànfàní okòwò  tó rinlẹ̀  àti ṣíṣe àkójọ  àwọn ohun àmúṣọrọ̀ láti sọ àwọ ànfàní náà di òkòwò tí ó yanjú nípa ṣíṣe ohun tuntun, wíwọ ewu, àti rirò nípa ìlọsíwájú

Ìdáṣẹ́sílẹ̀ ni ìṣe àti ìgbésẹ̀ tí ó yọrí sí ìṣẹ̀dá ohun ọ̀tun ìdàgbàsókè àti ìmúgbòòrò. Ó túnmọ̀ sí ipá tí ènìyàn ní láti sọ èròńgbà di ìṣe àti lílọ́wọ́ sí ọrọ̀ tó wùlò fún àwùjọ nípa lílo ìrònú nípa ohun túntun àti ṣíṣe e láti bá àìní àwọn olùmúlò pàdé, lílo ààgùn ẹni, àkókò àti àròjinlẹ̀.

Lílọ́wọ́ sí ìdáṣẹ́sílẹ̀ mú àwọn ènìyàn kúrò láti ẹni tó ń wá iṣẹ́ di ẹni tó ń pèsè iṣẹ́, èyí tó ṣe gbòògì ní ìlú tó ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn tí kò níṣẹ́ lọ́wọ́. Ó nílò ọgbọ́n àtinúdá tó jẹ́ igi lẹ́yìn ọgbà iṣẹ̀dá ohun ọ̀tun.

Olùdásílẹ̀: Olùdásílẹ̀ ni ẹnikẹ́ni tí ó bá ń ṣẹ̀dá tí ó sì ṣe àtòjọ èròńgbà okòwò tí ó sì fara da ewù dídá okòwò sílẹ̀ láti pèsè ọjà àti ìṣẹ́ tí yóò bá àìní àwọn olùmúlò pàdé.

Olùdásílẹ̀ tún ni ẹnìyàn, ìdáṣẹ́sílẹ̀ nì jẹ́ ìgbésẹ̀. Àti ọkùnrin àti obìnrin ló lè di olùdáṣẹ́sílẹ̀ tó làlùyọ; kò ní ohunkóhun ṣe pẹ̀lú bóyá akọ tàbi abo. Gbogbo olùdáṣẹ́sílẹ̀ ni olókòwò, ṣùgbọ́n kìí ṣe gbogbo olókòwò ni olùdáṣẹ́sílẹ̀.

Ronú nípa ẹni tó jókòó sí ẹ̀bá ọ̀ná ilé rẹ tí ó ń ta oúnjẹ irú kan náà, ó ń lo apẹ oúnjẹ kan náà, lórí tábílì kan náà, ó sì lè má leè gbé ìgbé ayé ìdẹ̀rùn tó wúni lórí. Irú ẹni bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ oǹṣòwò ṣùgbọ́n kìí ṣe Olùdáṣẹ́sílẹ̀.

Olùdáṣẹ́sílẹ̀ ni ẹni tí ọkàn rẹ̀ rọ̀ mọ́ káràkátà tí ó máa ń wá ọ̀nà láti mú kí okòwò dàgbà sí i. Olùdáṣẹ́sílẹ̀ ní a tún lè pè ní ẹni tí ó jẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ó ṣàwàrí àǹfàní okòwò láti pèsè ọjà tàbí iṣẹ́ tuntun tàbí tí ó dára sí i tí ó sì ń ṣe ìdámọ̀ ọ̀nà tuntun tí a fi lè gbà kó ohun èlò jọ.

Ní àkótán, Olùdáṣẹ́sílẹ̀ ni ẹni tí ó má a ń gbọn àyíká wò yẹ́bẹ́yẹ́bẹ́ láti wa ohun ọ̀tọ̀ tí ó le pèsè ààyè fún ṣíṣẹ̀dá okòwò ti yóò dàgbà.

- **Olùdáṣẹ́sílẹ̀ ni ẹni tí**
  1. ó ní ipá láti ṣe ìdámọ̀ àti láti ṣiṣẹ́ tọ àlàfo nínú okòwò
  2. ṣe onígbọ̀wọ́ òwò
  3. Gbé owó kalẹ̀ láti gbọ́ bùkátà rẹ̀
  4. Ṣe àkójọ àwọn èlò àrígbámú, owó, ènìyàn pàtàkì tí ó nílò fún dídarí okòwò
  5. Ní àwọn àfojúsùn fún ara rẹ̀ àti àwọn ẹlòmìíràn
  6. Ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìṣe tí ó tọ́ láti mú àṣeyọrí wá
  7. La gbogbo tàbí èyí tó pọ̀jù nínú ewu kọja
- **Olùdáṣẹ́sílẹ̀ jẹ́ olùpèsè iṣẹ́ yàtọ̀ fún ẹni tó ń wá iṣẹ́**
- **Olùdáṣẹ́sílẹ̀ ni ẹni ti ó:**
  1. Ní àlá
  2. Ní ìran
  3. ṣetán láti la ewu kọjá
  4. Mú rírí jádé nínú àìrí

### Ànfàní/pàtàkì Ìdáṣẹ́sílẹ̀

- Ìdáṣẹ́sílẹ̀ láti ṣe àgbékalẹ̀ orísìíríṣìí iṣẹ́ ara ẹni
- Olùdáṣẹ́sílẹ̀ jẹ́ ọ̀gá ara wọn tí ó sì fún wọn ní àǹfàní láti ní ìtẹ́lọ́rùn lẹ́nu iṣẹ́ àti ìrọ̀rùn iṣẹ́
- Ìrunisókè láti sọ àwọn ohun èlò abẹ́lé di ọjà tó yanjú fún ìlò àwọn ènìyan nílẹ̀ yìí àti lóke òkun
- Ìdíje tó rẹ́sẹ̀ walẹ̀ máa ń jẹ́ kí àwọn ọjà tó dángájíá wà ní ọjà, èyí sì ń mú kí ọjà àti iṣẹ́ púpọ̀ síi wà fún àwọn òǹrajà
- Àgbéǹde ọjà tuntun
- Ìgbéláruge Ìlò àwọn ẹ̀rọ òde òní láti ṣe ọjà ní ìlànà kéréje máa ń ṣe ìrànwọ́ fún ìpèsè ọjà púpọ̀ síi
- Omìnira lọ́wọ́ gbígbọ́kàn lé iṣẹ́ láti ọdọ̀ àwọn ẹlòmìíràn
- Ìṣeéṣe ṣìṣe àṣeyọrí ǹlá
- Àǹfàní owó orí náà lè yọ

### 2.0 Àwọn àmúyẹ Olùdáṣẹ́sílẹ̀

Ní ojú tọ̀nà láti ṣe àṣeyọrí, olùdáṣẹ́sílẹ ye kí ó ní àwọn àmúyẹ yìí

### 2.1 Ọkàn tó ń wá àlàfo

Àlàfo ni àwọn ìpèníjà tó mú ire lọ́wọ́ tó ń mú ìpòǹgbẹ fún ọjà, iṣẹ́ tàbí òwò tuntun. Ó pẹ̀lú níní oore-ọ̀fẹ́ sí owó, ibi-iṣẹ́, ẹ̀kọ́ abbl.

Olùdáṣẹ́sílẹ̀ máa ń fimú fínlẹ̀ àti ṣe ìdámọ̀ àwọn àwọn àlàfo tó fojú hàn. Yóò ṣe àmúlò àwọn àǹfàní àlàfo náà tí yoò sì sọ ọ́ di òótọ́ àti àṣeyọrí.

.

### 2.2 Fífi àya rán an láti ṣe àṣeyọrí

Ollùdáṣẹ́sílẹ̀ máa ń ṣa apá láti mú kí àfojúsùn rẹ̀ ṣe àṣeyọrí , ó máa ń fàyà rán an kìí sì jẹ́ kí àwọn ewu, ìdíwọ́ àti ìṣòro ṣe ìdíwọ́ fún òun láti mú gbogbo àfojúsùn rẹ̀ ṣe àṣeyọrí.

### 2.3 Kíkojú ewu nínú ìdókòwò

Ollùdáṣẹ́sílẹ̀ tó pèrègedémáa ń :

- Ní àfojúsùn ibi tí ewu ìkùnà tó mọ níwọ̀n wà tí yóò sì gbé ìgbésẹ̀ láti kojú ewu tó mọ́gbọ́n dání
- Ní ìfọkànbalẹ̀ lẹ́yìn tí isẹ́ bá yanjú dáa dáa
- Kìí bẹ̀rù ohun tí ayé tàbí àwọn oníyèméjì máa sọ
- Fọwọ́ sọyà láti gba gbogbo àre àti ẹ̀bi ìgbésẹ̀ tó bá gbé

### Pàtàkì kíkojú ewu

- Mú kí o ní ìgboyà nínú ara rẹ
- Mú kí o ní ìmọ̀lára jíjẹ́ olórí
- Yóò ru ọ́ sókè gidi gan láti yanjú iṣẹ́ a fi fún ọ dáadáa

### 2.4 Ṣíṣe àfẹ́rí ìpéye àti ìdángájíá nínu ohun gbogbo

**Ìdángájíá:** Dídáńgájíá pípèsè nǹkan láì fi ohun púpọ̀ ṣòfò

**Ìpéyè-tó túnmọ̀ sí**: Ìgbésẹ̀ tó ń tẹ̀síwájú nípa ẹ̀kọ́, ìfikùlukùn, dídíwọ̀n àti mímú ọjà tàbí iṣẹ́ dára síi láti bá àìní àwọn ònrajà pàdé ní ọ̀nà tí ó tayọ ìrètí ònrajà

**Ṣíṣàmúlọ̀ àkókò dáa dáa:** èyí túnmọ̀ sí ìwọn ọgbọ́n, àyínìke àti ohun èlò tí à ń lò láti ṣàmúlọ̀ àkókò dáa dáa nígbà tí a bá ń ṣiṣẹ́ tọ àṣeyọrí iṣẹ́ kan pàtó àti àlá wa. Ṣíṣàmúlọ̀ àkókò dáa dáa ni mímú ohun tó níye dáadáa jáde nínú àkókò rẹ àti láti fi tún ìgbéwọn-tó ayé rẹ. Lákọ̀ọ́kọ́, Ṣíṣàkóso

### 2.5 Wíwá Ìmọ̀ láti máa léwájú àwọn yòókù

Àwọn olùdaṣẹ́ṣílẹ̀ tó peregedé kìí gbára lé àròbájọ lásán bẹ́ẹ̀ ni wọn kìí gbára lé àwọn ẹlòmìíràn fún ìmọ̀. Dípò bẹ́ẹ̀, wọ́n a lò àkókò wọn láti wá ìmọ̀ kíkún nípa àwọn oníbàárà wọn, àwọn orogún wọn, àwọn olùpesè ọjà, ẹ̀rọ tí wọn nílò àti ọjà. Ṣíṣe àkójọ ìmọ̀ tó tan mọ́ wọn ṣe pàtàkì láti rí i dájú pé olókòwò gbé àwọn ìgbèsẹ̀ tó ṣe pàtàkì; ọjà, ìpesè ọjà, amáyédẹrùn, àkóso òwò, ìṣúná àti ofin ṣíṣe.

### 2.6 Níní ìlépa nípa ṣíṣe àmúlò àǹfàní

Ìlépa ni ibi ìdoríkọ tàbí àfọkàntẹ̀ ọlọ́jọ́pípẹ́ tí ó fẹ́ ṣe àṣeyọrí níbẹ̀. Kìí wà ní gbòógì tó láti ní òdiwọ̀n. Ó fẹ̀ gbòòrò, kò ní òdiwọ̀n àkókò, ó sì jẹ́ ohun tí àwọn ènìyàn máa ń lépa nípa mímú àwọn àfojúsùn wọn ṣẹ léyìí tí yóò padà ṣara jọ láti mú àlá rẹ ṣẹ

Àfojúsùn- máa ń ní òdiwọ̀n, ó sì máa ń jẹ́ pàtó. Wọ́n lè jẹ́ àfojúsùn àṣejáde, ó sì lè jẹ́ èyí tó rọ̀ mọ́ ìhùwásí. Ṣùgbọ́n ju gbogbo rẹ̀ lọ, wọ́n ní òdiwọ̀n , wọ́n jẹ́ pàtó, wọ́n jẹ́ ṣókí. Ronú nípa ohun tí à ń pè ní nǹkan. "o lè fi ọwọ́ kàn án , ó sì lè fojú rí i . Olùdáṣẹ́sílẹ̀ gbọdọ̀ ní àfojúsùn àti ìlépa tí ó jẹ́ pàtó, tí ó ní òdiwọ̀n, tí ó wúlò, tí àkókò sì ń ṣe atọ́na rẹ̀.

### 2.7 Ṣíṣètò láti máṣe kùnà

Ètò ṣíṣe ni ṣíṣe ìpinnu nípa ọjọ́ iwájú lórí kín ni o fẹ́ ṣe, ìgbà wo lo fẹ́ ṣe é, báwo lo ṣe fẹ́ ṣe é, ta ló fẹ́ ṣe é, àwọn ohun èlò wo lo fẹ́ fi ṣe é. Olùdáṣẹ́sílẹ̀ tó yakin máa ń to àwọn akitiyan àti àkọsílẹ̀ torí wọ́n lè wúlò fún àwọ ìṣẹ̀lẹ̀ tí a kò retí.

### 2.8 Yíyínikọ́kàn padà àti síso ènìyàn pọ̀ ní àìkáàárẹ̀

Yíyínikọ́kàn padà

- Ọ̀nà láti mú kí ènìyàn gbà láti wá nǹkan tàbí ṣe ìpinnu tí yóò pé ọ
- Ṣíṣe àwọn akitiyan tàbí fífi ara mọ́ èrò nìpa iyàn jíjà, ríronú jinlẹ̀, tàbí àrògún; fún ìyípadà ọkàn
- Láti ṣe àṣeyọrí nínú ènìyàn ṣe nǹkan tàbí fara mọ́ nǹkan; láti jèrè ọkan ẹnìkan sọ́dọ̀ rẹ, nípa àjọrò tàbí lílo àgbára ẹni
- Láti mú ènìyàn gba nǹkan gbọ́, rọ ènìyàn tàbí borí nǹkan jálẹ̀.

### 2.9 Niní ìgbóyà nínú ara ẹni láti rí ẹsẹ̀ walẹ̀

Ìgbóyà-nínú-ara-ẹni ni ipò ìdánilójú pé ìgbésẹ̀ tí o gùn lé ni ó dára jù láti kojú ìpènijà tó wà nílẹ̀. A lè ṣàlàyé ìgboyà gẹ́gẹ́ bi i ipò tí èrò àti ìmọ̀lára ọkàn wà. Ìgbóyà-nínú-ara-ẹni ni níní ìgboyà nínú ara ẹni nígbà tí a bá ń ṣe àgbéyẹ̀wò ìkápá. Àpọ̀jù-ìgboyà ni níní ìgboyà tí a kò ṣiṣẹ́ fún nípa gbígbàgbọ́ pé nǹkan tàbí ẹnìkan ní agbára ìṣe nǹkan láì rí bẹ́ẹ̀.

### 2.10 Títẹ́tí sí àwọn ẹlòmíràn láti ṣe ìpinnu tó tọ́

Olùdáṣẹ́sílẹ́ kìí súré gbé èrò rẹ̀ lé àwọn ẹlòmìíràn lórí. Kàkà bẹ́ẹ̀, yóò tẹ́tí sí àwọn ẹlòmìíràn ní agbègbè tí wọ́n ti lẹ́nu, ṣírò ìmọ̀ràn wọn gẹ́gẹ́ bí èrò wọn ṣe mọ, yóò sì ṣe ìpinnu tó mọ́gbọ́n dání.

### 2.11 Fífi ìwà aṣíwájú hàn nípa àpẹẹrẹ fifi lélẹ̀

Olùdáṣẹ́sílẹ́ kìí kàn ṣe nǹkan fúnra rẹ̀ nìkan, ṣùgbọ́n ó máa ń ṣe nǹkan nípasẹ̀ àwọn ẹlòmìíràn. Olùdáṣẹ́sílẹ́ máa ń ru àwọn ẹlòmìíràn sókè, mú orí wọn wú, ó sì máa ń darí àwọn ẹlòmìíràn láti ṣe ojúṣe tí a fi fún wọn lójú ọjọ́.

# ẸKỌ 10

# Ìdarí Àti Ìṣàkóso Okòwò tó Yanjú



### Ètò fún Abala Ẹ̀kọ́

Ètò fún abala yìí jẹ́ atọ́nà. Àwọn olùkọ́ni lè ṣe àtúnṣe sí èyíkéyìí abala láti mú kí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú ìrírí wọn lẹ́nu iṣẹ́. Àwọn ìbéèrè àgbéyẹ̀wò gbọdọ̀ jẹ́ bíbèèrè kí wọ́n tó ṣe ìgbéléwọ̀n.

---

**Àwọn àfojúsùn gbòógì :**

**Ní ìparí ẹ̀kọ́ yìí, ó yẹ kí àwọ akópa lè;**

- Ní òye ìdarí nínú àkóso okòwò
- Ṣe ìdámọ̀ àwọn àwòmọ́ adarí
- Dárúkọ àwọn ọ̀nà ìdarí
- Ní òye ipa pínpín ojúṣe nínú ìdarí okòwò
- Ṣe ìdámọ̀ àwọn àwọn ìpènijà adarí àti ọ̀nà láti yanjú wọn

---



# ÌFÁÀRÀ

Ní ìṣàkóso, ìdarí túnmọ̀ sí pípèsè ọ̀nà àti ìran fún ikọ̀ kan. Ìdarí kò kan bóyá akọ tàbí abo ni ènìyàn. Àwọn obìnrin jẹ́ adarí tí wọn yóò sì máa tẹ̀síwájú láti máa kó ipa adarí nínú òkòwo ìpèsè oúnjẹ. Jíjẹ́ alákòóso kò papọ̀ mọ́ jíjẹ́ adarí. Iṣẹ́ ni Alákòóso jẹ́. Ọgbọ́n inú ni a fi ń darí. Adarí máa ń ní ìran, ní ọ̀pọ̀ ìgbà adarí rere kìí sábà jẹ́ ẹni tó wà lókè ṣùgbọ́n gbogbo ẹni tó bá wà nípòni ó yẹ kó jẹ́ adarí.



### Àwọn Àwòmọ́ Adari Rere

- **Ìgboyà:** Láti darí àwọn ẹ̀lòmìíràn , o nílò láti ta ìgboyà wọn jí. ọ̀nà tí ó dárá jù láti ṣe èyí ni níní ìgboyà nínú ara ẹni. Àwọn ènìyàn máa ń ìgboyà nínú adarí tí ń fẹ́ láti ṣe àṣìṣe kí ó sì kọ́gbọ́n lára wọn.
- **Ìfikùnlukùn:** Ẹ̀yí kó 70% ojúṣe olórí nínú ìṣàkóso okòwò. Olórí gbọ́dọ̀ ní ìbáṣepọ̀ tó dára pẹ̀lú àwọn ènìyàn, kí ó sì ní àgbára láti bá àwọn ọmọ ẹ̀yìn sọ̀rọ̀ dáadáa
- **Òtítọ́:** Olórí tó ń gbìyànjú láti máa fi nǹkan pamọ́, da ọwọ́ bo àṣìṣe tàbí da ẹ̀bí lórí àwọn òṣìṣẹ́ kò fi ààyè ìjólóòótọ́ àti ìgboyà sílẹ̀. Àkóyawọ́ àti ìjólóòótọ́ máa ń fún àwọn ọmọ lẹ́yìn ní òye ó sì máa ń mú kí wọn ó jára mọ́ iṣẹ́.
- **Ìfọkànsìn:** Ìfọkansìn ni ọkàn láti lọ́wọ́ sí àti kọjú mọ́ ọ̀n títí tí wọn yóò fi rí èsì tí wọ̀n ń wá. Àwọn olórí máa ńní ìfọkàn sìn sí ohun kan èyí ló sì máa ń mú kí àwọn ọmọ lẹ́yìn ní ìgbàgbọ́ nínú wọn dé àwọn ààyè kan.
- **Àánú:** Olórí nílò láti fi han àwọn òṣìṣẹ̀/ ọmọ ẹ̀ẹyìn pé wọ́n nífẹ̀ẹ́ wọn. kí wọ́n tẹ́tí sí wọn láti mú kí èrò wọ́n yé wọn. Ẹ̀yí máa ń ṣèrànwọ́ láti mú kí ìfọkantánni gbilẹ̀ ó sì máa ń ran ìkópa lọ́wọ́.

### Àwọn ọ̀nà Ìdarí

Àwọn ọ̀nà ìdarí mẹ́ta pàtó ni ó wà nínú ìṣàkóso okòwò tó yanjú, Apàṣẹwàá, Àwarawa, Ayọ̀nda

- **Ìdarí Apàṣẹwàá:** Irúfẹ́ àwọn adarí yìí máa fi ẹ̀rù àti ìhàlẹ̀ darí àwọn òṣìṣẹ́ wọn. Adarí apàṣẹwàá wúlò ní àwọn ibi tó ti jẹ́ pé wọ́n nílò láti máa tẹ̀lé àṣẹ láì bèèrè ìbéèrè. Irú ọ̀nà ìdarí yìí máa ń ṣòro láti lò ní àwùjọ olókoòwò.

- **Ìdarí Àwarawa:** ídarí àwarawa túnmọ̀ sí pé àwọn alákòóso àti òṣìṣẹ́ ṣiṣẹ́ papọ̀ láti ṣe àwọn ìpinnu. Adarí àwarawa gbà pé àwọn ènìyàn kìí ṣe ọ̀lẹ tí wọ́n sì fẹ́ ṣiṣẹ́. Nípa fifi han àwọn òṣìṣṣẹ́ pé o ní àgbẹkẹ̀lé nínú wọn, wọ́n a ni ìgbẹkẹ̀lé tó ga nínú rẹ gẹ́gẹ́ bí i adarí.

- **Ìdarí Ayọ̀nda:** Ìdarí ayọ̀nda ń fẹ́ kí adarí ṣe àgbékalẹ̀ àfojúsùn rẹ̀ fún àwọn alákòóso àti òṣìṣẹ́, tí yóò sì fi wọ́n yọ̀nda wọn láti ṣe iṣẹ́ náà. Ẽyí ń fiàyè sílẹ̀ fún ìmẹ́lẹ́ pẹ̀lú bí ó ṣe jẹ́ pé ọ̀pọ̀ lè má ṣe iṣẹ́ wọn láìsí àmójútó.

### Ìmúdọ́gba àwọn ọ̀nà ìdarí

Kò sí ọ̀nà ìdarí kan tí ó sàn ju ara wọn lọ. Nítorí èyí, adarí gbọdọ̀ mọ èyí tí ó yẹ láti lò lásìkò tó yẹ. Ikọ̀ tí adarí bá jẹ́ alákòóso rẹ̀ máa ń gbájúmọ́ àfojúsùn ju iṣẹ́ lọ. Adarí rere gbọdọ kọ́ láti máa pín iṣẹ́.

### Àwọn ìdí fún iṣẹ́ pínpín

- Kò sí adarí tó lè dá gbogbo rẹ̀ ṣe
- Láti le gbájú mọ́ ìrònú ìmúṣẹ́ṣe
- Ó ń gba àwọn òṣíṣẹ́/ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ láàyè láti jẹ́ akópa
- Ó ń fún òṣíṣẹ́/ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ní àǹfàní láti ṣe àmújáde ẹ̀bùn ara tiwọn náà.

### Ìdari àti ìṣàkóso

- Ní ìmọ̀ àmọ̀dájú nípa ìyàtọ̀ tí ó nílò
- Yí èròńgbà pada di ìṣẹ kí o sì ta àwọn ènìyàn jí láti ṣiṣẹ́ lóri wọn
- Wá ìfọkànsìn nípa ìbánisọ̀rọ̀ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì, òtítọ́ àti òdodo
- Ṣẹ̀dá ààyé fún ẹ̀kọ́, kí àwọn ènìyàn lè mọ pé àṣìṣe ò ní ọ̀gá
- Máa tẹ̀síwájú- ìtẹ̀síwájú ṣe pàtàkì

### Àwọn ìpènijà tó le ṣe ìdíwọ́ fún àwọn obìnrin láti má lè kó ipa olórí àti ọ̀nà láti yanjú wọn

Àwọn ìpènìjà náà pẹ̀lú Ìdẹ́yẹsí, ṣùgbọ́n kò dúró níbẹ̀, ìyàsọ́tọ̀, Ìfojútẹ́mbẹ́lú, ìbéèrè ẹbí àti àìsíàayè

- **Kíkọjú ìjà sí ìdẹ́yẹsí:** Ilépa láàárín àwọn ọkùnrin ni a kà sí agbára, ṣùgbọ́n a kìí fi ojú irú rẹ̀ wo àwọn obìnrin. Àṣeyọrí nínú okòwò kìí ṣe fún ọkùnrin nìkan . O lé ṣe àkójọ okòwò iṣẹ́ àgbẹ̀ oníẹgbẹẹgbẹ̀rún dọ́là .

- **Ṣíṣe àkóso ipa tò pọ̀:** Ọ̀pọ̀ obìnrin tó pọ̀ jú ọkùnrin lọ ló máa ń padà fi okòwò wọn sílẹ̀ láti tọ́jú ẹbí. Kò yẹ kó jẹ́ ọ̀rọ̀ ọmọ tàbí iṣẹ́. Méjèèjì ni ó ṣe pàtàkì

- **Kíkojú ewu:** Ní gbòòrò, àwọn obinrin máa ń ṣọ́ra púpọ̀ fún ewu kíkojú tí àwọn fúnra wọn gan sì máa ń tako ìdájọ́ ara wọn

### Ojútùú tó lè ṣú yọ

- Máa ṣàkóso ìṣẹ̀lẹ̀ kí o sì gbájúmọ́ ibi tí agbára rẹ sodo sí. Máa dáwọ́ lé iṣẹ́ àkànṣe tuntun tí yóò mú ọ sún síwájú
- Kódà tó bá dà bí i pé ẹnikẹ́ni ò tẹ́tí sí ọ, pariwo àníyàn rẹ fún ìdàgbàsókè. Ẹ̀nikan ń gbọ́!!
- **Àiní ìgbàgbọ́ nínú ara ẹni:** pẹ̀lúpẹ̀lú níní ọgbọ́n adarí tó han gedegbe láti lè wa ní ipò gíga, ọ̀pọ̀ obìnrìn máa ń fojú fo ọ̀pọ̀lọpọ̀ àǹfàní

### Ojútùú

- Síso ara wọn pọ̀ mọ́ àwọn obìnrin mìíràn, pàápàá jùlọ àwọn obìnrin tó ti wà ní ipò asíwájú, yóò ran wọ́n lọ́wọ́ láti ní igboyà nínú ara wọn. Kọ́ nípa ìgbìyànjú wọn àti àṣeyọrí wọn.
- Tí àṣà tó wà láwùjọ bá ń da ojú ọ̀rọ̀ rú, wá èsì àìṣègbè lórí ìdáńgájíá rẹ
- Ìpinnu ayé

Kódà bí obìnrin kan bá ní ìgboyà nínú àgbára rẹ̀, ìpinnu ayé ẹni máa ń kópa lórí mímú àdínkù bá ìṣeéṣe dídé ipò aṣíwájú.

### Ojútùú tó lè ṣú yọ

- Jà fún àwọn òfin iṣẹ́ tí tóò ṣe àtìlẹ̀yìn fún bí àwọn obìnrin yóò ṣe máa dé ipò olórí
- Kódà bí ofin kò bá ṣe ìrànwọ́ fún ọ, ṣe àgbéǹde àwọn àwọn obìnrin mìíràn fún àṣeyọrí àti ìdàgbàsókè iṣẹ́ ẹni nípasẹ̀ líléwájú àyípadà láàárin ìgbìmọ̀ tìrẹ náà.

### Àwọn àṣàyàn ọ̀rọ̀ díẹ̀

"Ìṣàkóso jẹ́ ṣíṣe nǹkan dáadáa, Ìdarí ni ṣíṣe àwọn ohun tó tọ́" Peter Drucker
"Ìṣàkóso ṣe pàtàkì ní gígun àkàbà àṣeyọrí; Ìdarí ni yóò fi hàn yálà àkàbà náà fi ara ti ògiri tó tọ́."- Stephen R Covey

# ÌGBÉLÉWỌ̀N FÚN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ SWEAN

### Nípa Ìgbéléwọ̀n yìí

Ìgbéléwọ̀n yóò gbà tó ìṣẹ́jú 5 láti parí. Àwọn ìdáhùn rẹ ṣe pàtàkì láti ràn wá lọ́wọ́ ní mímọ ìmúnádóko ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà.

Àwọn ìdáhùn rẹ kì yóò fi ọ́ hàn, a ó sì ṣe àkójọ dátà gẹ́gẹ́ bíi ti ẹgbẹ́ kan.

**Orúkọ:**______________________________________________________________

**Ẹ̀yà okòwò:** ___________________________________________________________

**Ibùdó:**______________________________________________________________

### Àwọn ìdí fún kíkópa

1. Àwọn ìdí pàtàkì wo ni tó mú yín kópa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí? Dákun mú iye èyí tó bá jọ mọ́ tìrẹ níbẹ̀.

2. Àwọn ẹ̀kọ́ wo ni o ti kọ́?

3. 3Èwo nínú àwọn abala ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà ni o fẹ́ràn jù ? tò wọ́n lẹ́sẹẹsẹ

### DÁKUN ṢE ÌGBÉLÉWỌ̀N ÌMỌ̀ RẸ

4. Òye rẹ nípa aáyan oúnjẹ àti ìfi-èròjá-mú-oúnjẹ-dára-síi  (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

5. Òye rẹ nípa aáyan oúnjẹ àti ìfi-èròjá-mú-oúnjẹ-dára-síi, ìṣàpọ́nlé àti ìpamọ́  (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

6. Òye rẹ nípa àmúyẹ fún ìforúkọsílẹ̀ oúnjẹ lọ́dọ̀ àjọ NAFDAC (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

7. Òyè rẹ nípa àwọn ìpele ìdáńgajíá oúnjẹ (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

8. Òye rẹ nípa títà ẹja àti ẹ̀gẹ́ (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

9. Òye rẹ nípa àkọsílẹ̀ àti ìwé owó (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

10. Òye rẹ nípa ìṣirò owó àti àwọn ìlànà ìṣúná nínú okòwò (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

11. Òye rẹ nípa ìdarí àkóso okòwò tó làlùyọ  (1= òpè, 5= òye kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ṣíwájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |
| Lẹ́yìn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: | ● | ● | ● | ● | ● |

12. Báwo ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ṣe tan mọ́ okòwò rẹ (1= kò tan, 5= ó tan púpọ̀)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ìgbéléwọ̀n | ● | ● | ● | ● | ● |

## ÀMÚLÒ Ẹ̀KỌ́

13. Báwo ni ìgboyà rẹ ṣe kún tó lórí ṣíṣe àmúlò ẹ̀kọ́ tí o ní nínú okòwò rẹ(1= kò sígboyà, 5=Ìgboyà kíkún)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ìgbéléwọ̀n | ● | ● | ● | ● | ● |

## ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

14. Báwo ni o ṣe rí àkóónú ẹ̀kọ́ yìí sí (1= Kò dára rárá, 2= ó dára púpọ̀)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ìgbéléwọ̀n | ● | ● | ● | ● | ● |

## ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

15. Bá wo ni àwọn wọ̀nyìí ṣe ràn yín lọ́wọ́ láti kọ́ ẹ̀kọ́

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ẹ̀kọ́ | ● | ● | ● | ● | ● |
| Páwá pọ̀ìntì | ● | ● | ● | ● | ● |
| Ìwé ìléwọ́ | ● | ● | ● | ● | ● |
| Ìjíròrò láàárín ẹgbẹ́ | ● | ● | ● | ● | ● |
| Àwn Ìdánrawò | ● | ● | ● | ● | ● |

16. Dákun ṣe ìgbéléwọ̀n olùdánilẹ́kọ̀ọ́ rẹ ní àwọn abala wọ̀nyìí (1=kò dára rárá, 5= ó dára púpọ̀)

| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
|---|---|---|---|---|---|
| Ìmọ̀ nípa ẹ̀kọ́ | ● | ● | ● | ● | ● |
| Fífi ìfẹ́ hàn sí ẹ̀kọ́ | ● | ● | ● | ● | ● |
| Ṣíṣe àfiwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Pẹ̀lú ipa iṣẹ́ rẹ | ● | ● | ● | ● | ● |
| Níní ìmọ̀ nípá àwọn ohun tí o nílò | ● | ● | ● | ● | ● |
| Dídáhùn àwọn ìbéèrè | ● | ● | ● | ● | ● |

**Àwọn àwílé ìkádìí**

17. Ǹjẹ́ o máa tọ́nà ẹ̀kọ́ yìí fún àwọn akẹgbẹ́ rẹ?

- ◯ Bẹ́ẹ̀ni
- ◯ Rárá
- ◯ Kò dájú

**18. (Àwọn) Àwílé**

_______________________________________________________________________

_______________________________________________________________________

_______________________________________________________________________

_______________________________________________________________________

_______________________________________________________________________

_________________________

IITA

Transforming African Agriculture

The International Institute of Tropical Agriculture is a nonprofit organisation that works with partners to enhance crop quality and productivity, reduce producer and consumer risks, and generate wealth from agriculture, with the ultimate goals of reducing hunger, malnutrition, and poverty.

www.iita.org

Small & Medium Enterprises Development Agency Of Nigeria

FIIRO

NEPC

NIGERIAN EXPORT PROMOTION COUNCIL